# DÍDÁWÀ PẸ̀LÚ ỌLỌ́RUN

## ÌWÉ ÌSÌN OJOOJÚMỌ́

ROSE OF SHARON GLORIOUS MINISTRY INT'L

2021

# DÍDÁWÀ PẸ̀LÚ ỌLÓRUN

**Ìwé ìsìn ojoojúmọ́**

Copyri©ht 2014 by Rose of Sharon Glorious Ministry Int'l

ISSN: 2360-8617

Àtẹ̀jáde nì orìlẹ-èdẹ̀ Nigeria láti ọwọ́:

ROSE OF SHARON GLORIOUS MINISTRY INT'L

Akó gba ẹnikẹ̀ni lááye láti ṣe àtúnkọ tàbì àtúntẹ íwé yí ní ònà kọnà láì gba àṣẹ lọ́wọ́ àwọn olùtẹ̀ íwé yí yàtọ̀ sí tí abá fẹ lo diẹ ninu íwé ìròhìn tàbí awọn íwé pélébé miran.

*Fún àlàyé síwájú si tàbí igbani laye, ẹkàn sí wa ní:*

*14, Ogunlana Drive, Surulere, Lagos.*

*Tel: +234 (0) 9070004210, +2347013901110, +2347013901111*

*email: info@rosgmi.org website: www.rosgmi.org*

Ilé iṣẹ ti o tẹ̀we yi ni:

**DIGITALREALITY PRINT LTD.**

**78-89, Commercial Avenue, Oyadiran Estate, Sabo-Yaba, Lagos State.**

**Tel: +234 708 860 2607-15**

www.digitalrealityprintlimited.com

# ỌRỌ ÀKỌSỌ

Àsìkò tó gíríkì ni ki ènìyàn kó kọjúmọ́ Ọlọ́run láìwò ìbòmíràn, nínú ẹ̀sín ìgbàgbọ́ nìkan ni ati léè ri wípé Ọlọ́run gbogbo ayé fẹ́ràn láti máa ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwon ẹ̀dá ọwọ́ rẹ̀. Eléyìi fara hàn nínú ìbáṣepọ̀ láàrin Ọlọ́run àti Ádámù òhun Éếfà nínú ọgbà Édẹ́nì nínú Ìwe Jẹ́nẹ́sìsì.

Lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n bá ti sinmi nínú ọgbà, Ọlọ́run a máa ṣàbẹ̀wò wọn lọ́wọ́ ìrọ̀lẹ́. Gbogbo ìgbà tí ìbẹ̀wò yi n lọ lọ́wọ́ ni ọmọ ènìyàn ńṣe àṣeyọrí ní gbogbo ọ̀nà rẹ̀. Títí di àsìkò tí wọ́n ṣe àìgbọràn ní ìbáṣepọ̀ wọ́n pẹ̀lú ẹ̀mí ṣe wọ́n lóore.

Láti ìgbà ìṣubú yi ni ó ti di ohun ìnira fún ènìyàn láti jẹ ìgbádùn ìbáṣepọ̀ yi. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn nkan ni ó má ńgba àsìkò wa, tí wón kìí jẹ́ kí á gbádùn ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Ẹlẹ́ẹ̀dá wa, bẹ́ẹ̀ni ohunkóhun kò le ṣe pàṣípàarọ̀ igbádùn áti ìdàgbà nínú ti ẹ̀mí tó wà nínú ìbáṣepọ̀ àwa àti Ọlọ́run.

Ìwé yi tí ó jẹ ìwé ojoojúmọ́ ni àtẹ̀gùn sí íwájú Ọlọ́run ni ibi ti Ọlọ́run ti máa ń sọ̀rọ̀, ṣe ìtọ́sọ́nà áti yí àwa ọmọ rẹ̀ padà. Gẹ́gẹ́bi òye mi, ìwe ìrìn ẹ̀mí yi fún ìdàgbàsókè ni a ti ọwọ́ ẹ̀mí kọ láti mú ènìyàn wá sí iwájú Ọlọ́run, dàgbà nínú ẹ̀mí, pàápá ni irú àsìkò yìi ti òdodo ti di imi eégún.

Ẹ̀yi wá jẹ́ ki o jẹ́ ohun ti ó bójú mu láti dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run lóri alátòjọ àgbà ìwé yìi, Ìyá ààfin Fọ́lọ́runṣọ́ Alákijà fún iṣẹ́ rere ti ó gbà láàyè ki Ọlọ́run ṣe nípa ṣẹ̀ rẹ̀. Àìkáàrẹ̀ wọn àti ìfarajìn ni ó jẹ́ ki ìwé yìi ṣe di títẹ̀. Ki iṣẹ́ Ọlọ́run ti a gbé léwọn lọ́wọ́ máa gbòoró síwájú si.

Ní àisọ̀rọ̀ ní gbònkélé, mole fọwọ́gbáyà fuń gbogbo àwa oníìgbàgbọ́ nípa ìwé àkójọ ẹsẹ̀ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, orin tóní ìmísí, àti ìtọ́ni. Ní àìṣiyè méjì yó ràn gbogbo oníìgbàgbọ́ lọ́wọ́ láti fi gbogbo ọkàn papọ̀ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́run

Àdúrá wá ní wípé bí o ṣé n ṣe àṣàrò nípa lílo ìwé yí, kí o jẹ́ àjẹ́yo oúnjẹ ẹ̀mí, bẹ́ẹ̀ni kí ó leè ṣe ìfẹ Ọlọ́run fún ayé rẹ.

**Ẹni ọ̀wọ̀ gidi gan Adébọ́lá Ojófẹ̀itìmí**

# ORÍ ÌTỌ́KASI

a) Orí ìgbáṣẹ̀
b) Ọ̀rọ̀ àkọ́sọ
d) Ìàbíìlì ìtọ́kasí
e) Ìtọ́ni sí àdúrà
f) Àdúrà ìbèrè àti ìjẹ́wọ́ ìgbàgbọ́

**ORÍ**

| | |
|---|---|
| Kinni | Àdúrà fún agbègbè ìṣòwò |
| Ìkejì | Ìwà Ojoojúmọ́ tí n sọni d'aṣẹ́gun |
| Ìkẹta | Dídúró lórí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run |
| Ìkẹ́ẹ̀rin | Kóró ọgbọ́n |
| Ìkàárún | Ìgbésí ayé ìyìn |
| Ìkẹfà | Yíinyin aláàfin ọ̀run |
| Ìkèje | Ìwáàdí ọkàn: wíwá ìdáríjìn |
| Ìkéjọ | Ìwáàdí Okan: wíwá Àánú |
| Ìkẹsan | Ìtọ́ni àtòkèwá |
| Ìkẹẹ̀wá | Àdúrà Olúwa |
| Ìkọkànlá | Ẹni tí mo jẹ́ nínú Krístì |
| Ìkejìlá | Ìṣìpẹ̀ |
| Ìkẹtàlá | Ìfẹ́ ayérayé tí mo ní sí Ọlọ́run |
| Ìkẹrìnlá | Mímọ ìfẹ́ Ọlọ́run |
| Ìkẹẹ̀dógún | Dídá agbo májẹ̀mú burúkú dànù |
| Ìkẹrìndínlógún | Fífi àṣẹ hàn |
| Ìkẹtàdinlógún | Òmìnira lọ́wọ́ ìjogún burúkú láti ìrandíran |
| Ìkejìdínlógún | Àìgba ẹ̀rù ní àyè |
| Ìkọkàndínlógún | Àwọn orílẹ̀ èdè |
| Ogún | Ààbò àti ìtúnisílẹ̀ láti ọwọ́ ẹ̀mí burúkú |
| Ìkọkànlélógún | Ìpèsè |
| Ìkejìlèlógún | Àwọn ọmọdé |
| Ìkẹtàlèlógún | Ìwòsàn |
| Ìkẹrìnlélógún | Ìràpadà |
| Ìkẹẹ̀dọ́gbọ̀n | Ìrànwọ́ ní àsìkò àìní |

| | |
|---|---|
| Ìkẹrìndínlọ́gbọ̀n | Ẹnìkejì ẹni níti ọ̀rọ̀ ìdílé |
| Ìkẹtàdínlọ́gbọ̀n | Àṣeyọrí nínú ìdánwò |
| Ìkejìdínlọ́gbọ̀n | Ìsèso |
| Ìkọkàndínlọ́gbọ̀n | Dídúró de ìyanu |
| Ọgbọ̀n | Ọ̀rọ̀ ẹjọ |
| Ìkọkànlélọ́gbọ̀n | Ojúrere nínú iṣẹ́ àti òkòwò |
| Ìkejìlélọ́gbọ̀n | Àṣeyọrí nínú ìdánwò |
| Ìkẹtàlélọ́gbọ̀n | Àánú nínú ìrìn àjò |
| Ìkẹrìnlélọ́gbọ̀n | Ìtúsílẹ̀ nínú ìṣòro |
| Ìkarùndínlógójì | Ìṣẹ́gun àti ìdúpẹ́ |
| Ìkẹ́rìndínlógójì | Ìtọ́ni Bíbélì àgbà yípò ọdún fún ìrìn tí ó súnmọ́ Olúwa. |

# ÌTỌ́NI ÒJOOJÚMỌ́



**I** - Ìyìn àti ìdúpẹ

**S** - Síso ọ̀rọ̀ jáde. Àwárí ọkàn, dídáríjìn ara ẹni àti àwọn yóókù, títọrọ ìdáríjìn lọ́wọ́ Ọlọ́run

**I** - Ìdúpẹ́. Fífi óòre rẹ̀ hàn nínú ayé rẹ, ẹbí, okòwò àti iṣẹ́.

**N** - Ní àdúrà ìṣìpẹ̀ àti ìlàgàta fún orílẹ̀ èdè, ẹbí àti ara ẹni.

Máṣe jẹ́ kí ohunkóhun dí ọ lọ́wọ́ láti ṣiṣẹ́ àti sin Ọlọ́run

# ÀDÚRÀ ÌBẸ̀ẸRẸ̀ ÀTI ÌJẸ́WỌ́ ÌGBÀGBỌ́

1. Olúwa ṣí ojú mi láti rí ohun mèremère nínú òfin rẹ́

2. Ṣími ní ojú ẹ̀mi àti tí ara kín lèri jú ẹléran ara lọ

3. Mo jọ̀wọ́ ọkàn àti ibi èrò mí fún ọ̀rọ̀ rẹ́ kí n lè di ẹni tí o fi mí pè, kiń ni ohun tí o ní ó jẹ́ tèmi, kiń sìle ṣe ohun tí o ní mo lè ṣe

4. Fúnmi ní óòre ọ̀fẹ́ láti rìn, kí n sìle ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ gẹ́gẹ́bi ìfẹ́ rẹ, fún mi ní óòre ọ̀fẹ́ láti mọ ọ̀nà rẹ, iṣẹ́ rẹ, ọ̀rọ̀ rẹ, ọgbọ́n rẹ, kí nsì ní ìrírí agbára iṣẹ́ ìyanu rẹ

5. Fún mi ní okun ẹ̀mí àti agbára fún iṣẹ́ láti mú ìpinu rẹ ṣẹ, óòre ọ̀fẹ́ láti wọnú ìrírí ọ̀tun àti ìgbàgbọ́, òye tìrẹ tó tayọ àti ìfẹ́ rẹ.

6. Jẹ́ kí ògo Ọlọ́run bò mí

7. Jẹ́ ki ayọ̀ Ọlọ́run yí mi ká

8. Jẹ́ kí òjìjí Ọlọ́run kó má wà pẹ̀lú mi

9. Jẹ́ kí ẹwà Ọlọ́run dàṣọ bòmi.

10. Jẹ́ ki ẹ̀mí Ọlọ́run kún mi

11. Jẹ́ kí agbára Ọlọ́run tamíjí

12. Mojẹ́wọ́, mo sì pàṣẹ wípé gbogbo ìrètí mí ní yóò di mímúṣẹ pẹ̀lú èso ètè mi (ìwe òwe oríkejìdínlógún, ẹsẹ̀ ogun)

13. Mo gbàdúrà pé iṣẹ́ ìránṣẹ mi ní ayé yìí yóò mú okun, ìjọ Ọlọ́run yóò fi ìdí múlè, àyà yóò pá sàtánì, a ó sì yin Jésù lógo. Ní orúkọ Jesù.

## ORÍ KÍNNI

# ÀDÚRÀ FÚN AGBÈGBÈ ÌSỌ̀WO



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dáfidì 90:17**
Jẹ́ kí ojurere OLÚWA Ọlọ́run wa wà lára wa, fi ìdí iṣẹ́ ọwọ́ wa múlẹ̀, jẹ́ kí iṣẹ́ ọwọ́ wa fi ìdí múlẹ̀.

**Filippì 4:13**
Mo lè ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹni tí ó ń fún mi ní agbára.

**Orin Dáfidì 128:2**
O óo jèrè iṣẹ́ ọwọ́ rẹ, ayò ṇ́ bẹ fún ọ, yóo sì dára fún ọ.

**Àwọn Oníwààsù 9:10**
Ohunkohun tí o bá ti dáwọ́ lé, fi gbogbo agbára rẹ ṣe é nítorí, kò sí iṣẹ́, tabi èrò, tabi ìmọ̀, tabi ọgbón, ní isà òkú tí ò ń lọ.

**Ìwé Òwe 12:11**
Ẹni tí ó bá ń dáko yóo ní òpọ̣ oúnjẹ, ṣugbọn ẹni tí ó bá ń lo àkókò rẹ̀ lórí ohun tí kò lérè, kò l'ọgbón lórí.

**Tẹsalóníkà Kejì 3:10**
Nítorí nígbà tí a wà lọ́dọ̀ yín, a pàṣẹ fun yín pé bí ẹnikéni bá kọ̀ tí kò ṣiṣẹ́, ẹ má jẹ́ kí ó jẹun.

## Àdúrà

- Jésù Olúwa, bí mo ṣé ńwọ ibi iṣẹ́ yí, mo nwọ̀ pẹ̀lú ọwọ́ rẹ. Mo pàṣẹ àlááfià, oore ọ̀fẹ́ àti ètò sí gbogbo agbègbè yí. Mo jẹ́wọ́ rẹ bí Olúwa lóri gbogbo èrò, ọ̀rọ̀, ète tí yóò máa lọ ní gbogbo agbègbè yí.
- Jésù Olúwa, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ fún àwọn ẹ̀bùn tí o fún mi. Nkò rí wọn bí nkan yẹpẹrẹ, ṣùgbọ́n mo pinu láti máa lò wọ́n bí ó ti tọ́. Fí òtítọ́, ẹwà, ìṣípayá àti ọgbọ́n lórí ibi tí màá kọ́ bíi ilé àwon àṣàyàn ọgbọ́n àtinúdénú, ọgbọ́n Ọlọ́run, okun tóbẹ́ẹ̀ tí àwon ìlàkàkà mi yóò mú ìyìn wá fún ọ
- Olúwa, tọ́ mi tí ìpòrúùrù bá wà, fún mí ní okun tí ó bá rẹ̀ mí pẹ̀lú agbára ẹ̀mí mímọ́ rẹ. Máa ṣe atọ́nà tí màá gbà ṣe mú ìrètí, ìyè àti ìgboyà wá sí ọ̀nà gbogbo àwọn tí màá bá pàdé ní ọ̀nà. Olúwa, bí iṣẹ́ òní ṣe lè le tó, jẹ́ kí ń lee sinmi nínú rẹ, nínú ọwọ́ agbára àti ìfarahàn rẹ. Àmín.

## Àwàda

### Fìlà tò sọnu

Ìyá àgbà kan nwo Ọmọ Ọmọ rẹ̀ ńṣe eré ní etí òkun, bí ìjì òkun ṣe gbe ọmọ yìí lọ nìyí. Ìyá bá bẹ̀rẹ̀ àdúrà pé kí Ọlọ́run gba ọmọ òun là, kí òkun gbé yìí padà. Àfi bíi idán, ìjì omi bá gbé ọmọ yi padà, ìyá bá tún wòkè sí ọ̀run, lóbá wípé fìlà ọmọ náà nkọ́?

# ORÍ KEJÍ

## ÀWỌN ÌWÀ OJOOJÚMỌ́ TÍ Ó MAA Ń SỌ ÈNÌYÀN DÍ AṢẸ́GUN

## Ṣe Àṣàrò

1. **Sọ ọkàn rẹ dí ọ̀tun**

   **-Fílíppì 4:8**

   Ní ìparí, ẹ̀yin ará, gbogbo nnkan tí ó bá ń ṣe òtítọ́, gbogbo nnkan tí ó bá lọ́lá, gbogbo nkan tí ó bá tọ́, gbogbo nnkan tí ó bá jẹ́ mímọ́, gbogbo nnkan tí ó bá fa eniyan mọ́ra, gbogbo nkan tí ó bá ní ìròyìn rere, àwọn ni kí ẹ máa kó lé ọkàn.

2. **San ìdámẹ̀wá rẹ**

   **-Malaki 3:10**

   Ẹ mú gbogbo ìdámẹ́wàá yín wá sí ilé ìṣúra, kí oúnjẹ baà lè wà ninu ilé mi. Ẹ ṣe bẹ́ẹ̀ kí ẹ fi dán mi wò, bí n kò bá ní ṣí fèrèsé ọ̀run sílẹ̀, kí n sì tú ibukun jáde fun yín lọpọlọpọ, tóbẹ́ẹ̀ tí kò ní sí ààyè tó láti gbà á.

3. **Dáríji àwọn tí o sẹ̀ ọ́**

   **- Kolosse 3:13**

   Ẹ ní ìfaradà láàrin ara yín. Ẹ máa dáríjì ara yín bí ẹnikẹ́ni bá ní ẹ̀sùn kan sí ẹnìkejì rẹ̀; gẹ́gẹ́ bí Olúwa ti dáríjì yín bẹ́ẹ̀ gan-an ni kí ẹ̀yin náà máa ṣe sí ara yín.

4. **Gbé ìgbé ayé àdúrà**

   **-Jeremaya 29:12**

   Ẹ óo ké pè mí, ẹ óo gbadura sí mi, n óo sì gbó adura yín.

   **Tẹsalóníkà Kinni 5:17**

   Ẹ máa gbadura láì sinmi.

5. **Wà nínú ayọ̀**

   **-Nehemaya 8:10**

   Nehemaya bá sọ fún wọn pé, “Ẹ máa lọ, ẹ jẹ ẹran ọlọ́ràá, ẹ mu waini dídùn, kí ẹ sì fi oúnjẹ ranṣẹ sí àwọn tí wọn kò bá ní, nítorí pé ọjọ́ mímọ́ ni ọjọ́ òní jẹ́ fún OLÚWA wa, ẹ má sì banújẹ́, nítorí pé ayọ̀ OLÚWA ni agbára yín.”

6. **Kún fún Ẹmi mímọ́ nígbà gbogbo - Efesu 5:18**

   Ẹ má máa mu ọtí yó, òfò ni. Kàkà bẹ́ẹ̀, ẹ kún fún Ẹ̀mí Mímọ́.

7. **Ka ọ̀rọ̀ Ọlọ́run**

   **-Timoti Keji 2:15**

   Sa gbogbo ipá rẹ láti ṣe ara rẹ ní ẹni tí ó yege níwájú Ọlọ́run, gẹ́gẹ́ bí oníṣẹ́ tí kò ṣe ohun ìtìjú pamọ́, tí ó ń sọ ọ̀rọ̀ òtítọ́ bí ó ti yẹ.

**8. Fi ẹ̀jẹ̀ Jésù bẹ̀bẹ̀**

**-Ifihan 12:11**

Wọ́n ti fi ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́ Aguntan ati ẹ̀rí ọ̀rọ̀ tí wọ́n jẹ́ ṣẹgun rẹ̀. Nítorí wọn kò ka ẹ̀mí wọn sí pé ó

**10. Yi padà kúrò nínù ìwà ìbí**

**- Orin Dafidi 34:12-14**

Ta ni ń fẹ́ ìyè ninu yín, tí ń fẹ́ ẹ̀mí gígùn, tí ó fẹ́ pẹ́ láyé? Ẹ ṣọ́ ẹnu yín, ẹ má sọ̀rọ̀ burúkú, ẹ má sì jẹ́ kí ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn ti ẹnu yín jáde. Ẹ yàgò fún ibi, rere ni kí ẹ máa ṣe; ẹ máa wá alaafia, kí ẹ sì máa lépa rẹ̀.

**11. Má ṣe yára láti bínú -Iwe Owe 16:32**

Ẹni tí kì í tètè bínú sàn ju alágbára lọ, ẹni tí ń kó ara rẹ̀ níjàánu sàn ju ẹni tí ó jagun gba odidi ìlú lọ.

**12. Jẹ́ ẹni tó ń njọ́sìn -Orin Dafidi 29:2**

Ẹ fún OLÚWA ní ògo tí ó yẹ orúkọ rẹ̀, ẹ máa sin OLÚWA ninu ẹwà mímọ́ rẹ̀.

**13. Rìn nínu ìfẹ́ -Efesu 5:2**

Ẹ máa rìn ninu ìfẹ́ gẹ́gẹ́ bí Kristi ti fẹ́ wa, tí ó fi ara òun tìkararẹ̀ rú ẹbọ olóòórùn dídùn sí Ọlọ́run nítorí tiwa.

## Àwọn ohun tí óyẹ kí á se àti ohun tí a kò gbọdọ̀ se

- Ní òye agbára àti ìhùwàsí ẹ̀mí mímọ́ kí ó sì wá won ri
- Gbé ìfẹ́ àti ìwàpẹ̀lẹ́ wọ̀ bí ẹ̀wù
- Ní ojú àánú àti ọ̀kan fún àwọn ẹlòmíràn
- Ní ìrètí ìyípadà
- Gba ọ̀rọ̀ Ọlọ́run gbọ́, k áà déedé kí o sì jẹ́ kí o gbilẹ̀ ní ọkàn rẹ
- Ní òye agbára tí ó jí Jésù dìde nínú òkú, tí ó sì fi jókò ní ọwọ́ ọ̀tún Ọlọ́dùmarè
- Ní òye agbára Jésù tí ó ń ṣiṣẹ́ ninú rẹ
- Ní òye wípé bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé a kàn mọ́ àgbélébu ní àìlera, ó ji dìde ní agbára, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, bí àwa ná ṣe jẹ́ aílàrera, àwa náà le gbé ìgbé ayé pẹ̀lú agbára Ọlọ́run
- Há ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sí oókan àyà rẹ́ láti máa lò bí ohun ìjà láti dojúkọ Sàtánì.
- Bèerè lọ́wọ́ Ọlọ́run kí ó fi àmùrè rẹ̀ bò ọ́ ní ojoojúmọ́
- Ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ́ jẹ́ èso, bẹ́ẹ̀ni yó so ní àsìkò rẹ̀
- Jẹ́wọ́ ìṣẹ́gun bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ó dàbí wípé ìjákulẹ̀ wá.
- Gbára lé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí kìí yẹ̀ yàtọ̀ fún ìgbẹ́kẹ̀lé ènìyàn
- Ìlérí ní kí o gbà ní àdúrà, kìí ṣe ìṣòro
- Ya ẹnu rẹ láti gbàdúrà kí ọkàn rẹ leè papò
- Jẹ́wọ́ ìpèsè ní ojú gbèsè
- Riǹ ní ojúgbaara ìfẹ́ rẹ , kìí ṣe nínú ìfẹ́ tíí ṣe èyí tí ò wú ọ́
- Jẹ́ kí ó ye ọ wípé Ẹ̀mí tí ó fi fún wa kìí ṣe tí ayé yìí ṣùgbọ́n tí Ọlọ́run ní ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ rẹ̀ẹ wá.
- Gbogbo ìgbà ni kí o ma fi ọkàn gbà adúrà

- Dáríjin àwọn elòmíràn máa sénú. Èyí gan ní máa yí ìgbà èniyàn padà.
- Máa bọ̀wọ̀ fún Ọlọ́run ní ìgbà gbogbo pẹ̀lú ohun ìní rẹ, pẹ̀lú orin, ijó àti ìyìn
- Gbógbó wá ní a ní ọ̀tá, bẹ́ẹ̀ni wọ́n a sì máa fa ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà.
- Wá ìfẹ́ rẹ fún ayé nípasẹ̀ àdúrà àti ìgbọràn
- Àìgbọràn a máa dènà àdúrà. Àìgbọràn sí àwọn aláṣẹ, àti àwọn òbi gẹ́gẹ́ bí àpẹrẹ
- Tí iyèméjì bá wá, bèèrè lọ́wọ́ Ọlọ́run ná kí ó tó bèère lọ́wọ́ èniyàn
- Wá ojú rẹ ní àsìkò má ṣe sọ́ dí ọ̀la
- Fí Ọlọ́run ṣáajú kí ó sì wá ìfarahàn rẹ
- Retí ìdáhùn lẹ́yìn àdúrà
- Máṣe gbàdúrà ní kankan àyàfi tí ó bá di dandan
- Ní ìbáṣepò pẹ̀lú Ọlọ́run
- Máa ní àsìkò àdúrà. Wá àsìkò tí ó dára
- Fí ìrètí àti àlá rẹ śi ọwọ́ Ọlọ́run
- Wo Jésù kí ó bá gbogbo àìní rẹ pàdé
- Fí ìgbẹ́kẹ̀lé rẹ le Ọlọ́run nìkan lọ́wọ́, má fi sí ọwọ́ èniyàn tàbí ohunkóhun
- Tẹjú rẹ mọ́ Jésù, kí o si tẹ́tí sí ohun rẹ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ ní ọkàn rẹ
- Bèerè lọ́wọ́ Ọlọ́run kí o tó gbé ìgbésẹ̀ tó nípọn
- Jẹ́ kí ayé Ọlọ́run jẹ́ agbára rẹ
- Ní sùúrù, Ọlọ́run kíí pẹ́ kó tó de

- Ńífẹ́ ará rẹ bí ara rẹ, sì gbàdúrà fún wọn
- Fi fún àwọn tí kòní
- Wá ibi tí wàá tí máa bá Ọlọ́run pàdé ní gbònkẹ́lẹ́
- Gbàdúrà pẹ̀lú àwọn ara rẹ kí o sì ṣìpẹ̀ fún wọn
- Rán Olúwa létí ọ̀rọ̀ rẹ
- Gbé ìgbésì ayé rẹ lórí ọ̀rọ̀ rẹ́, gbé ọ̀rọ̀ rẹ lórí àyà rẹ
- Gbàdúrà ní aìsìnmi àti aìṣàárẹ̀
- Má jẹ̀ kí ohunkóhun dènà rẹ làti ṣiṣẹ́ fún Ọlọ́run
- Kíyèsára kí o sì má ṣe aláìmòye ète sàtánì bí ó ṣe ń wà ẹni tí yòò pa jẹ.
- Máṣe gbàdúrà èpè padà sórí elépè ṣùgbọ́n bèèrè fún àánú àti ìtúsílẹ̀ fún àwon tí sàtánì ńlò Ọlọ́run kò fẹ́ ikú ẹlẹ́ṣẹ̀ bíkòṣe kó ronú pìwàdà
- Fún ara rẹ̀ ní oúnjẹ alẹ́ Olúwa ní déédé
- Ní gbogbo ìgbà, máa fi ẹ̀jẹ̀ Jésù ṣe aàbò, ìwọ, ẹbí àti ara rẹ
- Fi ìgbàgbọ́ ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ. Ìlérí rẹ̀ yóò ṣẹ.
- Má ṣiyè méjì nípa agbára Ọlọ́run, oníyèméjì kíí rí Ìbùkún gbà
- Ka àwọn Ìbùkún Ọlọ́run ní ayé rẹ, ẹni tí ó ṣe gbogbo èyí yóò ṣe òmíràn.
- Ìlérí ní kí o gbà ní àdúrà kíí ṣé ìṣòro
- Kọrin ìyìn sí Olúwa, fi gbogbo àníyàn àti wàhálà rẹ lée lọ́wọ́
- Jẹ́ kí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run dí àkóso èrò rẹ mú, bẹ́ẹ̀ni máa fi àwọn èrò tó lòdì bú
- Má gbàgbé wípé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tó wà nínú rẹ tóbi jú wàhálà tó n kojú rẹ lọ

- Má gbéraga
- Jẹ́ kí èrò wípé Ọlọ́run wà láti tú ẹ́ nínú jẹ́ ohùn ayọ̀ àti ìtùnú fún ọkàn rẹ
- Jẹ́wọ́ ìpèsè ní ojú àìní
- Máṣe jẹ́kí gbòngbò ìkorò jọba ní ayé rẹ. Ma dunnú ní ìgbà gbogbo.
- Kígbe pé Olúwa nínú ìṣòro, ó wà láti gbà ọ́
- Fifún àwọn tí wọ́n ṣe àìní, bí o tilẹ̀ wù kí ó lé fún ọ tó, tí àwọn míiràn burú jù tirẹ̀ lọ.
- Máṣe fi oró yan oró, fi rere san búburú
- Jẹ́ kí ìbáṣepọ̀ tí o dánmọ́rán wà láàrin ìwọ àti Ọlọ́run, oun ni okun rẹ̀ ní gbogbo làáṡìgbò ayé
- Máṣe fi ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn Ọlọ́run ṣe awẹ́wa, wọ́n á ran ìdàgbásòke nínú èmí rẹ lọ́wọ́
- Máṣe gbàgbe wípé àti fún wa ní Ẹ̀mí Mímọ́ láti wà pẹ̀lu wà láti jọ lá ayé já papọ

# ORÍ KẸ́TA

## DÍDÚRÓ L'ÁÌYẸSẸ̀ LÓRÍ Ọ̀RỌ̀ ỌLỌ́RUN



## Ṣe Àṣàrò

- **Krónikà Kíní 16:11**

OLÚWA ni kí ẹ máa tọ̀ lọ fún ìrànlọ́wọ́, Ẹ máa sìn ín nígbà gbogbo.

- **Jeremáyà 29:12-13**

Ẹ óo ké pè mí, ẹ óo gbadura sí mi, n óo sì gbọ́ adura yín. Ẹ óo wá mi, ẹ óo sì rí mi, bí ẹ bá fi tọkàntọkàn wá mi.

- **Orin Dáfídì 102:17**

Yóo gbọ́ adura àwọn aláìní, kò sì ní kẹ́gàn ẹ̀bẹ̀ wọn.

- **Orin Dáfídì 145:18-19**

OLÚWA súnmọ́ gbogbo àwọn tí ń pè é, àní, àwọn tí ń pè é tọkàntọkàn. Ó ń tẹ́ ìfẹ́ àwọn tí ó bẹ̀rù rẹ̀ lọ́rùn; ó ń gbọ́ igbe wọn, ó sì ń gbà wọ́n.

- **Orin Dáfídì 18:30**

Ní ti Ọlọ́run, ọ̀nà rẹ̀ pé, pípé ni ọ̀rọ̀ OLÚWA; òun sì ni ààbò fún gbogbo àwọn tí ó sá di í.

- **Orin Dáfídì 55:11**

Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ tó ń jáde lẹ́nu mi yóo rí, kò ní pada sí ọ̀dọ̀ mi lọ́wọ́ òfo, ṣugbọn yóo ṣe ohun tí mo fẹ́ kí ó ṣe, yóo sì ṣe é ní àṣeyọrí.

- **Iwe Owe 30:5**

Kò sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kankan tí ó ń yẹ̀, òun ni ààbò fún àwọn tí wọ́n wá ààbò lọ sọ́dọ̀ rẹ̀.

- **Ìwe Òwe 3:5**

Fi tọkàntọkàn gbẹ́kẹ̀lé OLÚWA, má sì tẹ̀lé ìmọ̀ ara rẹ.

- **Nahumu 1:7**

OLÚWA ṣeun, òun ni ibi ààbò ní ọjọ́ ìdààmú; ó sì mọ àwọn tí wọn ń sálọ sọ́dọ̀ rẹ̀ fún ààbò.

- **Luku 11:13**

Nítorí náà bí ẹ̀yin tí ẹ burú báyìí bá mọ̀ bí a tií fún àwọn ọmọ yín ní ohun tí ó dára, mélòó-mélòó ni Baba yín ọ̀run yóo fi Ẹ̀mí Mímọ́ fún àwọn tí ó bá bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀!”

- **Awọn ará Filippi 4:6-7**

Ẹ má ṣe jẹ́ kí ohunkohun dààmú yín, ṣugbọn ninu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ yín, ẹ máa fi àwọn ìbéèrè yín siwaju Ọlọ́run pẹlu ọpẹ́. Alaafia Ọlọ́run, tí ó tayọ òye eniyan yóo pa ọkàn ati èrò yín mọ́ ninu Kristi Jesu.

- **Luku 18:27**

Ó dáhùn pé, “Ohun tí kò ṣeéṣe fún eniyan, ó ṣeéṣe fún Ọlọ́run.”

- **Jakobu 4:8**

  Ẹ súnmọ́ Ọlọ́run, òun óo sì súnmọ́ yín. Ẹ wẹ ọwọ́ yín mọ́, ẹ̀yin ẹlẹ́ṣẹ̀, ẹ jẹ́ kí ọkàn yín dá ṣáká, ẹ̀yin oníyèméjì.

- **Iwe Owe 18:10**

  Orúkọ OLÚWA jẹ́ ilé-ìṣọ́ tí ó lágbára, olódodo sá wọ inú rẹ̀, ó sì yè.

## Ọ̀rọ̀ Àperò

- Mo dúró lórí ìlérí ọ̀rọ̀ rẹ tó sọ wípé tí mo bá bèèrè ohunkóhun gẹ́gẹ́ bí ìlérí ọ̀rọ̀ rẹ wàà gbọ́ mi. Tí mo bá mọ̀ wípé ó gbọ́ ohunkóhun tí mo bá bèèrè, mo mọ̀ wípé gbogbo ohun tí mo bá bèèrè ní màá rí gbà

- Mo wá láti fí ẹ̀jẹ̀ Jésù tí a ta sílẹ̀ lórí òkè Kálfárì fún mí ṣe ààbo, ẹ̀jẹ̀ nípa èyí tí mo ní májẹ̀mú pẹ̀lú Ọlọ́run. Mo wá jẹ́wọ́ májẹ̀mú nà.

- Mo dúró lórí ọ̀rọ̀ rẹ tó sọ wípé tí mo bá bèèrè ohunkóhun lọ́wọ́ rẹ wàa´ṣe wọ́n

- Mo dúró lórí ìlérí rẹ tó sọ wípé ohunkúhun tí mo bá dè ní ayé, wàá dè ní ọ̀run, àti wípé ohunkóhun tí mo bá tú ní ayé, wàá tú wọn ní ọ̀run.

- Olúwa, rànmílọ́wọ́ kí n lè dúró nínú rẹ, àti iwọ nínú mi. Mo gbàdúrà kí nle so èso lọ́pọ̀lọpọ̀, nítorí ní áìsí rẹ, nkò lèṣe ohunkóhun.

- Mo wá pẹ̀lú ìgbàgbó wípé agbára rẹ kà ohun gbogbo, ṣebí ìwọ ní Ọlọ́run tó mọ ohun gbogbo, rí ohun gbogbo, tó sìlè ṣe ohun gbogbo.

- Olúwa, mo fi ìgboyà wá sí àgbàlá rẹ, pẹ̀lú ìgbáralé ìfẹ́ rẹ tí kò ní kẹ́yìn sí àdúrà mi. O ṣeun tí o jẹ́ lọ́wọ́lọ́wọ́ ìrànwọ́ fuń mi. Mo ní ìgbàgbó nínú rẹ àti agbára àikùnà rẹ láti gbàmí lọ́wọ́ àwọn ẹni búburú àti àwọn aláìlérò ènìyàn

- Mo dìídì pinu láti máṣe àníyàn lórí ohunkóhun, nítorí ìwọ ni o má n sọ mí láti ba gbogbo àiní mí pàdé. Ìdí

nìyí tí mo ṣe wà ní ìfọ̀kànbalẹ̀ torí mo gba wípé wàá mú ìlérí rẹ ṣe

- Bàbá mo mọ̀ wípé ètò rẹ fún ayé mi pè, ó sì dára. Mo rán àra mi létí àwọn ìlérí rẹ, mo sì dúpẹ́ pé o má n pa májẹ̀mú rẹ mọ́ fún àwọn tí wọ́n bẹ̀rù rẹ

**Ọ̀rọ̀ Àperò**

Tí o bá wà pẹ̀lú Ọlọ́run, o kò dáwà.

**Rose of Sharon Glorious Ministry Int'l**

Gbadùn

**Àsìkò Ọ̀tun Pẹ̀lú Ẹ̀mí Mímọ́**



**Ní ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kẹ̀jì Olóòṣọ̀ṣù

# ORÍ KẸ́RIN

## KÓRÓ ỌGBỌ́N



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 37:30**
Ọ̀rọ̀ ọgbọ́n níí máa jáde lẹ́nu ẹni rere, a sì máa sọ ọ̀rọ̀ ẹ̀tọ́.

**Iwe Owe 3:13**
Ayọ̀ ń bẹ fún ẹni tí ó wá ọgbọ́n rí, ati ẹni tí ó ní òye.

**Jakobu 1:5**
Bí ẹnikẹ́ni bá wà ninu yín, tí ọgbọ́n kù díẹ̀ kí ó tó fún, kí olúwarẹ̀ bèèrè lọ́dọ̀ Ọlọrun, yóo sì fún un. Nítorí Ọlọrun lawọ́, kì í sìí sìrègún.

- Ìgbàgbọ́ ní ìgbésẹ̀ tó wà láàrín ìlérí àti ìmúṣẹ
- Ìyanu má'n jìnà sí ẹni tí ìgbàgbọ̀ rẹ kòtò, ṣùgbọ́n gbogbo ìyanu, ńlá tàbí kékeré, bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú iṣẹ́ ìgbọràn. A lè má ri ọ̀nà àbáyọ títí tí a o fi gbé ìgbésẹ̀ ìgbàgbọ́ àkọ́kọ́.
- A kò fún wa ní ìpèsè Ọlọ́run kí a ba lè simi le, a nílò láti gbára lé Olúwa bí a ṣé ń ní àdojúko tuntun.
- Ìgbàlà wá láti ọwọ́ Ọlọ́run nìkan. Kòsí ìwọ̀n iṣẹ́ rere tí o lè ṣe tí ó le fi rá.
- Padà, ronúpìwàdà, kí o sì di ọ̀tun. Ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ìràpadà nípasẹ̀ Krísti, kí o sì máa yọ̀.
- Ọlọ́run fẹ́ lò ẹ́ láàrín àwọn ènìyàn tí o wà ní ojojúmọ́. Tí o báṣe èyí, yí o sọ̀ agbègbè rẹ di ńlá. Èso ìfẹ́ tí o bá so sí ayé ẹlòmíràn a máa sẹ̀dá irú ìkórè tí o máa ní. Ella Wheeler Wilkox sọ wípé, "Fífún ènìyàn ní oun tí ónì tí o dára jùlọ, oun tí o dára jùlo a si padà tọ̀ ọ́ wá". Ọlọ́run dá ọ ní Olùbùkún, kììṣe ẹni tí ó n gba ìbùkún nìkan. Nítorínà, jẹ́kí ìpinu Ọlọ́run wásí ìmúṣẹ nínu ayé rẹ́, ó sí rì gbogbo oun tí Ọlọ́run fẹ́ kí o rí gbá.
- Máṣe kópa nínú iṣẹ́ Ọlọ́run tó bẹ̀ ti wàá fi gbàgbé Ọlọ́run tí o ní iṣẹ́ na.
- Ayé tí lè já ọ kulẹ̀, ṣùgbọ́n Ọlọ́run kònì já ọ kulẹ̀
- Ojútù dìde ní ìrọ̀rùn nínú àlàfià ti ọkàn, nígbàtí ìbẹ̀rú àti àifọkànbalẹ̀ jẹ́ ìdíwọ́ fún ojútù.
- Ìgbé ayé lọ́kọláya jẹ́ oun tí a ṣẹ̀dá lẹ́yìn ọjọ́ ìgbéyàwó, kò ní dédé ṣẹlẹ̀. Ó ní láti kọ́ pẹ̀lú ìtẹ́ríba, àtìlẹ́yìn, sùúrù, àti ìfẹ́ tí ó ní ìṣàmísi nípa fifún, kììṣe gbígbà.

- Ìṣẹ́gun jẹ́ tí àwọn tí ó má wo ibi afẹ́dé tí kíí ṣe lílọ, kíí ṣe ìlànà ṣùgbọ́n ẹ̀bùn náà, kíí ṣe ìdánwò ṣùgbọ́n ìṣúra tí o tí ṣe ìlérí fún àwọn tí ó faradà

- Ọlọ́run kò pe ẹni tí ó k'ójú òṣùnwọ̀n, nṣe ni o ma n mú ẹnikẹ́ni tí ó bá pe k'ójú òṣùwọ̀n ní.

- Pétérù Wesley sọ wípé "a leṣe àwọn ohun ńla ńígbà tí a bá n gbàdúrà ṣùgbọ́n a kò le ṣè nkankan títí tí a ó fi gbàdúrà".

- Ṣe gbogbo rere tí o lèṣe, ní gbogbo ipá tí ó lè lọ, ní gbogbo ọ̀nà tí ó lè lọ, ní gbogbo ibi tí ó ti lèṣe, sí gbogbo ẹni tí o lèṣe fún, bí ó bá ti lè pẹ́ tó.

- Ìgbàgbọ́ kòṣe ìmùkúrò àwọn ìbéèrè, ṣùgbọ́n ìgbàgbọ́ mọ ibi tí ó le mú wọn lọ.

- Ti o ba n ṣiṣẹ́ ti o ko raye lati gbadura, o ti ṣiṣẹ́ ju bi Ọlọ́run ti fẹ́ ko ṣe nìyẹn.

- Ṣugbọn OLÚWA Ọlọ́run Olúwa ẹ̀jẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀ gẹ́gẹ́ ẹlòmíràn ẹ̀ Jẹ́nẹ́sìsì

- Akùnà nínú iṣẹ́ oore àti ìfẹ́ nígbàtí a bá wa nínú ara, tí díẹ̀ Ọlọ́run sí wa nínú wa.

- Rántí bí o tín lọ níti ọjọ́ rẹ̀ pé ó le jẹ́ ìwọ nìkan ní Jésù tí àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, aládúgbò rẹ́ àti ẹbí rẹ yóò rí.

- Ọlọ́run gbọ́ gbogbo èrò ọkàn rẹ̀ yálà o ṣé lọ́ṣọ̀ pẹ̀lú "ìrẹ" tàbí "ìwọ" àbí o kò ṣé lọ́ṣọ̀ rárá.

- Ìgbéyàwó dàbí ọgbà, o ma n gbà àkókò láti dàgbà. Sùgbọ́n ìkórè rẹ́ pọ̀ fún àwọn tí ó fi sùúrù àtí ìfọ̀kọ̀nbalẹ̀ ṣe ìtọ́jú rẹ̀.

- Bí Bíbélì rẹ bá ṣe dọ́ti sí ní ọkàn rẹ ṣe mọ́ sí.

- Nígbàmíràn ó gbọdọ̀ dúró kí ó balè tẹ̀síwájú sí ibi tí Ọlọ́run fẹ́ kí ó lọ.

- Òmìnira fún wa ní agbára láti fò, ṣùgbọ́n aáwọ̀ a má bá agbára náà jẹ́.

- Àwọn tó ti ṣẹ́gun kò pe. Wọ́n kùnà gẹ́gẹ́ bí àwọn ìyókù wà ṣùgbọ́n wọ́n dìde, wọn ronúpìwàdà, wọ́n sì ṣetán láti fi ara wọ́n fún Krístì, wọ́n fi àyè gbà ẹni tí ó jẹ́ ẹni pípé láti ṣiṣẹ́ nípasẹ̀ wọ́n.

- Ẹni tí o máá jẹ lọ́la bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ohun tí o baṣe lónì.

- Ọlọ́run bùkún fún ẹ kí o ba lè ló láti jẹ́ ìbùkún fún elòmíràn.

- Ìgbéyàwó tí ó dára jù lọ ní a kọ lórí ìfọwọ́sowọ́pọ̀, ìbọ̀wọ̀ fúnní, ìwúnilórí tí ó péye, àti ìfẹ́ àti ore ọ̀fẹ́ aláìlópin.

- Àṣeyọrí kìí ṣe ìparí, ìkùnà kìí ṣe àfàkù, ìgboyà láti tẹ̀ ṣíwájú ni ó ṣe kókó jùlọ.

- Tí o báfẹ́ ṣe nkàn, o má wá ọ̀nà láti ṣé. Tí o kò bá fẹ́ ṣe, o máá wá àwáwí.

- Àwọn ìdíwọ́ tí ó wá nìkan ni àwọn èyí tí ó tí gbé sínú ọkàn rẹ. Ìdíwọ́ tí ó ni wà níbẹ̀ nitorí ó ti gbàgbé àwọn ohun tí ó tí ṣe láṣeyọrí tẹ́lẹ̀.

- Àdúrà kìí ṣe bìbèerè, òùngbẹ ọkàn ní. Ó jẹ́ gbígbà nípa àilera wa nínú àdúrà, ó dárá kí a fi ọkàn wa sí lálái sọ̀rọ̀ jù pé kí á sọ̀rọ̀ lái fi ọkàn wa sí.

- Jẹ ki ọkan rẹ kun fun ọrọ Ọlọ́run ti o sọ iye sinu ayé rẹ.

- Bíbélì ń sọ́ fuń wa, ó n ṣe àtúnṣe, ó sì ń yípadà. Àwọn ìwé míràn kan sọ fún wa lásán ni.

- Ìdáríji á máá mú wá súnmọ́ àwọn tí ó ti ṣẹ̀ wà rí, a sì rán wọ́n lọ́wọ́ láti ní ìrírí ìdáríji àti ìfẹ́ Jésù nípasẹ̀ wa tí o dáríjì wọ́n.

- Sọ wípé ó ti dára bí ó tilẹ̀ wà nínú ìṣòro. A ṣìle rí Ọlọ́run nínú òkùnkùn birimu, gbe ọkán rẹ lé Olúwa.

- Tí o bá fẹ́ ìgbeyàwo aládùn tí Krístì wà nínú rẹ̀, ogbọ́dọ̀ wà nínú Krístì fun ra rẹ.

- Kò sí ohun tí o tóbi jù fún Ọlọ́run, bẹ́ẹ̀ni kò sí òhun tí ó kéré débi wípé kòní kọ̀bí ara sí. Kò sí àdúrà tí o yẹpẹrẹ sí Ọlọ́run.

- Bí o tilẹ̀ jẹ́ wípé ọ̀pọ̀ nkàn ní kìí lọ bí aṣe lérò, síbẹ̀ gbogbo rẹ̀ máa´n yọrí sí rere fún àwọn tí wọ́n nífẹ̀ Olúwa. Èrò rẹ gá jú ti wa lọ.

- Kòsí ohun tí ìfẹ́ kò le gbàmọ́ra. Ìfẹ́ kìí sọ ìrètí nù, bẹ́ẹ̀ni kìí sọ ìgbàgbọ́ nu tàbí yípadà.

## Àwàdà

### OLÈ MẸ́TA

Àwọn olè mẹ́ta, Ayọ̀, Éméka àti Ézè ní wọ́n mú ba ilé ẹjọ́. Ẹ̀sùn Éméka ní wípé, ẹja mẹ́ta inú agolo ní ó jí, torínà, adájọ́ sọ́ sí ẹ̀wọ̀n odún mẹ́ta. Ẹ̀sùn Ézè ni wípé, ẹyin ọgbọ̀n ni ó jí, torínà, adájọ́ sọ sí ẹ̀wọ̀n ọgbọ̀n ọdún. Ayọ̀ bá dákú kí wọ́n tó sọ ìdájọ́ tirẹ̀, nítorípé àpò ìrẹsì kan ni ó jí.

`

# Rose of Sharon Glorious Ministry Int'l



Gbádun

## Àsìkò Ìgbéga

**tí ọ̀tun**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kejì Olóoṣòṣu

# ORÍ KARÙN

## ÌGBÉSÍ AYÉ ÌYÌN



## Ṣe Àṣàrò

**Ẹksodu 15:2**
OLÚWA ni agbára ati orin mi, ó ti gbà mí là, òun ni Ọlọ́run mi, n óo máa yìn ín. Òun ni Ọlọ́run àwọn baba ńlá mi; n óo máa gbé e ga.

**Aisaya 63:7**
N óo máa sọ nípa ìfẹ́ ńlá OLÚWA lemọ́lemọ́, n óo máa kọrin ìyìn rẹ̀; nítorí gbogbo ohun tí OLÚWA ti fún wa, ati oore ńlá tí ó ṣe fún ilé Israẹli, tí ó ṣe fún wọn nítorí àánú rẹ̀, ati gẹ́gẹ́ bí ọpọlọpọ ìfẹ́ rẹ̀ tí kìí yẹ̀.

**Orin Dafidi 103:1-5**
Yin OLÚWA, ìwọ ọkàn mi, fi tinútinú yin orúkọ rẹ̀ mímọ́. Yin OLÚWA, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo oore rẹ̀, ẹni tí ó ń dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì ó, tí ó ń wo gbogbo àrùn rẹ sàn; ẹni tí ó ń yọ ẹ̀mí rẹ kúrò ninu ọ̀fìn, tí ó fi ìfẹ́ rẹ̀ tí kì í yẹ̀ ati àánú dé ọ ládé. Ẹni tí ó ń fi ohun dáradára tẹ́ ọ lọ́rùn, tí ó fi ń sọ agbára ìgbà èwe rẹ dọ̀tun bíi ti idì.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Mo ń ìmí ńtorínà mo yín ọ́ Olúwa torí ó dá ọ̀run àti ayé, ó gba àwọn aláìlágbára, ó pèsè oúnjẹ fún ẹni ebi ńpa àti omìnìra fuń àwọn tí a dè mọ́lẹ̀
- Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ́ Olúwa torí o ti bùkún mí jú ìwọ́n lọ́. Mo yìn ọ́ fún ìbùkún ojoojúmọ́ tí ó ń fi kún mi.
- Mo yìn ọ́ Olúwa nítorí wípé o dá mi pẹ̀lú ẹ̀mí àṣeyọrí, iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ ìyanu ó sí nì ògo tí ó ju àwọn ọ̀run lọ.
- Èmi ò yin ọ́ Olúwa pẹ̀lú ẹnu mí. Pẹ̀lú ìgboyà ní máá fi òtítọ́ rẹ̀ hàn fún gbogbo ayé. Ó ti gbé orí mi sókè làrín ọ̀pọ̀ èǹìyàn, a sì tí gbé ọwọ́ mí sókè. Nítorínà, èmí yọ̀, ẹnu mi yìn ọ́ nígbà gbogbo

**Ọ̀rọ̀ Àpérò**

Fi t'Ọlọ́run ṣ'ájú,
kí ó sí pòngbẹ láti
wà níwájú rẹ̀

# ORÍ KẸFA

## YÍN ALÁÀFIN ÀGBA



## Ṣe Àṣàrò

**Aisaya 12:5**
Kọ orin ìyìn sí OLÚWA nítorí ó ṣe nnkan tí ó lógo, jẹ́ kí èyí di mímọ̀ ní gbogbo ayé.

**Orin Dafidi 150:1**
Ẹ yin OLÚWA! Ẹ yin Ọlọ́run ninu ibi mímọ́ rẹ̀; ẹ yìn ín ninu òfuurufú rẹ̀ tí ó lágbára.

**Orin Dafidi 96:9**
Ẹ sin OLÚWA ninu ẹwà ìwà mímọ́; gbogbo ayé, ẹ wárìrì níwájú rẹ̀.

**Orin Dafidi 95:1**
Wá, ẹ jẹ́ kí á kọrin sí OLÚWA; ẹ jẹ́ kí á hó ìhó ayọ̀ sí Olùdáàbòbò ati ìgbàlà wa!

**Juda 1:25**
Ọlọ́run nìkan ṣoṣo, Olùgbàlà wa nípasẹ̀ Jesu Kristi Olúwa wa ni ògo, ọlá, agbára ati àṣẹ wà fún, kí á tó dá ayé, ati nisinsinyii ati títí ayé ainipẹkun. Amin.

**Orin Dafidi 66:4**
Gbogbo ayé ní ń sìn ọ́; wọ́n ń kọ orin ìyìn fún ọ, wọ́n ń kọ orin ìyìn sí orúkọ rẹ."

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo yin Ọlọ́run alaàyè tí ìjọba rẹ̀ wà títí ayé, tí kòsì ní parun láiláí.
- Mo jẹ́wọ́ wípé èmi kò ṣe pàtàkì ní ibi tí ó wà, ìwọ ní ọba tí ó ngbàlà, tí ó sí n kò àwọn ènìyàn rẹ̀ yọ.
- Ìwọ ní ó n ṣe iṣẹ́ àmì àti ìyanu ní ọ̀run àti ayé.
- Ìwọ ni o gba Jóséfù là lọ́wọ́ ikú nípasẹ̀ àwọn ẹ̀gbọ́n rẹ̀ tí ó sì gbé dé ipò ìgbàkejì ọba láti inú túbú.

Ìwọ ni ó fún onímọ̀ nímọ̀, tí ó sì fún ọlọ́gbọ́n ní òye.

Ón fi ọba jẹ, ó sì n yọ ọba kúrò, ó yí ìgbà àti àkókò padà, ó sì fi ohun ìkọ̀kọ̀ hàn.

- Ìwọ ní ó mọ ohun tí ó wà nínú òkùnkùn, ìmọ́lẹ̀ sí wa ní inú rẹ̀.

**Ọ̀rọ̀ Àpérò**

Ìfẹ́ rẹ̀ fún Ọlọ́run yóo mú ọ gbé ayé rẹ fún Ọlọ́run.

# ORÍ KÉJE

## ÌWÁDÍ Ọ̀KÀN....
## WÍWÁ ÌDÁRÍJÌ



## Ṣe Àṣàrò

**Johanu Kinni 1:9**

Ṣùgbọ́n bí a bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa: olóòótọ́ ati olódodo ni òun, yóo wẹ àìṣedéédé gbogbo nù kúrò lára wa.

**Jakọbu 5:16**

Ẹ máa jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ yín fún ara yín, ẹ máa gbadura fún ara yín kí ẹ lè ní ìwòsàn. Adura àtọkànwá olódodo lágbára, nítorí Ọlọ́run a máa fi àṣẹ sí i.

**Luku 6:37**

"Ẹ má ṣe dá eniyan lẹ́jọ́, kí Ọlọ́run má baà dá ẹ̀yin náà lẹ́jọ́. Ẹ má ṣe dá eniyan lẹ́bi. Ẹ máa dáríjì eniyan, Ọlọ́run yóo sì dáríjì yín.

**Kolose 3:13**

Ẹ ní ìfaradà láàrin ara yín. Ẹ máa dáríjì ara yín bí ẹnikéni bá ní ẹ̀sùn kan sí ẹnìkejì rẹ̀; . gẹ́gẹ́ bí Olúwa ti dáríjì yín bẹ́ẹ̀ gan-an ni kí ẹ̀yin náà máa ṣe sí ara yín.

**Aisaya 55:7**

Kí eniyan burúkú fi ọ̀nà ibi rẹ̀ sílẹ̀, kí alaiṣododo kọ èrò burúkú rẹ̀ sílẹ̀, kí ó yipada sí OLÚWA, kí OLÚWA lè ṣàánú rẹ̀. Kí ó yipada sọ̀dọ̀ Ọlọ́run wa, nítorí Ọlọ́run yóo dáríjì í lọ́pọ̀lọpọ̀.

**Orin Dafidi 86:5**

Nítorí pé olóore ni ọ́, OLÚWA, o máa ń dárí jini; ìfẹ́ rẹ tí kì í yẹ̀ sì pọ̀ sí gbogbo àwọn tí ń ké pè ọ́.

**Aisaya 45:25**

Èmi, èmi ni mo pa ẹ̀ṣ ẹ̀ yín rẹ́, nítorí ti ara mi; n kò sì ní ranti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yín mọ́.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo ní òmìnira kúrò lọ́wọ́ àìdáríjì àti ìjà.
- Mo ti ní ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀, ẹ̀jẹ̀ ọ̀dọ́ àgùntàn sí tí ràmí padà gẹ́gẹ́ bí kíkún ore ọ̀fẹ́ rẹ̀
- Gẹ́gẹ́ bí Krístì tí dáríjì mí, mo dáríjì

àwọn míràn, nítorí ìfẹ́ Olúwa ta nínú ọkàn mi nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́.

- Mo dáríjì gbogbo àwọn tí ó tí ṣẹ̀ mí ní ọ̀nà kan tàbí òmíràn, mo sì bèèrè fún Ẹ̀mí Mímọ́ Ọlọ́run kì o ranmílọ́wọ́ nínú èyí tí ó ṣórò fún mi láti ṣe.

- Fún mi ní ọkàn tútù, Olúwa.

## Àkíyèsi

Ìdáríjì wà fún ìdàgbàsókè àti ìdùnú wà. Àidáríjì a máa ṣe wá ní ibi jú ẹni tí o ṣẹ̀ wá lọ.

Ìdáríjì a máa fún wa ní òmìnira láti fi ojú fo ọ̀rọ̀ àná, a sì máa ràn wá lọ́wọ́ láti tẹ̀síwájú láì ní ìbínú àbí ẹ̀mí ẹ̀san gbígbà.

Ìfẹ́ tí ó ga jù lọ wà nínú agbára láti dáríjì àwọn tí ó ṣẹ̀ wá.  A'o wàa ní àlááfia àti ifọ̀kànbalẹ̀ tí a bá ní ẹ̀mí ìdáríjì.

Ìdáríjì kìí ṣe ohun tí a ṣe fún elòmíràn, aṣé fún ara wa ni. Àìní ìdàríjì jásí pé a gbé ara wa sínú ìgbèkùn ọgbẹ́ ọkàn, a sì wà ní ẹ̀wọ̀n fún ẹ̀ṣẹ̀ tí ẹlòmíràn ṣẹ.

Tí ẹnikẹ́ni bá ṣẹ̀ ọ́, pé ẹni bẹ̀ kí ó si fi sùúrù sọ́ bí ohun tí ẹni náà ṣe tí ṣẹ̀ dún ọ. Èyí a fún ẹ ní òmìnira kúrò nínú ìgbèkùn, yíò sì ràn ẹ́ lọ́wọ́ láti mú ọkàn kúrò nínú àríyànjiyàn.

## Àwàdà

### Ìdáríji

Olùkọ́ ilé ìwé ọjọ́ ìsinmi kan ṣèṣẹ̀ parí ìdánilẹ́kọ̀ rẹ̀, ó sì fẹ́ mò bóyá ohun tí ò ń kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ yé wọn, ó bèère wípé "ṣe ẹnikẹ́ni ní le sọ fún mi ohun tí a gbọ́dọ̀ ṣe kí a tó le rí ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ gbà"? Ìdákẹ́rọ́rọ́ wà fún ìgbà díẹ̀ kí ọmọkùnrin kan tó sọ̀rọ̀ láti ẹ̀yìn kílásì, ó ní wípe "a gbọ́dọ̀ dẹ́ṣẹ̀".

# Rose of Sharon Glorious Ministry Int'l

Gbádùn

# Àsìkò Ìjọ́sìn ọ̀tun



**Ni ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kẹ̀ji Olóoṣọ̀ṣu

# ORÍ KẸJỌ

## ÌWÁDÍ ỌKÀN...
## WÍWÁ ÀÁNÚ



## Ṣe Àṣàrò

**Ekisodu 34:6-7**
OLÚWA kọjá níwájú rẹ̀, ó sì kéde orúkọ ara rẹ̀ báyìí pé, "OLÚWA Ọlọ́run aláàánú ati olóòre, ẹni tí ó lọ́ra láti bínú, tí ó sì pọ̀ ní àánú ati òtítọ́. Ẹni tí ó máa ń ṣàánú fún ẹgbẹẹgbẹrun, tí ó máa ń dárí àìṣedéédé ji eniyan, ó máa ń dárí ẹ̀ṣẹ̀, ati ìrékọjá jì, ṣùgbọ́n kì í jẹ́ kí ẹlẹ́ṣẹ̀ lọ láìjìyà, a sì máa fi ìyà ẹ̀ṣẹ̀ baba jẹ ọmọ ati ọmọ ọmọ títí dé ìran kẹta ati ikẹrin."

**Mika 7:18-19**
Ta ló dàbí rẹ, Ọlọ́run, tí ó ń dárí ẹ̀ṣẹ̀ ji eniyan, tí ó sì ń fojú fo ẹ̀ṣẹ̀ àwọn eniyan ìní rẹ̀ yòókù, ibinu rẹ kì í wà títí lae, nítorí pé a máa dùn mọ́ ọ láti fi ìfẹ́ rẹ̀ tí kì í yẹ̀ hàn. O óo tún ṣàánú wa, o óo sì fẹsẹ̀ tẹ ẹ̀ṣẹ̀ wa ní àtẹ̀parẹ́. O óo sọ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa sí ìsàlẹ̀ òkun

**Efesu 2:4-5**
Sùgbọ́n nítorí ìfẹ́ ńlá tí Ọlọ́run tí ó ní àánú pupọ ní sí wa, ó sọ wá di alààyè pẹlu Kristi nígbà tí a ti di òkú ninu ìwàkíwà wa. Oore-ọ̀fẹ́ ni a fi gbà yín là.

**Iwe Òwe 3:3-4**
Má jẹ́ kí ìwà ìṣòótọ́ kí ó fi ọ́ sílẹ̀, so àánú ati òtítọ́ mọ́ ọrùn rẹ, kọ wọ́n sí oókan àyà rẹ. Nípa bẹ́ẹ̀, o óo rí ojurere ati iyì lọ́dọ̀ Ọlọ́run ati ènìyàn.

**Aisaya 64:8-9**
Sibẹsibẹ OLÚWA, ìwọ ni baba wa, amọ̀ ni wá, ìwọ sì ni amọ̀kòkò; iṣẹ́ ọwọ́ rẹ ni gbogbo wa. OLÚWA má bínú pupọ jù, má máa ranti ẹ̀ṣẹ̀ wa títí lae. Jọ̀wọ́, ro ọ̀rọ̀ wa wò, nítorí pé ènìyàn rẹ ni gbogbo wa.

**Aisaya 55:7**
Kí eniyan burúkú fi ọ̀nà ibi rẹ̀ sílẹ̀, kí alaiṣododo kọ èrò burúkú rẹ̀ sílẹ̀, kí ó yipada sí OLÚWA, kí OLÚWA lè ṣàánú rẹ̀. Kí ó yipada sọ́dọ̀ Ọlọ́run wa, nítorí Ọlọ́run yóo dáríjì í lọpọlọpọ

# Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Olúwa, wẹ̀ mí mọ́, gbé ojú rẹ kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ mí, kí ó má ṣìṣe gbà Ẹ̀mí Mímọ́ rẹ̀ kúrò lọ́wọ́ mí. Dá ayọ̀ ìgbàlà rẹ padà fún mi kí o sì di mí mú nípa ẹ̀mí rẹ Olúwa.

- Ìwọ ni o dárí gbogbo àiṣedéedé mí jì mí, tí ó jẹ́ àláanu àti oloore ọ̀fẹ́, ó lọ́ra láti bínú, àànú rẹ pọ̀ gídígídí. O kò ní bá mi jà títí, bẹ́ẹ̀ni o kòní bínú símí títí ayé. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ Olúwa nítorí o kò ní bámi wí tàbí bámi lò gẹ́gẹ́bí ẹ̀ṣẹ̀ mi. Mo dúpẹ́ Olúwa nítorí o rántí pé erùpẹ̀ lásán ni mí, èyí sì mú kí àànú rẹ kí ó pọ̀si fún mí.

- Nítorí tí ó dìde tí ó sì ṣàánú fún mi, bímo ṣe fi ìgboyà wá síwájú ìtẹ́ àánú rẹ, tí mo sì rí ore ọ̀fẹ́ nígbàtí mo nílò rẹ̀. Ní orúkọ Jésù Olúwa. Àmín.

- Olúwa Ọlọ́run mí, ṣí ojù mí kí èmi másì sùn orun ikú, Mo ti gbọ́kànlé àánú rẹ́, nítòrínà, ọkàn mí yóò yọ̀ nínú ìgbàlà rẹ́ nítorí ó ti ṣe lọ́pọ̀ pẹ̀lú mí àti àwọn ènìyàn mí.

- Olúwa, wẹ̀mí mọ́ pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀ Jésù kí ó másì ṣe rò ẹ̀ṣẹ̀ mí, mú wọn jìnà réré sí mi.

- Dá ọkàn titun sínú mi Olúwa kí o sì fún mi ní ẹ̀mí rẹ́ ní ọ̀tun

- Ṣàánú fún mi Olúwa gẹ́gẹ́ bí ìṣehun ìfẹ́ rẹ́, máṣe jẹ́ kí ń pàdánù àmì àánú àti ore ọ̀fẹ́ rẹ́ lórí mi. Nítorí fún ìgbà díẹ́ ní ìbínú rẹ, ṣùgbọ́n ìfẹ́ rẹ́ àti àánú rẹ wà fún àwọn tí o n wá ọ. Nítorínà, níkùtù ní èmi yóò wá ọ, tị ún ó sì fi ọkàn mí fún ọ, mosì mọ̀ pe o kò ní tamínù bí ó tiwù kí ó rí

- Bàba mi ọ̀run, a dúpẹ́ wípé nípa Ẹ̀mí Mímọ́ rẹ, ó ti fi onírurú ẹ̀bùn ẹ̀mí rẹ fún àwọn ọmọ rẹ́.

- Rànmílọ́wọ́ láti fi ìfẹ́ àti ojúrere rẹ́ hàn sí ayé. Fúnmi ní ore-ọ̀fẹ́ láti jẹ́ apá àti ẹsẹ̀ rẹ nínú gbígba ènìyàn níyànjú, àánú àti ìfẹ́ sí arákùnrin àti arábìrin mi nínú Krístì. Àmín.

## Àwàdà

Ọmọkùnrin tí ọjọ́ orí rẹ̀ kò ju ọdún mẹ́rin kan ní wọ́n sọfún pé kí ó gbàdúrà sí oúnjẹ tí wọ́n fẹ́ jẹ. Àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ̀ bá tẹríba ní ìrètí àdúrà, ọmọ náà bẹ̀rẹ̀ àdúrà rẹ̀, ó dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, ó sì ń dárúkọ wọn níkọ̀ọ̀kan.

Ó tẹ̀síwájú láti dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ìyá, bàbá, àwọn ẹ̀gbọ́n àti àbúrò rẹ̀, fún bàbá àti ìyá tí ó bí òbí rẹ̀, àti gbogbo ẹ̀gbọ́n àti àbúrò tí a bí mọ́ àwọ́n òbí rẹ̀. Ó wá bẹ̀rẹ̀ síní dúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún oúnjẹ náà. Ó dúpẹ́ fún tòlótòló tí wọ́n pa, sísè tí wọ́n sè, àtí fún gbogbo èso tí ó wà lórí tábílì nằ. Ó wá dákẹ́, gbogbo ènìyàn sì dúró kí ó mú àdúrà rẹ̀ wá sí ìparí. Lẹ́yìn tì o ti dákẹ́ fún ìgbà díẹ̀, ọmọkùnrin náà wo ìyá rẹ, ó sì bẹ̀ẹ̀rẹ sí wípé,

"tí òun bá dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún brokólì, ṣé kòní mọ̀ wípé òun ń parọ́ ni?

# ROSE OF SHARON GLORIOUS MINISTRY INT'L

Gbádùn

## Àsìkò Ìjọ́sìn ọ̀tun




**Ni ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kẹ̀ji Olóoṣọ̀ṣu

# ORÍ KẸSÀN

## ÌTỌNI ÀTÒKÉWA



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 24:4-5**
Ẹni tí ọwọ́ rè mọ́, tí inú rẹ̀ sì funfun, tí kò gbẹ́kẹ̀lé oriṣa lásánlàsàn, tí kò sì búra èké. Òun ni yóo rí ibukun gbà lọ́dọ̀ OLÚWA, tí yóo sì rí ìdáláre gbà lọ́wọ́ Ọlọ́run, Olùgbàlà rẹ̀.

**Iwe Owe 3:5-6**
Fi tọkàntọkàn gbẹ́kẹ̀lé OLÚWA, má sì tẹ̀lé ìmọ̀ ara rẹ. Mọ Ọlọ́run ní gbogbo ọ̀nà rẹ, yóo sì mú kí ọ̀nà rẹ tó.

**Aisaya 30:21**
Bí ẹ bá fẹ́ yapa sí apá ọ̀tún tabi apá òsì, ẹ óo máa gbọ́ ohùn kan lẹ́yìn yín tí yóo máa wí pé, "Ọ̀nà nìyí, ibí ni kí ẹ gbà."

**Orin Dafidi 25:9**
A máa tọ àwọn onírẹ̀lẹ̀ láti ṣe ohun tí ó tọ́, a sì máa kọ́ wọn ní ìlànà rẹ̀.

**Orin Dafidi 32:8**
N óo kọ́ ọ, n óo sì tọ́ ọ sí ọ̀nà tí o óo rìn; n óo máa gbà ọ́ ní ìmọ̀ràn; n óo sì máa mójútó ọ.

**Aisaya 48:17**
OLÚWA, Olùràpadà rẹ, Ẹni Mímọ́ Israẹli, ní, "Èmi ni OLÚWA Ọlọ́run rẹ, tí ń kọ́ ọ ní ohun tí yóo ṣe ọ́ ní anfaani, tí ń darí rẹ, sí ọ̀nà tí ó yẹ kí o gbà.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Tọ́mi ni ọ̀nà tí ó yẹ kí n rìn, Olúwa. Fún mi ní ore-ọ̀fẹ́ láti mọ ìfẹ́ rẹ, ọ̀nà rẹ, iṣẹ́ rẹ, ọ̀rọ̀ rẹ, ìmọ̀ rẹ, àti agbára iṣẹ́ àmì rẹ ní Orúko Jésu
- Jẹ́kí ọ̀rọ̀ rẹ́ jẹ́ ìmọ́lẹ̀ nípa ẹ̀sẹ̀ mi, kín ba lè gbé ìgbésẹ̀ tí ó yẹ, ní ọ̀nà tí ó yẹ, láti jẹ́kí àyànmọ́n mi gẹ́gẹ́ bí ìfẹ́ fún mi wá sí ìmúṣẹ
- Máṣe dákẹ́ nígbàtí mobá ké pè ọ́ Olúwa, ṣùgbọ́n ṣí ojú mi kín bale rí àwọn ohun ìyanu tí èmi kò mọ̀.
- N kò sinmi lé òye mí, ṣùgbọ́n momọ̀ ọ, mosì ní àgbẹkẹ̀lé nínú rẹ, kí ó ba lè tọ́ ipasẹ̀ mi, ní Orúkọ Jésu, Àmín.
- Modúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ baba nítorí ìwọ ni olùṣọ́ àgùntàn ọkàn mí, lójoojúmọ́ ni èmí yóò má ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ìpàmọ̀ àti ìtọ́sọ́nà rẹ bí ó ti ń bámisọ̀rọ̀. Nítorínà, èmi kì yóò ní ìrújú nítorí ìwọ yó máa ṣọ́ mi pẹ̀lú ojú rẹ ní ibi gbogbo tí mo bá lọ.
- Olúwa, ìwọ ni olùràpadà mí, ẹni mímọ́ Ísráẹ́lì. Ìwọ yóò tọ́ mi nípa ọwọ́ rẹ, ó sì kọ́ mi láti jèrè ní orúkọ Jésù, Àmín.

## Ọ̀rọ̀ Àpérò

Ìpinu tí ó dára jùlọ tí
ẹnikẹ́ni le ṣe,
nipé kí wọ́n fi ayé wọn
fún Ọlọ́run kí o
má darí wọn

# ORÍ ÌKẸWÁ



## BABA WA TÍ Ń Bẹ LỌ́RUN -Èǹìyàn ológo

*Olúwa tí ó tóbi jùlọ, olùdá ayé àti ọ̀run, ìwọ ni Olorun Ábráhámù, Isaákì àti Jákọbù, eni mímọ́ Ísrelì, èmi ni tínje èmi ni, Olọ́run àwọn olọ́run, Olorun tí ó tiwà lánà, tín bẹ leni, tí ó sì maà wà títí ayé. Ó wà títí láilái, bàbá ìmole, ọba ológojùlọ, ìrawo òwúrọ̀, tí ó ti wà, tí ó ń be, tí ó sì ń bowá. Ìwo tí ìmole ngbe nínú re, tí ó sì mọ́ ohun tí ó wà nínú òkùnkùn. Olá ni fún orúkọ mímọ́ re. Àmín.*

## KÍ Á BỌ̀WỌ̀ FÚN ORÚKỌ RẸ -Ìyìn/ọlá

*Ìwọ ní Olorun mímọ́, òtítọ́ sì wà nínú re, mo gbàdúrà wípé òtítọ́ re yóò maá dàgbà sí nínú mi, yi o si tọ́ ìsíse mi. Ìwo ní ó tọ láti gba ìyìn.*

**Kronika Keji 29:11**
OLÚWA, o tóbi púpọ̀, tìrẹ ni agbára, ògo, ìṣégun, ati ọlá ńlá; nítorí tìrẹ ni ohun gbogbo ní ọ̀run ati ní ayé. Tìrẹ ni ìjọba, a gbé ọ ga bí orí fún ohun gbogbo.

*Ìwọ ni Olorun alàyè tí yóò jọba láilái, ìjoba re kò sí ní parun.*

## KÍ ÌJỌBA RẸ DÉ – Ìdí

**Kolose Kinni 1:16**
Nítorí pé, nípaṣẹ̀ rẹ̀ ni a ti dá ohun gbogbo, lọ́run ati láyé: ati ohun tí a rí, ati ohun tí a kò rí, ìbáà ṣe ìté ọba, tabi ìjọba, tabi àwọn alágbára, tabi àwọn aláṣẹ. Nípasẹ̀ rẹ̀ ni a ti dá gbogbo
nnkan, nítorí tirẹ̀ ni a sì ṣe dá wọn.

*Olúwa Olorun, mo gbàdúrà pe kí ife re pípé wá sí imúse nínú ayé mí nínú ayé yi. Ràǹmílowo láti mo ìfe re, ọ̀nà re, ise re, ogbọn re àti ìyanu agbára re.*

*Bàbá, fúnmí ní ore-ofẹ́ láti jẹ́ ìrìn ise fún ògo rẹ́, kín má ba kùnà lojo kẹ̀yìn, sùgbon kín le sá eré ìkẹ̀yìn fún ògo orúko rẹ́.*

## FÚŃ WÁ NÍ OÚŃJE OJO WA LONI- Ìpèsè

**Korinti Keji 9:8**
Ọlọ́run lè fun yín ní oríṣìíríṣìí ẹ̀bùn, tí ẹ óo fi ní ànító ninu ohun gbogbo nígbà gbogbo. Ẹ óo sì tún ní tí yóo ṣẹ́kù fún ohun rere gbogbo.

*Olúwa, pẹse oun gbogbo ti mo nilo gẹgẹ bi ogo rẹ ninu Kristi Jesu. Mo gbadura wipe, bi o se bukun fun mi, n ko ni ni idi lati tọrọ lọwọ ẹlòmíràn, sùgbọn sọ mi*

*di orisun ibukun fun ẹlòmíràn.*

**Luku 12:22-24**

Jesu bá sọ fún àwọn ọmọ-ẹ̀yìn pé, "Nítorí èyí ni mo ṣe sọ fun yín pé kí ẹ má máa páyà nípa ẹ̀mí yín, pé kí ni ẹ óo jẹ, tabi pé kí ni ẹ óo fi bora. Nítorí ẹ̀mí ṣe pataki ju oúnjẹ lọ, ara sì ṣe pataki ju aṣọ lọ. Ẹ ṣe akiyesi àwọn ẹyẹ; wọn kì í fúnrúgbìn, béẹ̀ ni wọn kì í kórè. Wọn kò ní ilé tí wọn ń kó nǹkan pamọ́ sí, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò ní abà. Sibẹ Ọlọ́run ń bó wọn. Mélòó-mélòó ni ẹ fi sàn ju àwọn ẹyẹ lọ.

*Baba, mo gbàdúrà wípé kí ìlérí àti ìbùkún Ábráhámù ma e fòmí run. Ìbùkún Ábráhámù jẹ́ tèmi, mo sì gba ìlérí ẹ̀mi nípase ìgbàgbo.*

**Malaki 3:10**

Ẹ mú gbogbo ìdáméwàá yín wá sí ilé ìṣúra, kí oúnjẹ baà lè wà ninu ilé mi. Ẹ ṣe bẹ́ẹ̀ kí ẹ fi dán mi wò, bí n kò bá ní ṣí fèrèsé ọ̀run sílẹ̀, kí n sì tú ibukun jáde fun yín lọpọlọpọ, tóbẹ́ẹ̀ tí kò ní sí ààyè tó láti gbà á.

*O ti se ìlérí láti pèsè fún mi nípa sisí fèrèsé orun láti dá ìbùkún sórí mi. Mo gbàdúrà wípé bí mo se ń bu olá fún oro rẹ láti má san ìdámeewá mi, ìlérí yí yio jẹ́ tèmi, ń o sì jẹ́ orísun ìbùkún fún àwon ẹlòmíràn.*

**Orin Dafidi 37:25**

Mo ti jẹ́ ọmọde rí; mo sì ti dàgbà: n kò tî ri kí á kọ olódodo sílẹ̀, tabi kí ọmọ rè máa tọrọ jẹ.

*Bí mo tín se àsàrò oro re l'ọsan àti ní òru, n ó se rere ní ohun gbogbo tí mo bá dáwo lé, làálàá mi kò ní já sásán. Je kí igi mí kí ó dàgbà ní àsìkò tí ó ye.*

**Johanu Kinni 1:9**

Ṣùgbọ́n bí a bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa: olóòótó ati olódodo ni òun, yóo wẹ àìṣedéédé gbogbo nù kúrò lára wa

*Modúpẹ́ toripé ẹti dárí ese mi jìmí. Rànmílọ́wọ́ láti le daríjì àwon tí ó sẹ̀ mí, pàapà nígbàtí mobá ní ìnira láti pa òfin rẹ̀ yí mo. Nkò fẹ́ gbé nínú ara, kí n sì gbàdúrà fún àwon tí ó sẹ̀ mí; jẹ́kí ìfẹ́ rẹ bòmí kín sìle fi ifẹ yi hàn sí elòmíràn.*

**Johanu Kinni 2:9**

Ẹni tí ó bá wí pé òun wà ninu ìmọ́lẹ̀, tí ó kórìíra arakunrin rẹ̀, wà ninu òkùnkùn sibẹ.

*Olúwa Olorun, nkò jẹ nǹkankan jú àkísà ẹlẹ́gbin níwájú rẹ, ẹ̀sẹ̀ mi sì pon bí àlàárì. Sùgbọ́n mo wá síwájú*

*rẹ́ nínú àdúrà, mo sì jẹ́wọ́ ẹ̀sẹ̀ mi fún ọ, mo gbàgbọ wípé mo ti ri ìdáríjì gbà.*

**Efesu 1:7**
Nípasè Kristi ni a ti ní ìdándè nítorí ẹ̀jẹ̀ tí ó ta sílẹ̀. Nípasè rè ni a ti rí ìdáríjì gbà fún àwọn ìrékọjá wa, gégé bí òpọ̀ oore-òfé rẹ̀.

**Matiu 26:28**
Èyí ni ẹ̀jẹ̀ mi tí a fi dá majẹmu, ẹ̀jẹ̀ tí a ta sílè fún ìdáríjì ẹ̀jẹ̀ ọpọlọpọ eniyan

*Jésu, oní agbára láyé láti dáríjí mi, nítorína mo wá síwájú re báyiì, mo sì n bèère fún àánú àti ore-ofe re fún ìwenùmọ́ kúrò nínú àìgbọ́ràn, àìnigbàgbo, iyèméjì, àti sise okàn méjì. Mo bèère fún eyí ní Orúko Jésù tí ó se iyebíye.*

**Diutaronomi 7:9**
Nítorí náà, ẹ máa ranti pé OLÚWA Ọlọ́run yín ni Ọlọ́run, Ọlọ́run olótìítọ́ tíí pa majẹmu mọ́, tíí sì ń fi ìfé ńlá rẹ̀ hàn sí àwọn tí wọ́n bá fẹ́ ẹ, tí wọ́n sì ń pa òfin rè mọ́, títí dé ẹgbẹrun ìran.

**Mika 7:18-19**
Ta ló dàbí rẹ, Ọlọ́run, tí ó ń dárí ẹ̀ṣẹ̀ ji eniyan, tí ó sì ń fojú fo ẹ̀ṣẹ̀ àwọn eniyan ìní rè yòókù, ibinu rẹ kì í wà títí lae, nítorí pé a máa dùn mọ́ ọ láti fi ìfé rẹ̀ tí kì í yè hàn. O óo tún ṣàánú wa, o óo sì fẹsẹ̀ tẹ ẹ̀ṣẹ̀ wa ní àtẹ̀parẹ́. O óo sọ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa ṣí ìsàlẹ̀ òkun.

*Bàbá aláànú júlọ otun ni àánú rení ojojúmo, nítorinà, mo bèère wípé kí ó fi aso àánú re wò mí ní oní àti ní ojoojúmo. Máse jekí n mase àlaìri ore-ofé gbà láti odo rè, máse wo èsè mi láti se ìdájó mi. Je kí ìfé re tí ó pé àti e je o mo re Jésù Krístì pa e se mi re.*

**MÁFÀWÁ SÍNÚ ÌDÁNWÒ/ Ipámọ́**

**Peteru Keji 2:9**
Olúwa mọ ọ̀nà láti yọ àwọn olùfọkànsìn kúrò ninu ìdánwò, ṣugbọn ó pa àwọn alaiṣododo mọ́ de ìyà ọjọ́ Ìdájọ́.

**Efesu 6:10-11**
Ní ìparí, ẹ jé alágbára ninu Olúwa, kí ẹ fi agbára rè ṣe okun yín. Ẹ gbé gbogbo ihamọra Ọlọ́run wọ̀, kí ẹ lè dúró láti dojú kọ èṣù pẹlu ọgbọ́n àrékérekè rẹ̀.

*Olúwa Olorun, ró mi lágbára nípasẹ̀ emi mímọ́ rẹ, kí èmí inú mi le se àtakò fún àdánwò tí èsù, tí ó'n gbìyànjú láti pa, láti jí àti láti ba isẹ́ rẹ̀ jẹ́ nínú ayé mi.*

**Jakobu 1:12**
Ẹni tí ó bá fi ara da ìdánwò kú

oríire, nítorí nígbà tí ó bá yege tán, yóo gba adé ìyè tí Ọlọ́run ṣe ìlérí fún àwọn tí ó fẹ́ràn rẹ̀.

*Olúwa, o jẹ́ olóòtọ́, ó sìmọ̀ àìlèra mi, sùgbọ́n ose ìlérí fún mi nínú ọ̀rọ̀ re wípé o kò ní je kín ní àdánwò tí ó kọjá oun tí mo le faradà, laî fi se ohunkóhun tí ó sẹlẹ̀. Mo mò pé o kii se adáníwò sùgbon aláye wo ni ọ́, rànmílọ́wọ́ láti se àseyorí nínú gbogbo àyewo rẹ ní orúko Jésù.*

**GBÀWÁ LỌ́WỌ́ IBI/Ìtùsílẹ̀**

**Aisaya 49:25**
OLÚWA ní: "Bí ó bá tilè ṣeéṣe láti gba ọ̀dẹ̀ lọ́wọ́ alágbára, tabi láti gba ìkógun lọ́wọ́ òkúrorò eniyan. N óo bá àwọn tí ó ń bá ọ jà jà, n óo sì gba àwọn ọmọ rẹ là.

*Mo jerí wípé ẹ̀jẹ̀ Jésù àti oro rẹ gbàmí sílẹ̀ lowo agbára àti èro òtá, níbaàyí àti ni ojo wajú.*

**Efesu 6:16-17**
Lẹ́yìn gbogbo nnkan wọnyi, ẹ fi igbagbọ ṣe ààbò yín. Nípa rẹ̀ ni ẹ óo lè fi pa iná gbogbo ọfà amúbíiná tí èṣù ń ta. Ẹ fi ìgbàlà ṣe fìlà onírin tí ẹ óo máa dé, kí ẹ sì mú idà Ẹ̀mí Mímó, tíí ṣe òrọ̀ Ọlọ́run.

**Johanu Kinni 4:4**
Ẹ̀yin ọmọde, ti Ọlọ́run nì yín, ẹ ti ṣẹgun ẹ̀mí alátakò Kristi nítorí pé ẹni tí ó wà ninu yín tóbi ju ẹni tí ó wà ninu ayé lọ.

*Mo jẹ́wo pe mo ní agbára àti àse nínú Jésù Krísti láti te gbogbo àwon tí o fẹ se mí níbi. Ìmọ̀ wọn máá ní ìkùnà n ó sì borí nítorí Jésù ti san gbèsè ná nípa rírànmípadà nípase títa ẹ̀jẹ̀ rẹ sílẹ̀.*

**Aisaya 43:2**
Nígbà tí o bá ń la ibú omi kọjá, n óo wà pẹlu rẹ; nígbà tí o bá la odò ńlá kọjá, kò ní bò ó mólè, nígbà tí o bá ń kọjá ninu iná, kò ní jó ọ.

**Orin Dafidi 32:7**
Ìwọ ni ibi ìsásí mi; o pa mí mọ́ kúrò ninu ìṣòro; o sì fi ìgbàlà yí mi ká.

*Olúwa Olorun, ẹ lè gbàmí sílẹ̀ lọ́wọ́ ẹrú àti àjàgà tí e kò gbé rùmí, pẹ̀lú àwon tí mo ti fi àìmokan gbé ru arà mi. Nítorínà bàba, e gbàmí kúrò nínú gbogbo ìponjú otá, mo sì de gbogbo isẹ́ won lórí ayé mi nísisìnyín àti láìlaí.*

**NÍTORÍ ÌJỌBA NÍ TÌRẸ, AGBÁRA NÍ TÌRẸ, ÒGO NI TÌRE, LÁI ÀTI LÁILÁI, ÀMÍN _ Ìjọ́sìn**

**Orin Dafidi 103:2**
Yin OLÚWA, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo oore rẹ̀

**Kronika 16:29**
Ẹ fi ògo tí ó yẹ orúkọ OLÚWA fún un, ẹ mú ọrẹ wá sí iwájú rẹ̀! Ẹ sin OLÚWA pẹlu ẹwà mímọ́.

**Romu 12:1**
Njẹ́ nítorí náà, ẹ̀yin ará, mo f'Ọlọ́run aláàánú bẹ̀ yín pé kí ẹ ya ara yín sọ́tọ̀ bí ẹbọ mímọ́ tí ó yẹ láti fi sin Ọlọ́run. Èyí ni iṣ ẹ́ ìsìn tí ó yẹ yín.

*Olúwa, ifẹ yín fún ayé mi ni kín yín ó fún ẹni tí ejẹ́ àti ohun tí e jẹ́sí mi. Modúpẹ́ nítorí ẹ̀ ń fi ojojúmo dí ẹ̀rù ìbùkún yín rù mí, mọ́ yìn ọ́ fún àwon oore wo nyi.*

**Ifihan 4:11**
"Olúwa Ọlọ́run wa, ìwọ ni ó tọ́ sí láti gba ògo, ati ọlá ati agbára. Nítorí ìwọ ni ó dá ohun gbogbo, ati pé nípa ìfẹ́ rẹ ni wọ́n ṣe wà, nípa rẹ ni a sì ṣe dá wọn."

**Heberu 12:28**
Nítorí náà, níwọ̀n ìgbà tí ẹ ti gba ìjọba tí kò ṣe é mì, ẹ jẹ́ kí á dúpẹ́. Ẹ jẹ́ kí á sin Ọlọ́run bí ó ti yẹ pẹlu ọ̀wọ̀ ati ẹ̀rù

*Ọlọ́run àwon Ọlọ́run, Oba àwon ọba, gba ọpe mi fún àilèrami tí ó mu kúrò, mo yìn ọ́ bí o ti fún mi ní ìwòsan tí o péye.*

*Mo bèèrè fún gbogbo èyí ní Orúko Jésu Krístì Olúwa wa, Àmín.*

## Ọ̀rọ̀ Àpérò

Ọ̀lọ́run ní o ṣẹda ẹ̀rọ àgbélọ́wọ́ àkọ́kọ́ tí a ní, àdúrà ní o sì pe orúkọ rẹ̀. Kò nílò kafi owó sí orí rẹ kí á tó rílò, ó sì̀n ṣiṣẹ́ níbi gbogbo. Ẹlo níbikíbi.

## Àwàdà

**Ìyàwò mẹ́rìndínlógún**

Ọ̀dọ́mọdé kùnrin kan ni ó lọ sí ìsìn ìgbéyàwó fún ìgbà àkọ́kọ́ ní ayé rẹ. Lẹ́yìn ìsìn náà, arákùnrin rẹ bèère lọ́wọ́ rẹ wípé “obìnrin mélò ni ọkùnrin le fẹ́”? Ọmọdékùnrin náà fèsì wípé “mẹ́rìndínlógún”. Èyí jẹ́ ìyàlẹ́nu fún arákùnrin rẹ́, ó sì bì léèrè pe báwo ni o ṣe mọ̀? ọmọdékùnrin náà dáhùn wípé ìyẹn rọrùn, àlùfáà sọ wípé nínú ìpọ́njú àti ìgbà tí ó rọrùn, nínú níní àti àìní, àlúfàa sọ gbogbo ẹ̀yin lẹ̀ẹ̀ mẹ́rin mẹ́rin, ó jásípé mẹ́rin lọ́na mẹ́rin jẹ ìyàwó mẹ́rìndínlógún.

# ORÍ ÌKẸ̀RÌNLA

# ẸNI TÍ MOJẸ́ NÍNÚ KRÍSTI



## Ṣe Àṣàrò

**Korinti Kinni 1:2**
Sí ìjọ Ọlọ́run ti ó wà ní Kọrinti, àwọn tí a yà sí mímó nípa ìṣọ̀kan pẹlu Kristi Jesu, tí a pè láti jẹ́ eniyan ọ̀tọ̀, ati gbogbo àwọn tí ń pe orúkọ Olúwa wa Jesu Kristi níbi gbogbo, Jesu tíí ṣe Olúwa tiwọn ati tiwa.

**Korinti Keji 5:17**
Èyí ni pé nígbà tí ẹnikéni bá wà ninu Kristi, ó di èdá titun. Ohun àtijọ́ ti kọjá lọ. Ìgbé-ayé irú ẹni bẹ́ẹ̀ sì di titun.

**Efesu 1:3**
Ẹ jé kí á fi ìyìn fún Ọlọ́run Baba Olúwa wa Jesu Kristi, tí ó ti fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ ibukun ti ẹ̀mí fún wa lọ́run nípasẹ̀ Kristi.

**Iṣe Awon Aposteli 17:28**
Nítorí ẹnìkan sọ níbìkan pé: 'Ninu rẹ̀ ni à ń gbé, tí à ń rìn kiri, tí a wà láàyè.' Àwọn kan ninu àwọn akéwì yín pàápàá ti sọ ohun tó jọ bẹ́ẹ̀; wọ́n ní, 'Ọmọ rẹ̀ ni a jẹ́.'

**Kolose 2:10**
Ó sì ti ṣe yín ní pípé ninu rẹ̀. Òun níí ṣe orí fún gbogbo àwọn èmí ojú ọ̀run, ìbáà ṣe ìjọba tabi àwọn aláṣẹ.

**Johanu Kinni 4:13**
A mọ̀ pé à ń gbé inú Ọlọ́run ati pé òun náà ń gbé inú wa nítorí pé ó fún wa ní ẹ̀mí rẹ̀.

**Efesu 5:8**
Nítorí nígbà kan, ninu òkùnkùn patapata ni ẹ wà. Ṣugbọn ní àkókò yìí ẹ ti bọ́ sinu ìmọ́lẹ̀ nítorí ẹ ti di ẹni Olúwa. Ẹ máa hùwà bí ọmọ ìmọ́lẹ̀.

**Efesu 2:21-22**
Òun ni ó mú kí gbogbo ilé dúró dáradára, tí ó sì mú un dàgbà láti di ilé ìsìn mímó fún Olúwa. Ẹ̀mí ń kó àwa ati ẹ̀yin papọ̀ ní ìṣọ̀kan pẹlu Kristi kí á lè di ibùgbé Ọlọ́run.

**Peteru Kinni 1:3**
A dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run, Baba Jesu Kristi Olúwa wa, tí ó fi ọ̀pọ̀ àánú rẹ́ tún wa bí sí ìrètí tí ó wà láàyè nípa ajinde Jesu Kristi kúrò ninu òkú.

**Johanu Kinni 1:7**
Ṣugbọn bí a bá ń gbé inú ìmọ́lẹ̀, bí òun náà ti wà ninu ìmọ́lẹ̀, a ní ìrépọ̀ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ̀ Jesu Ọmọ rẹ̀ sì ti wẹ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa nù kúrò lára wa.

**Romu 6:11**
Bákan náà ni kí ẹ ka ara yín bí ẹni tí ó ti kú ní ayé ẹ̀ṣẹ̀, tí ó tún wà láàyè pẹlu Ọlọ́run ninu Kristi.

**Galatia 3:13-14**

Kristi ti rà wá pada kúrò lábẹ́ ègún òfin, ó ti di ẹni ègún nítorí tiwa, nítorí ó wà ní àkọsílẹ̀ pé, “Ègbé ni fún gbogbo ẹni tí wón bá gbé kọ́ sórí igi.” Ìdí rẹ̀ ni pé kí ibukun Abrahamu lè kan àwọn tí kì í ṣe Juu nípasẹ̀ Kristi Jesu, kí á lè gba ìlérí Ẹ̀mí nípa igbagbọ.

**Korinti Kinni 15:57**

Ṣugbọn ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run tí ó fún wa ní ìségun nípasẹ̀ Olúwa wa Jesu Kristi.

**Filippi 4:13**

Mo lè ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹni tí ó ń fún mi ní agbára.

**Romu 8:37**

Ṣugbọn ninu gbogbo ìrírí wọnyi, a ti borí gbogbo ìṣòro nípa agbára ẹni tí ó fẹ́ràn wa.

**Galatia 2:20**

Mo wà láàyè, ṣugbọn kì í ṣe èmi ni mo wà láàyè; Kristi ni ó ń gbé inú mi. Ìgbé-ayé tí mò ń gbé ninu ara nisinsinyii, nípa igbagbọ ninu Ọmọ Ọlọ́run tí ó fẹ́ràn mi ni. Ó fẹ́ràn mi tóbẹ́ẹ̀ tí ó fi ẹ̀mí rẹ̀ lélẹ̀ nítorí mi.

**Romu 6:8**

Bí a bá jọ bá Jesu kú, a ní igbagbọ pé a óo jọ bá Jesu yè.

**Johanu 15:7-9**

Bí ẹ bá ń gbé inú mi, tí òrọ̀ mi ń gbé inú yín, ẹ óo bèèrè ohunkohun tí ẹ bá fẹ́, ẹ óo sì rí i gbà. Báyìí ni ògo Baba mi yóo ṣe yọ, pé kí ẹ máa so ọ̀pọ̀lọpọ̀ èso. Béẹ̀ ni ẹ óo ṣe jẹ́ ọmọ- ẹ̀yìn mi. Gẹ́gẹ́ bí Baba ti fẹ́ràn mi, béẹ̀ ni mo fẹ́ràn yín. Ẹ máa gbé inú ìfẹ́ mi.

**Maku 16:17-18**

Àwọn àmì tí yóo máa bá àwọn tí ó gbàgbọ́ lọ nìwọ̀nyí; wọn yóo máa lé ẹ̀mí burúkú jáde ní orúkọ mi; wọn yóo máa fi àwọn èdè titun sọ̀rọ̀; wọn yóo gbé ejò lọ́wọ́, wọn yóo mu òògùn olóró, ṣugbọn kò ní ṣe wón léṣe; wọn yóo gbé ọwọ́ lé àwọn aláìsàn, ara wọn yóo sì dá.”

**Titu 3:7**

Ó dá wa láre nípa oore-òfé kan náà, tí a fi ní ìrètí láti di ajogún ìyè ainipẹkun.

**Ifihan 1:6**

Ó sọ wá di ìjọba, ati alufaa Ọlọ́run Baba rẹ̀. Tirẹ̀ ni ògo ati agbára lae ati laelae. Amin.

**Heberu 13:5-6**

Ẹ má jẹ́ kí ìfẹ́ owó gbà yín lókàn. Ẹ ní ìtẹ̀lọ́rùn pẹlu ohun tí ẹ ní. Nítorí Ọlọ́run fúnrarẹ̀ ti sọ pé, “N kò ní fi ọ́ sílẹ̀, bẹ́ ẹ̀, ni n kò ní kọ̀ ọ́!” Bí ó bá rí bẹ́ ẹ̀, a lè fi ìgboyà sọ pé, “Olúwa ni olùrànl ọ́w ọ́ mi, ẹ̀rù kò ní bà mí. Ohun yòówù tí eniyan lè ṣe sí mi.”

# Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Èmi (sọ orúkọ rẹ), jẹ ara ọ̀run, aláṣeyọrí ni mo jẹ́, olùṣẹ́gun, mosì ju aṣẹ́gun lọ. ẹyinjú Ọlọ́run ni mo jẹ́, ènìyàn ọ̀tọ̀, ènìyan mímọ́. Nínú ìjáde àti ìwọlé mi, yío dára fún mi. Mo jẹ́ alábùkún fún pẹ̀lú ìbùkún Olúwa. Èmi kòní kú bíkò ṣe yíyè láti ròyìn iṣẹ́ Olúwa nínú ayé mi.

- Ìmọ́lẹ̀ mi á tàn sí lójoojúmọ́. Mo jẹ́ témpìlì Olúwa mo sì ní ọkàn Kristì. Ẹni tí ó ńgbé nínú mi jú ẹni tí ó ńgbé nínú ayé lọ.

- Ọmọ Ọlọ́run ni mí, èso rẹ̀ àti ọmọ Ábráhámù, nítorínà, mo jẹ́ olùṣẹ́gun. Nítorí Olúwa wà fún mi, kòsí ẹni tí ó le lòdì sí mi. Ìwọ ni Ọlọ́run tí ó sọ́mi pẹ̀lú agbára, tí ó sì mú ipasẹ̀ mi pé. Ìwọ ni ó mú ẹsẹ̀ mi dúróṣinṣin, mo sì ń tẹ̀síwájú nínú àyẹ̀wò àti ìdànwò.

- Mú mi dúró níbi gíga. O kọ ọwọ́ mi láti jà. O fún ọwọ́ mi ní agbára ọ̀run tí mosì le dá ìrìn. Ọrọ̀ àwọn kèfèrí jẹ́ tèmí, mo sì gba ohun ìní wọn lójoójúmọ. N o di ńlá níwájú àwọn ọba, ọ̀pọ̀ okun sì di tèmi. Ọmọ àjòjì yóò kọ́ ilé mi, ọba wọn yóò sìtọ́jú mi.

- Ìwọ ni àpáta mi, asà mi àti ibi ìsádi mi. Ẹ ti ṣe ìpèsè ọkọ̀ ìgbàlà rẹ fúnmi. Mo kéde pé ìgbà àti àkókò mi ńbẹ lọ́wọ́ rẹ Olúwa, ẹnikẹ́ni kòsì le bàjẹ́. Ẹ̀tọ́ Ọlọ́run ní ẹ̀tọ́ mi. Gbogbo ohun tí o jẹ́ tèmi ni Ọlọ́run yóò ṣe láṣepé. Ìwọ ni o bùkún mi tí o sì ń ró mi lágbára, kìí ṣe nípa agbára mi bíkòṣe nípa ẹ̀mí Ọlọ́run. Ẹ̀mi Ọlọ́run ńbẹ nínú mi, ẹ̀mí ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìmọ̀ràn àtọ̀runwá, pẹ̀lú agbára àtọ̀runwá. Mo jẹ́wọ́ wípé ipò àṣẹ àti ọlá jẹ́ tèmi, ojúrere, ore-ọ̀fẹ́, àti ìyìn rọ́po gbogbo ibi nínú ayé mi, ẹbí mi, ọ́wọ́ mí, iṣẹ́ mi, àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ tí a pè mí fún.

- Mo jẹ́wọ́ wípé Ọlọ́run ti mú mi wa sípò ọlá mi, mo sì gbé ní ilẹ̀ Góṣẹ́nì tí a ti pèsè fún mi. Ọlọ́run tí sọ mí di ńlá, ó mú mi pọ̀ si, mo sì ń ṣe rere ní ilẹ̀ tí mò ń gbé.

- Mo jẹ́ aṣojú Olúwa, gbogbo ẹ̀tọ́, iyì àti ọlá sìjẹ́ tèmi. Ore-ọ̀fẹ́, òótọ́, ìṣerere, àti àánú Ọlọ́run rọ̀ gbà yí mi ká.

- Mo jẹ́wọ́ wípé ọgbọ́n jẹ́ olùbádámọ̀ràn mi, Ẹ̀mi Mímọ́ jẹ́ olùbádárò mi, Jésù Krístì sí jẹ́ agbẹjọ́rò mi. Mo fìdí ẹ̀ múlẹ̀ wípé àláfia ní olùbáṣiṣẹ́ mi, ìṣòdodo ní olùdarí mi, ìgbàlà ní odi mi, ìyìn sí ni ìlẹ̀kùn àbáwọlé mi. Àkókò ojúrere mi ti dé, kòsí ni pinmílẹ́mì. A kò ní bààjẹ́, a kò ní paárun, a kò ní ge kúrú, kò ní gbẹ, kòsì ní ku.

- Mo gba ìtùsílẹ̀ ìṣura àti ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ tèmí. Gbogbo ohun tí a ti pèsè sílẹ̀ fún mí kí a tó dá mi sínú ìyá mi, àti kí a tó ṣe ìpínlẹ̀ṣẹ̀ ayé, tí ó jẹmọ́ ayé mí, ìpè mí, ẹbí mí, àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ mí wà fún báyìi. Mo kọ àyọkúrò. Mo pe gbogbo ohun èlò láti ìlà òorùn, ìwọ́ oòrùn, gúsù, àti àríwá. Nítorínà, a kòní fi ẹ̀tọ́ mi dùn mí. Mo jẹ́wọ́ wípé àti fi ẹ̀jẹ̀ rà mí, a ti dáríjìmí, a ti ràmípadà, ọmọ Ọlọ́run tí ó ńlọ sí Ọ̀run ni mí, ní orúkọ Jésù Krístì Olúwa àti Olùgbàlà mí.

**Ọ̀rọ̀ Àpérò**

Bí ó ti ṣè gbà Jésù Krístì ní Olúwa, máá rìn nínú rẹ̀.

ROSE OF SHARON GLORIOUS MINISTRY INT'L

Gbádùn

# Àsìkò Àdúrà Ọtun



**Ni ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kẹ̀jì Olóoṣọ̀ṣụ

# ORÍ ÌKẸJÌLA

## ÌṢÌPẸ



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 6:9**
OLÚWA ti gbọ́ ẹ̀bẹ̀ mi, OLÚWA ti tẹ́wọ́gba adura mi.

**Filippi 4:6**
Ẹ má ṣe jẹ́ kí ohunkohun dààmú yín, ṣugbọn ninu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ yín, ẹ máa fi àwọn ìbéèrè yín siwaju Ọlọ́run pẹlu ọpẹ́.

**Efesu 6:18**
Ẹ máa gbadura nígbà gbogbo, kí ẹ máa fi gbogbo ẹ̀bẹ̀ yín siwaju Ọlọ́run nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́. Nítorí náà, ẹ máa gbadura láì sùn, láì wo, fún gbogbo àwọn èniyàn Ọlọ́run.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

Mo fi ọpẹ́ fún Olúwa tí ó kàmí yẹ láti jẹ́ alábàpín ogún àwọn ẹni mímọ́

Nkò mú ìṣìpẹ̀ mi wá sí iwájú rẹ nítorí iṣẹ́ òdodo mi, ṣùgbọ́n nítorí ọ̀pọ̀ àànú rẹ, Olúwa, gbọ́ mi kí o ṣìṣe. Àmín

Ọkàn mi ńdúró de ọ Olúwa. Ìrètí mi wà nínú rẹ àpáta mi àti ìgbàlà mi. N ó dírọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ rẹ, ẹsẹ̀ mí kò sí ní yẹ̀.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Tọ́ ipa ẹsẹ̀ mí nínú rẹ, kí ẹsẹ̀ mí má ṣe yẹ̀.

Pamímọ́ lábẹ́ ìyẹ́ rẹ kúrò lọ́wọ́ ẹni ibi àti ọ̀tá tí ó yímiká.

Tan ìmọ́lẹ̀ rẹ sínú òkùnkùn mí, kí ó sì tan fitílà mí.

Mú gbogbo ìdíwọ́ tí kò fẹ́ kí ògo mí yọ

Mú mi yẹ níwájú rẹ Olúwa, kíí ń so èso nínú ìṣerere, kíí n sì mú ìmọ̀ rẹ́ pọ̀ si.

Ró mi lágbára nínú agbára rẹ̀, fún sùúrù pẹ̀lú ayọ̀

## Àwàdà

### Agogo Ilé Ìjọsìn

Álúfàa kán wà ní ọ̀nà ilé ìjọsìn ní òwúrọ̀ ọjọ́ kan nígbàtí ó pàdé ọmọ ìjọ rẹ̀ kan tí ó ń ṣiṣẹ́ nínú ọgbà rẹ̀. "Ṣé o kó gbọ agogo tín pè ọ fún ìjọsìn ní?", àlúfàa náà bèère lọ́wọ́ ọmọ ìjọ rẹ̀. Ọmọ ìjọ ná fèsì wípé "éh, kínìyen"?
"Ṣé o kò gbọ́ agogo tí n pè ọ fún ìjọsìn ni?"
Ọmọ ìjo náà bání "ẹ sọ̀rọ̀ sókè ẹjọ̀, nkò gbọ yín."

"ṢÉ O KÒ GBỌ́ AGOGO ÌJỌSÌN NI?" Álúfàa náà pariwo sókè. Ọmọ ìjọ bá ní, ẹ má bínú, agogo yi kòjẹ́ kí n gbọ́ ohun tí ẹ ń sọ.

# ORÍ ÌKẸTÀLÁ

## ÌFẸ́ AYÉRAYÉ TÍ MO NÍ SÍ ỌLỌ́RUN



## Ṣe Àṣàrò

**Romu 8:31**
Kí ni kí á wá wí sí gbogbo nnkan wọnyi? Bí Ọlọ́run bá wà lẹ́yìn wa, ta ni lè lòdì sí wa?

**Romu 8:32**
Ọlọ́run, tí kò dá Ọmọ rẹ̀ sí, ṣugbọn tí ọ yọ̀nda rẹ̀ nítorí gbogbo wa, báwo ni kò ṣe ní fún wa ní ohun gbogbo pẹlu rẹ̀?

**Romu 8:33**
Ta ni yóo fi ẹ̀sùn kan kan àwọn ẹni tí Ọlọ́run ti yàn? Ṣé Ọlọ́run ni, òun tí ó dá wọn láre?

**Romu 8:34**
Àbí ta ni yóo dá wọn lẹ́bi? Dájúdájú, kò lè jẹ́ Kristi, ẹni tí ó kú, àní ṣé ẹni tí a jí dìde kúrò ninu òkú, tí ó jókòó ní ọwọ́ òtún Ọlọ́run, tí ó sì ń bẹ̀bẹ̀ fún wa.

**Romu 8:35**
Ta ni yóo yà wá kúrò ninu ìfẹ́ Kristi? Ìpọ́njú ni bí, tabi ìṣòro, tabi inúnibíni, tabi ìyàn, tabi òṣì, tabi ewu, tabi idà?

**Romu 8:37-38**
Ṣugbọn ninu gbogbo ìrírí wọnyi, a ti borí gbogbo ìṣòro nípa agbára ẹni tí ó fẹ́ràn wa. Nítorí ó dá mi lójú pé, kò sí ohunkohun–ìbáà ṣe ikú tabi ìyè, ìbáà ṣe àwọn angẹli tabi àwọn irúnmọlẹ̀, tabi àwọn ohun ayé òde òní tabi àwọn ti ayé tí ó ń bò,

**Korinti Kinni 10:13**
Kò sí ìdánwò kan tí ó dé ba yín bíkò ṣe irú èyí tí ó wọ́pọ̀ láàrin eniyan. Ṣugbọn Ọlọ́run tó gbẹ́kẹ̀lé kò ní jẹ́ kí ẹ rí ìdánwò tí ó ju èyí tí ẹ lè fara dà lọ. Ṣugbọn ní àkókò ìdánwò, yóo pèsè ònà àbáyọ, yóo sì mú kí ẹ lè fara dà á.

**Johanu 16:33**
Mo ti sọ nnkan wọnyi fun yín kí ẹ lè ní alaafia nípa wíwà ninu mi. Ẹ óo ní ìpónjú ninu ayé, ṣugbọn ẹ ṣe ara gírí, mo ti ṣẹgun ayé.”

**Numeri 23:19**
Ọlọ́run kò jọ eniyan tí máa ń puró, bẹ́ẹ̀ ni kì í ṣe eniyan tí máa ń yí ọkàn pada. Ohun tí ó bá ti sọ ni yóo ṣe, bí ó bá sì sọ̀rọ̀ yóo rí béè.

**Jeremaya 29:11**
Nítorí pé mo mọ èrò tí mò ń gbà si yín, èrò alaafia ni, kì í ṣe èrò ibi. N óo mú kí ọjọ́ òla dára fun yín, n óo sì fun yín ní ìrètí.

**Orin Dafidi 18:1**
Mo fẹ́ràn rẹ, OLÚWA, agbára mi.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Bàbá, nítorí Jésù kú fún mi, mo ní ẹ̀bùn ìgbàlà, a kò dá mi lẹ́bi mọ́ nítorí mo ní ore- ọ̀fẹ́ ìràpadà. A ti dámiláre, a sì ti tú mi sílẹ̀. Nígbàtí sàtánì bá pèmíníjà, Jésù agbẹjọ́rò mi ń ṣìpẹ̀ fún mi lápá ọ̀tún Ọlọ́run tí ó wà. Òdodo mi kòsì nínú iṣẹ́ ọwọ́ mi tàbí ìgbọràn mi, ṣùgbọ́n nínú Jésù Krístì. Òdodo Jésù si wà nínú Ọlọ́run

- Ìpọ́njú, ìyàn, ìhòhò, ewu tàbí idà kòle yà mí kúrò nínú ìfẹ́ Krístì.

- Moju aṣẹ́gun lọ nínú Ọlọ́run tí o fẹ́ mi. Ìwọ tí sọ, ìwọ kò ha ní ṣe bí? Nítorí o kò ní pàrọ̀, ọ̀rọ̀ rẹ kòsí ní padà wá lófo láì ṣe èyi tí ó rán, nítorí ó ti gbe ọ̀rọ̀ rẹ̀ ga ju ohun gbogbo lọ, ó sì tún gbégaju Orúko rẹ̀ lọ.

- Mo hó ìhó ayọ̀ sí Olúwa, mo wà sí iwájú rẹ pẹ̀lú orin ìyìn. Ẹ̀mi ni àgùntàn pápáa rẹ̀ Ọlọ́run mi ni, èmi si jẹ̀ tirẹ̀. Ó da mí pẹ̀lú ọwọ́ ìfẹ́ rẹ̀, ó sì mọ̀mí látinú ìyá mi wá. Nítorínà, mo fibùkún fún orúkọ rẹ̀ títí, nítorítí ore rẹ̀ wà títí laílaí, òtítọ́ rẹ̀ dúró láti ìgbà dé ìgbà.

- Mo fẹ́ Olúwa pẹ̀lú gbogbo ọkàn mi, n ó sì fi iṣẹ́ rere rẹ̀ hàn. Ìfẹ́ rẹ kùn ọ̀run, òtítọ́ rẹ̀ sí wà láti ìgbà dé ìgbà. Ọkàn mi yọ̀ nínú rẹ Olúwa Ọlọ́run àpata mi.

## Àwàdà

**Ohun tó sọnù tá ri pada**

`

Ọmọkùnrin kan rí àpò owó, ó ṣì pe ìkànnì agbóhùn sáfẹ́fẹ́, ónì, hèlló, mo rí àpò owó tí ẹgbẹ̀rún lọ́nà ẹgbẹgbẹ̀rún owó wà nínú rẹ̀, pẹ̀lú káàdì ìdánimọ̀, pẹ̀lú káàdì ìgbowó tí ó jẹ́ ti ọkùnrin kán tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ arákùnrin Fikto James tí o ńgbe ní ìkòyí. Ẹni tí o wa nì íkànnì agbóhùn sáfẹ́fẹ́ ná bà dáhùn wípé, olóòtọ́ ènìyàn ni ọ́, mo sì nígbàgbọ́ wípé o fẹ́ dá àpò náà padà ní.

Ọmọkùnrin náà bá fèsì wípé rárá o, nígbàtí ń kò ya wèrè, fún kíni? mokàn fẹ́ kí ẹ bámi kọrin kán fún ni o. Ẹbá mikọ ALAANU MI....

# Rose of Sharon Glorious Ministry Int'l

Gbádùn

## `asìkò Ìfàmì `oróró yàn



**Ni ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé keji Olóoṣòṣu

# ORÍ ÌKỌ̀KÀNLÁ

## MÍMỌ ÌFẸ́ỌLỌ́RUN



## Ṣe Àṣàrò

**Galatia 3:13**
Kristi ti rà wá pada kúrò lábẹ́ ègún òfin, ó ti di ẹni ègún nítorí tiwa, nítorí ó wà ní àkọsílẹ̀ pé, "Ègbé ni fún gbogbo ẹni tí wọ́n bá gbé kọ́ sórí igi."

**Kolose 1:13**
Baba wa náà ni ó gbà wá lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, ó sì mú wa wá sinu ìjọba àyànfẹ́ Ọmọ rẹ̀.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Olúwa Ọlọ́run, a wa síwájú ìtẹ́ rẹ, a jẹ́wọ́ wípé ìwọ ni olùdájọ́ òdodo ní ayé, pẹ̀lú ìdùnú ní a sìfi wá síwájú rẹ ní òní.
- Aní ẹ̀tọ́ láti wá nítorí a ní májẹ̀mú ẹ̀jẹ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì. À ń bèerè fún àánú, a sì ń bèere fún ojúrere àti ore-ọ̀fẹ́, a bèère fún ìdájọ́ òdodo nítorí o ti ṣṣèlérí òmìnira àti ìtúsílẹ̀ nípasẹ̀ òtítọ́ ọ̀rọ̀ rẹ. Gẹ́gẹ́ bí ọmọ rẹ, à ní ẹ̀tọ́ sí òmìnira a sì gba wípé a kòsì nínú ìgbèkùn ọ̀tá.
- Májẹ̀mú ìgbèkùn àti èmi àti àwọn baba baba wa mọ̀ọ́mọ̀ wọ̀ tàbí ṣèsì wọ̀ ńdè wá mólẹ̀. Ágbà wípé ati sẹ̀. Asì gbà wípé ó tọ́síwa láti wà nínú ìgbèkùn. Bí àwọn ǹkan wọ̀nyí tilẹ̀ jẹ́ òótọ́, òótọ́ kan wà tógaju èyí lọ, òótọ́ yí sìni wípé a lé kúrò nínú ìgbèkùn. Awá pẹ̀lú ìjẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyí:

- Èmi àti àwọn baba ńlá mi ti bọ òrìṣà. O sì sọfún wa nínú òfin mẹ́wà rẹ wípé kí á máṣe bọ òrìṣà kankan yálà tinú omi tàbí tí orí-ilẹ̀, kí á má sìṣe yá ère kankan sọ́tọ̀ fún ara wa. A ti tàpá sófin rẹ, asì tiṣẹ̀ sí ọ. Èmi àti àwọn baba mí tidá ìjọsìn pọ̀mọ́ ìbálọ̀pọ̀. A ti da ẹ̀sìn mọ́ ìsìn. Ẹ̀ṣẹ̀ nì àwọn wọ̀nyí jẹ́ a sì kọ ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyí sílẹ̀.
- Èmi àti àwọn baba mi lọ́wọ́ nínú ẹ̀ṣẹ̀ àìṣedéedé, dída májẹ̀mú, àgbèrè àti panṣágà, ẹ̀ṣẹ̀ àìmọ̀, gbígba owó ẹyìn, ìbọ̀rìṣà, ìkórira, ìjà, owú, ìmọtara ẹni nìkan, ìpàniyàn, ìmutí para, iró pípa àti bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ. Ẹ̀ṣẹ̀ ni gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́. Èèwọ̀ sì ní wọ́n níwájú rẹ. A fagi le wọ́n, a sí kọ̀ wọ́n sílẹ̀. Lára wa tijẹ arúfin láwùjọ, a ti yan ìjọba jẹ nínú owó orí wa, a sì tí lọ́wọ́ nínú ìwà ìbájẹ́.
- Ati lọ ilé oníṣègùn, asì ti darapọ̀ mọ ẹgbẹ́ òkùnkùn. Ati wọ́nu orísirísi májẹ̀mú pẹ̀lú sàtánì láìmọ̀.
- A ti sin Ọlọ́run míràn nípa gbígba elòmíràn àti afẹ́ ayé láti jẹ́ àkọ́kọ́

- nínú ọkàn wa, àwọn nnkan bi iṣẹ́, ọkọ/aya wa, ọmọ wa, àti afẹ́ aye. A ti nífẹ̀ àwọn ohun tí ó dá jú ìwọ tí o dá wọn, a sì ti jẹ́kí àwọn nnkan wọ̀nýi gba ipò rẹ nínú ayé wa.

- Baba, ajẹ́wọ́ wípé ìrúfin jẹ́ èèwọ̀ sí ọ. Kìí ṣe ohun kékeré, ó sì ti ṣílẹ̀kùn fún ọ̀tá nínú ayé wa. A bèère Olúwa wípé kí o ṣì àkọsílẹ̀ gbogbo mọ̀lẹ́bí wa láti ìbẹ̀rẹ̀ ayé, a sì béèrè wípé kí o tọ́ka sí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ àti àìṣedéédé wá tí o ti ṣílẹ̀kùn fún ìgbèkùn àti májẹ̀mù ibi. Jẹ́kí ìwé ìfẹ̀sùnkàn wa wà níwájú ìtẹ́ rẹ, a sì sọpe a jẹ̀bi baba. Àkọsílẹ̀ náà jẹ́ òtítọ́, ìgbèkùn sítọ́ síwa. Agbà wípé ajẹ̀bi gbogbo ẹ̀sùn tí wọn fí kàn wá.

- Ṣùgbọ́n baba, lòdì sí gbogbo ẹ̀sùn wọ̀nyíi, alo ẹ̀jẹ Jésù. Asọwípé Jésù kú lórí igi àgbélèbú láti wẹ ẹ̀ṣẹ̀ wa nù. Asọwípé gbogbo ẹ̀gún àti májẹ̀mú ibi ní á kànmọ́ àgbélébù tí asì fi ẹ̀jẹ̀ jésù bọ ni ẹgbẹgbẹ̀rún ọdún sẹ́yìn. Kòsí ohun tí èmí tàbí àwọn baba mí ṣẹ̀ tí akò tí kànmọ àgbélébu pẹ̀lú Jésù Krístì. Nítorínà, agbé ẹ̀jẹ̀ Jésù wá dípò gbese tí a jẹ ọ.

## Ọ̀rọ̀ Àpérò

Ọlọ́run kòní mú ọ de
`làjì ọ̀nà kí ó wá já ọ kulẹ̀.

**ROSE OF SHARON GLORIOUS MINISTRY INT'L**

Gbádùn

# àsìkò fífúni ọ̀tun



**Ni ibi**

**Ètò Àdúrà**

***Beeni Oluwa!***

ti Sátidé kẹ̀jì Olóoṣòṣu

# ORÍ ÌKẸẸDÓGÚN

## DÍDA ÀGBO MÁJẸ̀MÚ BURÚKÚ DÀNU

## Ṣe Àṣàrò

**Galatia 3:13**
Kristi ti rà wá pada kúrò lábẹ́ ègún òfin, ó ti di ẹni ègún nítorí tiwa, nítorí ó wà ní àkọsílẹ̀ pé, "Ègbé ni fún gbogbo ẹni tí wọ́n bá gbé kọ́ sórí igi."

**Kolose 1:13**
Baba wa náà ni ó gbà wá lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, ó sì mú wa wá sinu ìjọba àyànfẹ́ Ọmọ rẹ̀.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Olúwa Ọlọ́run, a wa síwájú ìtẹ́ rẹ, a jẹ́wọ́ wípé ìwọ ni olùdájọ́ òdodo ní ayé, pẹ̀lú ìdùnú ní a sìfi wá síwájú rẹ ní òní.

- Aní ẹ̀tọ́ láti wá nítorí a ní májẹ̀mú ẹ̀jẹ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì. À ń bèerè fún àánú, a sì ń bèere fún ojúrere àti ore-ọ̀fẹ́, a bèère fún ìdájọ́ òdodo nítorí o ti ṣ̀ṣèlérí òmìnira àti ìtúsílẹ̀ nípasẹ̀ òtítọ́ ọ̀rọ̀ rẹ. Gẹ́gẹ́ bí ọmọ rẹ, à ní ẹ̀tọ́ sí òmìnira a sì gba wípé a kòsì nínú ìgbèkùn ọ̀tá.

- Májẹ̀mú ìgbèkùn àti èmi àti àwọn baba baba wa mọ̀ọ́mọ̀ wọ̀ tàbí ṣèsì wọ̀ ńdè wá mólẹ̀. Ágbà wípé ati sẹ̀. Asì gbà wípé ó tọ́síwa láti wà nínú ìgbèkùn. Bí àwọn ǹkan wọ̀nyí tilẹ̀ jẹ́ òótọ́, òótọ́ kan wà tógaju èyí lọ́, òótọ́ yí sìni wípé a lé kúrò nínú ìgbèkùn. Awá pẹ̀lú ìjẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyí:

- Èmi àti àwọn baba ńlá mi ti bọ òrìṣà. O sì sọfún wa nínú òfin mẹ́wà rẹ wípé kí á máṣe bọ òrìṣà kankan yálà tinú omi tàbí tí orí-ilẹ̀, kí á má sìṣe yá ère kankan sọ́tọ̀ fún ara wa. A ti tàpá sófin rẹ, asì tiṣẹ̀ sí ọ. Èmi àti àwọn baba mí tidá ìjọsìn pọ̀mọ́ ìbálọ̀pọ̀. A ti da ẹ̀sìn mọ́ ìsìn. Ẹ̀ṣẹ̀ nì àwọn wọ̀nyí jẹ́ a sì kọ ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyí sílẹ̀.

- Èmi àti àwọn baba mi lọ́wọ́ nínú ẹ̀ṣẹ̀ àìṣedéedé, dída májẹ̀mú, àgbèrè àti panṣágà, ẹ̀ṣẹ̀ àìmọ̀, gbígba owó ẹyìn, ìbọ̀rìṣà, ìkórira, ìjà, owú, ìmọtara ẹni nìkan, ìpànìyàn, ìmutí para, irọ́ pípa àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ̀ṣẹ̀ ni gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́. Èèwọ̀ sì ní wọ́n níwájú rẹ. A fagi le wọ́n, a sí kọ̀ wọ́n sílẹ̀. Lára wa tijẹ arúfin láwùjọ, a ti yan ìjọba jẹ nínú owó orí wa, a sì tí lọ́wọ́ nínú ìwà ìbàjẹ́.

- Ati lọ ilé oníṣègùn, asì ti darapọ̀ mọ ẹgbẹ́ òkùnkùn. Ati wọńu oríṣiríṣi májẹ̀mú pẹ̀lú sàtánì láìmọ̀.

- A ti sin Ọlọ́run míràn nípa gbígba elòmíràn àti afẹ́ ayé láti jẹ́ àkọ́kọ́ nínú ọkàn wa, àwọn nǹkan bi iṣẹ́, ọkọ/aya wa, ọmọ wa, àti afẹ́ aye. A ti nífẹ̀ àwọn ohun tí ó dá jú ìwọ tí o dá wọn, a sì ti jẹ́kí àwọn nnkan wọ̀nyí gba ipò rẹ nínú ayé wa.

- Baba, ajẹ́wọ́ wípé ìrúfin jẹ́ èèwọ̀ sí ọ. Kìí ṣe ohun kékeré, ó sì ti ṣílẹ̀kùn fún ọ̀tá nínú ayé wa. A bèère Olúwa wípé kí o ṣì àkọsílẹ̀ gbogbo mọ̀lẹ́bí wa láti ìbẹ̀rẹ̀ ayé, a sì béèrè wípé kí o tọ́ka sí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ àti àìṣedéédе wá tí o ti ṣílẹ̀kùn fún ìgbèkùn àti májẹ̀mù ibi. Jẹ́kí ìwé ìfẹ̀sùnkàn wa wà níwájú ìtẹ́ rẹ, a sì sọpe a jẹ̀bi baba. Àkọsílẹ̀ náà jẹ́ òtítọ́, ìgbèkùn sítọ́ síwa. Agbà wípé ajẹ̀bi gbogbo ẹ̀sùn tí wọn fí kàn wá.

- Ṣùgbọ́n baba, lòdì sí gbogbo ẹ̀sùn wọ̀nyíi, alo ẹ̀jẹ Jésù. Asọwípé Jésù kú lórí igi àgbélèbú láti wẹ ẹṣẹ̀ wa nù. Asọwípé gbogbo ẹ̀gún àti májẹ̀mú ibi ní á kànmọ́ àgbélébù tí asì fi ẹ̀jẹ̀ jésù bọ ni ẹgbẹgbẹ̀rún ọdún sẹ́yìn. Kòsí ohun tí èmí tàbí àwọn baba mí ṣẹ̀ tí akò tí kànmọ àgbélébu pẹ̀lú Jésù Krístì. Nítorínà, agbé ẹ̀jẹ̀ Jésù wá dípò gbese tí a jẹ ọ.

- Baba, ọ̀rọ̀ rẹ sọwípé tí abá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, ẹkò ní dáríjì wá nìkan, e ó wẹ̀wámọ́, a sì gbá ìwẹ̀nùmọ yí fún ara wa àti àwọn ọkọ /aya, pẹ̀lú fún àwọn ọmọ tí ó ti ara wa jáde nínú ara tàbí nínú ẹ̀mí títí kan àwọn ìran wà tí ó nbọ̀ lẹ́yìn. Asọwípé ẹ̀tọ́ tí àwọn ìgbèkùn wọ̀nyíi ní síwa ti lọ, fún ìdi èyí, a bá èṣù wí ní orúkọ Jésù, àti gbogbo ẹ̀mi òkùnkùn tí wọ́n yàn tí ẹ̀mí, mọ̀lẹ́bí mi, ìjọ mi, isẹ́ ìránṣẹ́ mí àti owó mi, torí àti pa ẹ̀ṣẹ̀ mi rẹ́.

- Apàṣẹ pé kí wọ́n lọsí ọ̀gbun àìnísàlẹ̀, kí wọ́n má sìṣe padà wá mọ́. Baba, o kìí ṣe onídajọ́ nìkan, ìwọ ni Olúwa lórí àwọn ángẹ́lì. A bèère wípé kí o fi ìdí òdodo múlẹ̀. A bèèrè wípé kí o rán angẹ́lì rẹ láti le ẹ̀míkẹ̀mí tí ó bakù dànù.

- Gbogbo ibi tí òmìnira titọ́ sí wa, a bèèrè wípé kí o fúnwa ní òmìnira. A bèèrè wípé kí ònì jẹ́ ọjọ́ ìyípadà. Ìyàtọ̀ yóò wà nínú ayé wa, ilé wa, ìjọ wa, ìsìn wa àti ìbárìn wa pẹ̀lú yín láti ònì lọ.

- A dúpẹ́ fún ẹ̀jẹ̀ Jesù Krístì, a dúpẹ́ fún àjíǹde rẹ, tí ó fúnwa nì agbára láti wàláyé. A bèèrè fún agbára ìyípadà, láti máṣe kọjá ayé wa. Ati fọ́jú fo ìgbé ayé wa tẹ́lẹ̀.

- A bèèrè fún ìsọjí ẹ̀mí, kí ó sì fúnwa ní àyà ìgbáṣẹ. A gba ẹ̀mí ìgbọràn fún ara wa àti fún ìran tí ó nbọ wá lẹ́yìn wá. Fún wa ní ìgbé ayé tuntun, èyí tí yóò wù ó, sọ ọkàn wa jí, kí a sì mọ́wa sí ẹ̀mí mímọ́ tí óhún sìṣẹ́ nínú ojúrere Ọlọ́run, ní ọjọ́ ìkẹyìn, kí ẹ sì kàwá yẹ.

- A beèrè fún gbogbo èyí ní Orúkọ Jésù. Àmín.

## Àwàdà

**`Ọjọ́ Ìbí Jésù**

Ìtàkúròsọ yìí wáyé láàrín tọkọtaya kán:

**Aya:** Ìgbàwo ni màá gba ẹ̀bùn kérésìmesì mi?
**Ọkọ:** Kí lo fẹ́?
**Aya:** O ṣeéṣe kí nkàn tí mo fẹ́ wọ́n, nítorínà, fún mi ní nǹkan tí ó bá ti ọkàn ẹ wá.
**Ọkọ:** Ṣáà sọ ohun tí o fẹ́
**Aya:** Tábúlẹ́ti
**Ọkọ:** Èwo nínú wọn, tí ẹ̀fórí tàbí ara ríro
**Aya:** Samsung galaxy ìwé kẹ́jọ
**Ọkọ:** Samsung galaxy kíni? Ọjọ́ ìbí Jésù ní o, kìíṣe ọjọ́ ìbi rẹ.

# ÌKẸ̀RÌNDÍNLÓGÚN

## FÍFI ÀṢẸ HÀN



## Ṣe Àṣàrò

**Jenesisi 1:26**
Léyìn náà Ọlọ́run wí pé, "Ẹ jé kí á dá eniyan ní àwòrán ara wa, kí ó rí bíi wa, kí wọ́n ní àṣẹ lórí àwọn ẹja inú òkun, ẹyẹ ojú ọ̀run, àwọn ẹranko ati lórí gbogbo ayé ati àwọn ohun tí wọn ń fàyà fà lórí ilẹ̀."

**Jenesisi 1:28**
Ó súre fún wọn, ó ní, "Ẹ máa bímọ lémọ, kí ẹ máa pọ̀ sí i, kí ẹ kún gbogbo ayé. Kí ayé wà ní ìkáwọ́ yín, kí ẹ ní àṣẹ lórí àwọn ẹja inú omi, lórí ẹyẹ ojú ọ̀run, ati lórí gbogbo ẹ̀dá alàààyè tí ń rìn káàkiri lórí ilẹ̀ ayé."

**Jenesisi 3:15**
N óo dá ọ̀tá sí ààrin ìwọ ati obinrin náà, ati sí ààrin atọmọdọmọ rẹ ati atọmọdọmọ rẹ̀. Wọn óo máa fọ́ ọ lórí, ìwọ náà óo sì máa bù wọ́n ní gìgísẹ̀ jẹ."

**Marku 16:16-18**
Ẹni tí ó bá gbàgbọ́, tí ó bá ṣe ìrìbọmi, yóo ní ìgbàlà. Ẹni tí kò bá gbàgbọ́ yóo gba ìdálẹ́bi. Àwọn àmì tí yóo máa bá àwọn tí ó gbàgbọ́ lọ nìwọ̀nyí; wọn yóo máa lé ẹ̀mí burúkú jáde ní orúkọ mi; wọn yóo máa fi àwọn èdè titun sọ̀rọ̀; wọn yóo gbé ejò lọ́wọ́, wọn yóo mu òògùn olóró, ṣugbọn kò ní ṣe wọ́n léṣe; wọn yóo gbé ọwọ́ lé àwọn aláìsàn, ara wọn yóo sì dá."

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Mojẹ́wọ́ ní orúkọ Jésù àti nípa agbára ẹ̀jẹ̀ Jésù, pé gbogbo àṣẹ ní ọ̀run àti ayé ní à ti fifún mi. Moní àṣẹ lórí gbogbo agbára ọ̀tá nínú ayé mi àti nínú ẹbí mi. Mo jẹ́wọ́ wípé a dààbobòwá, asì wa láyé nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, ìpinu ọ̀tá lórí mi kòsí ní wásí ìmúṣẹ. Ìmúdará wa yóò wá sí ìmúṣẹ ní Orúkọ Jésù.

- Olúwa ti fúnmi ní ẹnu láti bùkún, nítorínà, mo pàṣẹ ní Orúkọ Jésù péé èmi àti ẹbí mí jẹ́ alábùkún. Ajẹ́ alábùkúnfún nínú ìlú àti ní oko. A jẹ́ alábùkúnfún nínú èso ara wa. Wí wọlé wa àti ìjáde wa jẹ́ alábùkúnfún ní Orúkọ Jésù.

- Ní Orúkọ Jésù Olúwa wa, mo ba gbogbo ègún jẹ́, àti gbogbo èrò ìbì lórí mi àti àwọn ènìyàn mi. Mo pàṣẹ kòsí ahọ́n tí o dìde síwa tí yóò ṣe rere ní Orúkọ Jésù.

- Ní orúkọ Jésù, àti nípa agbára Ẹ̀mi Mímọ́, n o tẹ́ orí ejò àti àkeèké àti órí gbogbo agbara ọ̀tá, ohunkóhun kòsí níṣe mí níbi.

# ORÍ ÌKẸTÀDÍNLÓGÚN

## ÒMÌNIRA LỌ́WỌ́ ÌJOGÚN BURÚKÚ LÁTI ÌRAN DÍRAN



## Ṣe Àṣàrò

**Peteru Kinni 1:3-4**
A dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run, Baba Jesu Kristi Olúwa, tí ó fi ọ̀pọ̀ àánú rẹ̀ tún wa bí sí ìrètí tí ó wà láàyè nípa ajinde Jesu Kristi kúrò ninu òkú. Ó fún wa ni ogún ainipẹkun, ogún tí kò lè díbàjẹ́, tí kò lè ṣá, tí a ti fi pamọ́ fun yín ní ọ̀run.

**Orin Dafidi 16:5-6**
OLÚWA, ìwọ ni ìpín mi, ìwọ ni mo yàn; ìwọ ni ò ń jẹ́ kí ọ̀kàn mi fìdí múlẹ̀. Ìpín tí ó bọ́ sí mi lọ́wọ́ dára pupọ; ogún rere ni ogún ti mo jẹ.

**Efesu 1:11**
Nípasẹ̀ Kristi kan náà ni Ọlọ́run ti pín wa ní ogún. Ètò tí ó ti ṣe fún wa nìyí, òun tí ó ń mú ohun gbogbo ṣẹ gẹ́gẹ́ bí ìfẹ́ ọkàn rẹ̀.

**Galatia 3:29**
Tí ẹ bá jẹ́ ti Kristi, a jẹ́ pé ẹ jẹ́ irú-ọmọ Abrahamu, ẹ sì di ajogún ìlérí.

**Korinti Keji 5:17**
Èyí ni pé nígbà tí ẹnikẹ́ni bá wà ninu Kristi, ó di ẹ̀dá titun. Ohun àtijọ́ ti kọjá lọ. Ìgbé-ayé irú ẹni bẹ́ẹ̀ sì di titun.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Ẹ̀ṣẹ Jésù tí ó wá túwa sílẹ̀ lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ àná. Mo kọ̀ láti gbé nínú ìgbèkùn, mo sì gbàdúrà wípé àwọn ọmọ mi kòní jogún ìgbekùnkígbèkùn láti mọ̀lẹ́bí wọn, ṣùgbọ́n wọ́n ó jogún ìjọba tí a ti pèsè sílẹ̀ fún wọn.

- Nínú rẹ Olúwa, ohun àtijọ́ tiré kọjálọ, ati sọ ohun gbogbo dí ọ̀tun, nkò síní ṣàṣàrò lórí ohun àtijọ́ mọ́. Èmi àti àwọn ìran mí tí ón bọ̀wá ti ní ìtúsílẹ̀ kúrò nínú ẹ̀gún ọ̀fin, mosì ti bọ́ nínú ìgbèkùn.

- Mo gbàdúrà pé gbogbo àjogúnbá ìgbèkùn ní a tí bàjẹ́, gbàmí nínú wọn Olúwa. Mo jẹ́ alábápín ọ̀rọ̀ rẹ̀ tí ó nípé ọkùnrin rere fi ogún sílẹ̀ fún àwọn ọmọ ọmọ rẹ̀.

- Mo gbàdúrà wípé wọn á jogún èrè iṣẹ́ rere àti ọkàn mímọ́ láti ọ̀dọ̀ rẹ́ Olúwa.

# ORÍ ÌKEJÌDÍNLÓGÚN

## ÀÌGBA Ẹ̀RÙ NÍ ÀAYE



## Ṣe Àṣàrò

**Aisaya 41:10**
Má bèrù, nítorí mo wà pẹlu rẹ, má fòyà, nítorí èmi ni Ọlọ́run rẹ. N óo fún ọ ní agbára, n óo sì ràn ọ́ lọ́wọ́; ọwọ́ ọ̀tún mi, ọwọ́ ìṣégun, ni n óo fi gbé ọ ró.

**Timoti Keji 1:7**
Nítorí kì í ṣe ẹ̀mí ojo ni Ọlọ́run fún wa bíkòse ẹ̀mí agbára ati ti ìfẹ́ ati ti ìkóra-ẹni-níjàánu.

**Orin Dafidi 91:5**
O ò ní bẹ̀rù ìdágìrì òru, tabi ọfà tí ń fò kiri ní òsán

**Orin Dafidi 23:4**
Àní, bí mo tilẹ̀ ń rìn ninu òkùnkùn létí bèbè ikú, n kò ní bẹ̀rù ibi kankan; nítorí tí o wà pẹlu mi; ògọ rẹ ati òpá rẹ ń fi mí lókàn balẹ̀.

**Johanu Kinni 4:18**
Kò sí ẹ̀rù ninu ìfẹ́; ìfẹ́ pípé a máa lé ẹ̀rù jáde, nítorí ìjayà ni ó ń mú ẹ̀rù wá. Ẹni tí ó bá ń bẹ̀rù kò ì tíì di pípé ninu ìfẹ́.

**Orin Dafidi 27:1**
OLÚWA ni ìmọ́lẹ̀ ati ìgbàlà mi; ta ni n óo bẹ̀rù? OLÚWA ni ààbò ẹ̀mí mi, ẹ̀rù ta ni yóo bà mí?

**Orin Dafidi 34:4**
Mo ké pe OLÚWA, ó sì dá mi lóhùn, ó sì gbà mí lọ́wọ́ gbogbo ohun tí ń bà mí lẹ́rù.

**Romu 8:6**
Lílépa àwọn nnkan ti ẹran-ara nìkan a máa yọrí sí ikú, sugbọn lílépa àwọn nnkan ti Ẹ̀mí a máa fúnni ní ìyè ati alaafia.

**Aisaya 35:4**
Ẹ sọ fún àwọn tí àyà wọn ń já pé: "Ẹ ṣe ara gírí, ẹ má bèrù. Ẹ wò ó! Ọlọ́run yín óo wá pẹlu èsan, ó ń bọ̀ wá gbẹ̀san gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́run; ó ń bọ̀ wá gbà yín là."

**Josua 1:9**
Ranti pé mo ti pàṣẹ fún ọ pé kí o múra, kí o sì ṣe ọkàn gírí. Má bẹ̀rù, má sì jẹ́ kí ìrẹ̀wẹ̀sì bá ọkàn rẹ, nítorí pé èmi, OLÚWA Ọlọ́run rẹ wà pẹlu rẹ níbikíbi tí o bá ń lọ."

**Johanu 14:27**
"Alaafia ni mo fi sílẹ̀ fun yín. Alaafia mi ni mo fun yín. Kì í ṣe bí ayé ti í fúnni ni mo fun yín. Ẹ má jẹ́ kí ọkàn yín dàrú, ẹ má sì jẹ́ kí ẹ̀rù bà yín.

# Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Èmi kòní bẹ̀rù ọfà tí ó ń fò lọ́san

- Èmi kòní bẹ̀rù tàbí fòya torí Ọlọ́run mí wà pẹ̀lú mí láti ró mi lágbára.

- Ràǹmílọ́wọ́, kí o sì dì mí mú pẹ̀lú ọwọ́ ọ̀tún òdodo rẹ, tí mobá tilẹ̀ rìn ní ibojì ikú.

- Ìfẹ́ rẹ̀ símì borí gbogbo ìbẹ̀rù ṣugbọ́n nigbàkugbà tí n kò bále borí ìbẹ̀rù mi. Olúwa, fún mi ní ọgbọ́n, pamímọ, kí o sì fà mí mọ́ra. Ràǹmílọ́wọ́ láti le gba pé mò ń bẹ̀rù, kín sìle múwá síwájú rẹ nínú àdúrà.

- A dúpẹ́ fún ìlérí yín láti gbàwá sílẹ̀ nínú ìbẹ̀rù, mo sì gbàdúrà fún ìdándè kúrò nínú ìbẹ̀rù. Mo rí ọ ní òní, mo sì nígbàgbọ́ pé ó gbọ́ mi, mo sì gbàdúrà pé kí o ro mi lágbára, kí o sì gbàmí kúrò nínú ìbẹ̀rù tó halẹ̀ láti borí ẹ̀mí mi. Wẹ mí mọ kúrò nínú ìbẹ̀rù, àníyàn, àti iyèméjì.

- Mo gbàdúrà wípé ọ̀rọ̀ rẹ yóò múlẹ̀ nínú ọkàn mí, mú awọn ohun tí ó mọ, ohun rere, àti ohun ìyìn rọ́pọ̀ ẹ̀mí ìbẹ̀rù àbí iṣẹ́ ibi ọ̀tá nínú ọkàn mí.

- Adúpẹ́ Olúwa fún ìlérí àbò rẹ lórí wa. Mo ní gbàgbọ́ nínú rẹ, n kò sìní bẹ̀rù ohun tí eniyan lèṣe fún mi. Moti borí ẹ̀mí ìbẹ̀rù. Ranmílọ́wọ́ láti le sínmí nínú ìfẹ́ rẹ, níbi tí agbára ibi kòle kànmí ní orúkọ Jésù. Àmín.

- Mo wà ní abẹ́ ibi àbò Olúwa, mo sì wà lábẹ́ òjìji Olódùmarè. Olúwa ní àpáta àti ibi ìsádi mi, nítorí náà, a kò ní ṣími nídì. Nítorí Olúwa Ọlọ́run jẹ́ ibi ìsádi mi, n kò ní bẹ̀rù ohunkóhun. Ọkàn mi dúró ṣinṣin nínú ìgbẹkẹle mi sí Olúwa, nítorínà, n kòni bẹ̀rù ohunkóhun torí ìgbàgbọ́ mi dúró lori ọ̀rọ̀ rẹ.

- Mo sọ wípé èmi kòni bẹ̀rù nítorí Olúwa wà pẹ̀lú mí níbi gbogbo. Nítorínà, mo sinmi nínú àlàáfià Olúwa tó ju ọgbọ́n ènìyàn lọ ní orúkọ Jésù.

## Àwàdà

**Ìwé Ìdánwọ̀**
Ní ìdánwò àṣekágbá tí WÀẸ́Ẹ̀KÌ, olùkọ gba Kofi mu níbi tí o tiń narùn wo iṣẹ́ Kwame.
Ìtàkurọsọ yíí sí tẹ̀lee:

**Olùkọ:** Kílódé ti ò ńwo ìwé Kwame?

**Kofi:** Mo n bá wò bóyá ó dáhùn àwọn ìbéèrè ná dáradára ni.

ORÍ ÌKỌKÁNDÍNLÓGÚN

# ÀWỌN ORÍLẸ ÈDÈ



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 33:12**
Ayọ̀ ń bẹ fún orílẹ̀-èdè tí OLÚWA jẹ́ Ọlọ́run wọn, àní àwọn eniyan tí ó yàn gẹ́gẹ́ bí ìní rè!

**Òwe 14:34**
Òdodo ní ń gbé orílẹ̀-èdè lékè, ṣugbọn ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ ẹ̀gàn fún orílẹ̀-èdè.

**Jeremaya 1:10**
Mo ti fi ọ́ ṣe orí fún àwọn orílẹ̀-èdè ati ìjọba lónìí, láti fà wọ́n tu ati láti bì wọ́n lulẹ̀, láti pa wọ́n run ati láti bì wọ́n ṣubú, láti tún wọn kọ́ ati láti gbé wọn ró."

**Orin Dafidi 22:27-28**
Gbogbo ayé ni yóo ranti OLÚWA wọn yóo sì pada sọ́dọ̀ rẹ̀; gbogbo ẹ̀yà àwọn orílẹ̀-èdè ni yóo sì júbà níwájú rè. Nítorí OLÚWA ló ni ìjọba, òun ní ń jọba lórí gbogbo orílẹ̀-èdè.

**Aisaya 2:4**
Yóo ṣe ìdájọ́ láàrin àwọn orílẹ̀-èdè; yóo sì bá ọpọlọpọ eniyan wí. Wọn yóo fi idà wọn rọ ọkọ́, wọn yóo sì fi ọ̀kọ̀ wọn rọ dòjé. Àwọn orílẹ̀-èdè kò ní yọ idà sí ara wọn mọ́, wọn kò sì ní kọ́ ogun jíjà mọ́.

**Aisaya 60:18,21-22**
Kò tún ní sí ìró ìdàrúdàpọ̀ ní ilẹ̀ rẹ mọ́, kò sì ní sí ìdágìrì ati ìparun ní ibodè rẹ, o óo máa pe odi rẹ ní ìgbàlà, o óo sì máa pe ẹnubodè rẹ ní ìyìn. Gbogbo àwọn eniyan rẹ yóo jẹ́ olódodo, àwọn ni yóo jogún ilẹ̀ náà títí lae. Àwọn ni ẹ̀ka igi tí mo gbìn, iṣẹ́ ọwọ́ mi, kí á baà lè yìn mí lógo. Ìdílé tí ó rẹ̀yìn jùlọ yóo di orílẹ̀-èdè, èyí tí ó sì kéré jùlọ yóo di orílẹ̀-èdè ńlá, Èmi ni OLÚWA, kíákíá ni n óo ṣe é nígbà tí àkókò rè bá tó."

**Kronika Keji 7:14-15**
Bí àwọn eniyan mi, tí à ń fi orúkọ mi pè, bá rẹ ara wọn sílẹ̀, tí wọ́n bá gbadura, tí wọ́n sì wá ojurere mi, tí wọ́n bá yipada kúrò ní ọ̀nà burúkú wọnyi; n óo gbọ́ láti ọ̀run, n óo dárí ẹ̀ṣẹ̀ wọn jì wọ́n, n óo sì wo ilè wọn sàn. Nisinsinyii, n óo fojú sílẹ̀, etí mi yóo sì ṣí sí adura tí wọ́n bá gbà níbí yìí.

**Aisaya 62:4**
A kò ní pè ọ́ ní "Ẹni-tí-a-kọ̀-sílẹ̀" mọ́, bẹ́ẹ̀ ni a kò ní pe ilè rẹ ní "Ahoro" mọ́, "Ẹni- OLÚWA -fẹ́" ni a óo máa pè ọ́, a óo máa pe ilẹ̀ rẹ ní "Ẹni-a-gbé-níyàwó." Nítorí pé OLÚWA nífẹ̀ẹ́ rẹ, ilẹ̀ rẹ yóo sì dàbí iyawo lójú rè.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Bàbá mi àti Ọlọ́run mi, ṣàánú fún àwa èǹìyàn rẹ́, nî ìtara fún àwa èǹìyàn ré, kí a máṣe jẹ́ ẹni yẹ̀yẹ́ àti alábùkú láàrîn àwọn èǹìyàn.

- Èmi àti àwọn ọmọ orîlẹ̀ èdè mî rẹ ara wa sîlẹ̀ nîwájù re, agbàdúrà, asì wa ojú rẹ́ bi a ṣe yî padà kúrò nînú ìwà búburú wa, a bẹ̀bẹ̀ kî o gbọ́ wa láti ọ̀run, kî o dáwa lóhùn, kî o sì wo ilẹ̀ wa sàn, Olúwa.

- Mo gbàdúrà wîpé ìwà ipá yóò dáwọ́dúró nî orîlẹ̀dè wá, gbogbo ìbàjẹ́ nî a ó sì mú kúrò. Orîlẹ̀ ẹ̀dè mî yóò nî orúkọ tuntun, a o sì jẹ olódodo sî ògo rẹ́.

- Orîlẹ̀ ẹ̀dè mî yóò dàgbà, a ó sì ro lágbára gẹ́gẹ́ bî isẹ́ ọwọ́ rẹ̀ lórúkọ Jésù. Máse mu àlâfiaa rẹ́ kúrò tîtî tî ìlérî rẹ sî orîlẹ èdè wa yóò fi wásî ìmúṣẹ.

- Tú èmi àti orîlẹ èdè mî nînú Olúwa, mú ìpadà bọ̀sîpọ̀ wá fún ohun gbogbo tî a ti bàjẹ́, mú ayọ̀, ìdùnnú àti ọpẹ́ wá sî ilé wa.

- A kò nîpé orîlè ẹ̀dè wa nî aṣálẹ̀ mọ, a ó máá jẹ́ ìdùnú rẹ̀ láti ìgbàyî lọ nî Orúkọ Jésù, Àmîn.

### Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n

Ọlọ́run kò sọ wîpé ìrìn àjò náà yóò rọrùn, ṣùgbọ́n ìgbẹ̀yìn rẹ yóò dára.

# ORÍ OGÚN

ÀBÒ ÀTI ÌTÚSÍLẸ̀
ỌLỌ́RUN



## Ṣe Àṣàrò

**Diutaronomi 33:27**
Ọlọ́run ayérayé ni ààbò yín, ọwọ́ rè ni ó sì fi ń gbé yín ró. Bí ẹ ti ń súnmọ́ wájú, béè ni ó ń lé àwọn ọ̀tá yín jáde, tí ó sì ní kí ẹ máa pa wọ́n run.

**Jeremaya 1:18-19**
Wò ó, mo ti sọ ó di ìlú tí a mọ odi yíká lónìí, o di òpó irin ati ògiri tí a fi bàbà mọ fún gbogbo ilè yìí, ati fún àwọn ọba ilè Juda, àwọn ìjòyè, ati àwọn alufaa rè, ati àwọn eniyan ilè náà. Wọn yóo gbógun tì ó, ṣugbọn wọn kò ní ṣẹgun rẹ. Nítorí pé mo wà pẹlu rẹ láti gbà ó kalè. Èmi OLÚWA ni mo sọ béè."

**Orin Dafidi 18:13-14**
OLÚWA sán ààrá láti ọ̀run, Ògá Ògo fọhùn, òjò dídì ati èyinná sì fón jáde. Ó ta ọfà rè jáde, ó sì fón wọn ká, ó jé kí mànàmáná kọ, ó sì tú wọn ká.

**Orin Dafidi 18:35-36**
O ti fún mi ní asà ìgbàlà rẹ, ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni ó gbé mi ró, ìrànlọ́wọ́ rẹ sì ni ó sọ mí di ẹni ńlá. O la ọ̀nà tí ó gbòòrò fún mi, n kò sì fi ẹsè ró.

**Aisaya 26:3**
O óo pa àwọn tí wọ́n gbé ọkàn wọn lé ọ mọ́ ní alaafia pípé, nítorí pé wọ́n gbékèlé ọ.

**Orin Dafidi 24:7-10**
Ẹ ṣí sílè gbayau, èyin ìlèkùn, ẹ wà ní ṣíṣí sílè, èyin ìlèkùn ayérayé, kí Ọba ògo lè wọlé. Ta ni Ọba ògo yìí? OLÚWA tí ó ní ipá tí ó sì lágbára, OLÚWA tí ó lágbára lógun. Ẹ ṣí sílè gbayau, èyin ìlèkùn, ẹ wà ní ṣíṣí sílè, èyin ìlèkùn ayérayé, kí Ọba ògo lè wọlé. Ta ni Ọba ògo yìí? OLÚWA àwọn ọmọ ogun, òun ni Ọba ògo náà.

**Numeri 23:23**
Kò sí òògùn kan tí ó lè ran Jákọ́bù, béè ni àfòṣẹ kan kò lè ran Israẹli. Wò ó! Àwọn eniyan yóo máa wí nípa Israẹli pé, 'Wo ohun tí Ọlọ́run ṣe!'

**Luku 4:10**
Nítorí ó wà ní àkọsílè pé, 'Yóo pàṣẹ fún àwọn angẹli rè nítorí rẹ pé kí wọn pa ó mọ́.'

**Orin Dafidi 30:5**
Nítorí pé fún ìgbà díè ni ibinu rè, ṣugbọn títí ayé ni ojurere rè; eniyan lè máa sọkún títí di alé, ṣugbọn ayò ń bò fún un lówùúrò.

**Orin Dafidi 34:7**
Angẹli OLÚWA yí àwọn tí ó bèrù rè ká, a sì máa gbà wọ́n.

**Aisaya 43:1-4**
Ṣugbọn nisinsinyii, Jakọbu, gbó nnkan tí OLÚWA ẹlẹ́dàá rẹ wí, Israẹli, gbó ohun tí ẹni tí ó dá ọ

sọ. Ó ní, "Má bẹ̀rù, nítorí mo ti rà ó padà; mo ti pè ó ní orúkọ rẹ, èmi ni mo ni ó. Nígbà tí o bá ń la ibú omi kọjá, n óo wà pẹlu rẹ; nígbà tí o bá la odò ńlá kọjá, kò ní bò ó mọ́lẹ̀, nígbà tí o bá ń kọjá ninu iná, kò ní jó ọ. Ahọ́n iná kò ní jó ọ run. Nítorí èmi ni OLÚWA Ọlọ́run rẹ, Ẹni Mímọ́ Israẹli, Olùgbàlà rẹ. Mo fi Ijipti, lélẹ̀, láti rà ó padà, mo sì fi Etiopia ati Ṣeba lélẹ̀ mo ti fi ṣe pàṣípààrọ̀ rẹ. Nítorí pé o ṣọ̀wọ́n lójú mi, o níyì, mo sì fẹ́ràn rẹ, mo fi àwọn eniyan rọ́pò rẹ; mo sì fi ẹ̀mí àwọn orílẹ̀-èdè dípò ẹ̀mí rẹ.

**Aisaya 10:27**
Ní ọjọ́ náà, a óo gbé ẹrù tí ó dì lé ọ lórí kúrò, a óo sì fa àjàgà rẹ̀ dá kúrò lọ́rùn rẹ."

**Johanu Kinni) 4:4**
Ẹ̀yin ọmọde, ti Ọlọ́run nìyí, ẹ ti ṣẹgun ẹ̀mí alátakò Kristi nítorí pé ẹni tí ó wà ninu yín tóbi ju ẹni tí ó wà ninu ayé lọ.

**Ifihan 12:11**
Wọ́n ti fi ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́ Aguntan ati ẹ̀rí ọ̀rọ̀ tí wọ́n jẹ́ ṣẹgun rẹ̀. Nítorí wọn kò ka ẹ̀mí wọn sí pé ó ṣe iyebíye jù kí wọ́n kú lọ.

**Aisaya 44:25**
Èmi tí mo sọ àmì àwọn tí ń woṣẹ́ èké di asán, tí mo sì sọ àwọn aláfọ̀ṣẹ di òmùgọ̀. Mo yí ọgbọ́n àwọn ọlọ́gbọ́n po mo sì sọ ọgbọ́n wọn di òmùgọ̀.

**Aisaya 45:1**
Ohun tí OLÚWA sọ fún kirusi, ẹni tí ó fi àmì òróró yàn nìyí: Ẹni tí OLÚWA di ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ mú, tí ó lò, láti rẹ àwọn orílẹ̀-èdè sílẹ̀ níwájú rẹ̀, láti tú àmùrè àwọn ọba, láti ṣí àwọn ìlẹ̀kùn níwájú rẹ̀, kí ẹnubodè má lè tì.

**Aisaya 45:2**
OLÚWA ní, "N óo lọ ṣáájú rẹ, n óo sọ àwọn òkè ńlá di pẹ̀tẹ́lẹ̀; n óo fọ́ ìlẹ̀kùn idẹ, n óo sì gé ọ̀pá ìlẹ̀kùn irin.

**Orin Dafidi 144:5-8**
OLÚWA, fa ojú ọ̀run wá sílẹ̀, kí o sì sọ̀kalẹ̀ wá, fọwọ́ kan àwọn òkè ńlá, kí wọ́n máa rú èéfín. Jẹ́ kí mànàmáná kọ, kí o sì tú wọn ká, ta ọfà rẹ, kí o tú wọn ká. Na ọwọ́ rẹ sílẹ̀ láti òkè, kí o yọ mí ninu ibú omi; kí o sì gbà mí lọ́wọ́ àwọn àjèjì, tí ẹnu wọn kún fún iró, tí ọwọ́ ọ̀tún wọn sì kún fún èké.

**Joobu 5:12-13**
A máa da ète àwọn alárèékérekè rú, kí wọn má baà lè yọrí ètekéte wọn. Ó mú àwọn ọlọ́gbọ́n ninu àrékérekè wọn; ó sì mú ète àwọn ẹlẹ́tàn wá sópin.

**Efesu 6:12**
Nítorí kì í ṣe eniyan ni à ń bá

jagun, bíkòṣe àwọn ẹ̀mí burúkú ojú ọ̀run, àwọn aláṣẹ ati àwọn alágbára òkùnkùn ayé yìí.

**Maku 16:17**
Àwọn àmì tí yóo máa bá àwọn tí ó gbàgbó ̣lọ nìwọ̀ṇyí; wọn yóo máa lé ẹ̀mí burúkú jáde ní orúkọ mi; wọn yóo máa fi àwọn èdè titun sọ̀ṛọ̀;̣

**Matiu 15:13**
Jesu dá wọn lóhùn pé, "Gbogbo igi tí Baba mi tí ń bẹ lọ́ṛun kò bá gbìn ni a óo hú dànù.

**Korinti Keji 10:4**
Nítorí àwọn ohun-ìjà wa kì í ṣe ti ayé, agbára Ọlọ́run ni, tí a lè fi wó ìlú olódi. À ń bi gbogbo iyàn jíjà lórí èké ṣubú

**Luku 10:19**
Mo fun yín ní àṣẹ láti tẹ ejò ati àkeekèé mọ́lẹ̀.̣ Mo tún fun yín ní àṣẹ lórí gbogbo agbára ọ̀ṭá. Kò sí ohunkohun tí yóo pa yín lára.

**Orin Dafidi 50:15**
Ẹ ké pè mí ní ọjọ́ ̣ìṣòro; n óo gbà yín, ẹ óo sì yìn mí lógo."

**Aisaya 49:24-26**
Njé ̣a lè gba ìkógun lọ́ẉó ̣alágbára, tabi kí á gba òǹdè lọ́ẉó ̣òkúrorò eniyan? OLÚWA ní: "Bí ó bá tilè ̣ṣeéṣe láti gba òǹdè lọ́ẉó ̣alágbára, tabi láti gba ìkógun lọ́ẉó ̣òkúrorò eniyan. N óo bá àwọn tí ó ń bá ọ jà jà, n óo sì gba àwọn ọmọ rẹ là. N óo mú kí àwọn tó ń ni ó ̣lára máa pa ara wọn jẹ: wọn óo máa mu ẹ̀jẹ̀ ̣ara wọn, bí ẹni mu ọtí, gbogbo ayé yóo sì mò ̣nígbà náà pé, èmi ni OLÚWA, Olùgbàlà rẹ, Olùràpadà rẹ, Ọlọ́run alágbára Jakọbu."

**Johanu 14:1-4**
"Ẹ má ṣe jé ̣kí ọkàn yín dàrú. Ẹ gba Ọlọ́run gbó,̣ kí ẹ sì gba èmi náà gbó.̣ Yàrá pupọ ni ó wà ninu ilé Baba mi. Bí kò bá ṣe béẹ̀,̣ ǹjé ̣n óo sọ fun yín pé mò ń lọ pèsè àyè sílè ̣dè yín? Bí mo bá lọ pèsè àyè sílè ̣dè yín, n óo tún pada wá láti mu yín lọ sọ́ḍọ̀ ̣ara mi, kí ẹ lè wà níbi tí èmi pàápàá bá wà. Ẹ kúkú ti mọ ọ̀ṇà ibi tí mò ń lọ."

**Aisaya 54:14-15**
A óo fìdí rẹ múlè,̣ ninu òdodo, o óo jìnnà sí ìnira, nítorí náà ẹ̀ṛù kò ní bà ó.̣ O óo jìnnà sí ìpayà, nítorí kò ní súnmó ̣ọ. Bí ẹnìkan bá dojú ìjà kọ ó,̣ kìí ṣe èmi ni mo rán an, ẹnikéṇi tó bá gbéjà kò ó,̣ yóo ṣubú nítorí rẹ."

**Aisaya 54:17**
Kò sí ohun ìjà tí a ṣe láti fi bá ọ jà tí yóo lágbára lórí rẹ. Gbogbo ẹni tí ó bá bá ọ rojọ́ nílé ẹjọ́, ni o óo jàre wọn. Èyí ni ìpín àwọn iranṣẹ OLÚWA, ati ìdáláre wọn lọ́dọ̀ mi. Èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀.”

**Orin Dafidi 91:4**
Yóo da ìyẹ́ rẹ̀ bò ọ́, lábẹ́ ìyẹ́ apá rẹ̀ ni o óo ti rí ààbò; òtítọ́ rẹ̀ ni yóo jẹ́ asà ati apata rẹ.

**Orin Dafidi 91:11**
Nítorí yóo pàṣẹ fún àwọn angẹli rẹ̀, nítorí rẹ, pé kí wọ́n máa pa ọ́ mọ́ ní gbogbo ọ̀nà rẹ.

**Jeremaya 1:9**
OLÚWA bá na ọwọ́, ó fi kàn mí lẹ́nu, ó sì wí fún mi pé, “Wò ó, mo ti fi ọ̀rọ̀ mi sí ọ lẹ́nu.

**Iwe Òwe 18:10**
Orúkọ OLÚWA jẹ́ ilé-ìṣọ́ tí ó lágbára, olódodo sá wọ inú rẹ̀, ó sì yè.

**Luku 1:37**
Nítorí kò sí ohun tí ó ṣòro fún Ọlọ́run.”

**Aisaya 41:10**
Má bẹ̀rù, nítorí mo wà pẹlu rẹ, má fòyà, nítorí èmi ni Ọlọ́run rẹ. N óo fún ọ ní agbára, n óo sì ràn ọ́ lọ́wọ́; ọwọ́ ọ̀tún mi, ọwọ́ ìṣẹ́gun, ni n óo fi gbé ọ ró.

**Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n**

Gba ọ̀rọ̀ náa gbọ, kàá lójoojúmọ́, kí ó sì jẹ́ kí o múlẹ̀ lọ́kàn rẹ pẹ̀lú ìgbàgbọ́.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ

- Romí lágbára kí o si mọ odi yímiká lòdì sí àwọn ọ̀tá mi àti ìránṣẹ́ òkùnkùn tí óún pèrò láti pamí run Olúwa. Àwọn tí ó ń bámijà kòní borí mí nítorí ní gbogbo ìgbà ní ìwọ yóò má gba àwọn èǹìyàn rẹ̀. Mo dúpẹ́ Olúwa tí ó sọ ìpèsè mí dí ńlá, tí o sì fúnmi ní ìgbàlà rẹ, ọwọ ọtún rẹ tí dì mí mú, ó sì ti gbémiga.

- Mo pálásẹ pé gbogbo ìlẹ̀kùn tí a ti mọ́ mi bẹ̀rẹ̀ síní ṣí. Ògo olúwa bẹ̀rẹ̀ síní wọlé láti ìsisín yin lọ.

- Ọfọ̀, àsọtẹ́lẹ̀ ibi àti àfọ̀ṣẹ ibi nítorí mí kí yóò ṣe rere, nítori bàbá mi yóò fún àwọn Ángẹ́lì rẹ ní àṣẹ láti máa ṣọ́ mi.

- Gbogbo àjàgà àbí ìṣòro tí o ba kọjú mi ní a o mú kúrò tí a ó sì parun pátápátá, torí ìwàláayè rẹ nínú ayé mi, Olúwa.

- Torí mo jẹ́ olúborí, ẹni tí o wà nínú mí jù ẹni tí ó wà nínú ayé lo, fún ìdí èyí, n kòní kùnà ní àdáwọ́lé mi.

- Olúwa, mú gbogbo ibi wíwọ́ inú aye mí di títò, kí o sì gbà mí, ẹbí mi, òwò mi, iṣẹ́ mi, àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ mí sílẹ̀ lọ́wọ́ ibi.

- Gbà mí sílẹ̀ lọ́wọ́ ìmọ̀ràn òpúrọ́ àti ayanijẹ, pín ọgbọ́n àwọn ẹni ibi lémi, mú ìmọ àwọn tí o fẹ́ dàmílójurú wá sí àimúṣẹ.

- Ní orúkọ Jésù, mo ṣe ìlòdì sí gbogbo ìjọba, agbára, àti aláṣẹ òkùnkùn ayé yi, pẹ̀lú gbogbo ìkà. Kòsí ohunkóhun tí yio ṣe mí níbi.

- Láti ìsín sin yí lọ, gbogbo ohun tí baba mí kò gbìn sínú àyànmọ́ mi di fífàtu. Mo wó gbogbo òdì t'ọ́ta kọ́ nítorí mi, mosì tẹ gbogbo ibi wọ́n mọ́lẹ̀. Olúwa yó gba mí fún ògo rẹ.

- Ọlọ́run mi yóò kọjú ìjà sí gbogbo agbára ọ̀ta tí́n bá mi àti àwọn ẹbí mí jà nítorí ohun ní olùràpadà mí, olùgbàlà mi, àpáta mi, ọkọ̀ mí, okun mi àti agbára mí. Mo dá gbogbo ahọ́n tí ó bá dide sí mi lẹ́jọ́.

- Nínú òdodo, ni a o fì idí mí múlẹ̀, a ó mumí jìnà sí ìrẹ́jẹ torí èmi kòni bẹ̀rù. Ibi kòní súnmọ́ mi. Ní kíkójọ, wọ́n yo kó ara wọn jọ, ṣùgbọ́n kìí ṣe nítorí tí Ọlọ́run mí, gbogbo ibi tí ó kó ara jọ torí mí la ò túka. Àbò mí wà nínú Ọlọ́run nìkan, mosá tọ Olúwa, mo sì rí ìgbàlà. Olúwa yóò pàṣẹ fún àwọn ángẹ́lì rẹ láti dáàbò bòmí àti ẹbí mí ní gbogbo ọ̀nà mi, a ó sì borí gbogbo ipá òkùnkùn.

- Olúwa yóò gbàmí lọ́wọ́ gbogbo agbára torí kò ní jẹ́ kí wọ́n borí mi. Yóò bá ìpinu wọ́n jẹ́, èrò wọ́n kò síní wásí mímúṣẹ. Olúwa yóò gbàmí lọ́wọ́ ìkẹkùn àwọn pẹyẹpẹyẹ àjàkálẹ̀ àarùn. Yóò fi ìyẹ́ rẹ̀ bòmí, àpá ìyẹ́ rẹ sí ní ibi ìsádi mi.

- Mowà ní abẹ́ òjìjí Olódùmarè, ibi ìsádi mi. Mo jẹ́wọ́ wipe mo ti gba odi ìgbàlà, ọwọ́ ọ̀tún rẹ sì pamímọ́ kúrò nínú ìrìnsẹ̀ àwọn ọ̀tá. Bí wọ́n tilẹ̀ bámi jà, wọn kòní borí, torí Olúwa wà pẹ̀lú mi láti gbàmí sílẹ̀.

- Olúwa tí pèsè àwọn ángẹ́lì rẹ láti pamímọ́ ní ọ̀nà mi gbogbo, fún ìdí èyí, moní ìfọ̀kànbalẹ̀ torí ẹni tí́n pamímọ́ kìí sùn, bẹ́ẹ̀ni kìí tóógbé.

- Mo jẹ́ iyebíye níwájú bàbá mi, mo ní ìgboyà pé kò sí àsàsí tàbí èdì tí a ṣe sí mi tí yóò ṣe rere. Ẹni mímọ́ Ísráẹ́lì ni olùgbàlà mi, ìfẹ́ rẹ símí mú kí ó fi ẹ̀mí èníyàn pàarọ̀ ẹ̀mí mi.

## Àdúrà/Ìtúsílẹ̀

Ní Orúkọ Jésu, orúkọ tí ó ń já ìdè tí ó sì ńtú sílẹ̀, mo gba àṣẹ lórí gbogbo ìsẹ̀lẹ̀ ibi nínú ayé mi, ayé ọkọ/aya mi, aye àwọn ọmọ mi, ọkọ mi, iṣẹ́ mí àti ohun gbogbo tí o jẹ tèmi.

Bẹ̀rẹ̀síní wó palẹ̀, nípa lílo àwon ọ̀rọ̀ ìjà ogun wọ̀nyí:

Àpẹẹrẹ: mo ba gbogbo iṣẹ́ èṣù àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ tí wọ́n tilè gbìn sínú ayé mi jẹ́, mo bọ́ lọ́wọ́ agbára rẹ̀ lórí ayé mi lórúkọ Jésù. Àmín.

·Paarẹ́
·Túsílẹ̀
·Fọ́
·Túká
·Fagilé
·Dè
·Dà wó

## Àwàdà

### Ìwé Ìwọ̀le

´Onímọ̀ ẹ̀rọ mẹ́ta àti onísìrò owó mẹ́ta ń rìn ìrìn àjò nínú ọkọ̀ ojú irin lọsí ìpàdé kan. Ní ibùdókọ̀, àwọn onísìrò owó ra ìwé ìwọlé kan kan, wọ́n sì rí nígbàtí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ra ìwé ìwọlẹ́ kan péré. Báwo ni ẹ̀yin mẹ́ta ṣe máá rìn ìrìn àjò lórí ìwé ìwọlé kan, onísìrò owo kan bèrè?. Wo wá, oo sì rí idán ni èsì tí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ fún wọn.

Gbogbo wọn wọ́ ọkọ̀ ojú irin. Àwọn onísìrò owó joko sí orí àga wọn, nígbàtí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ mẹ́tẹ̀ẹta wọ nú ilé ìgbọ̀nsẹ̀ kan lọ, wọ́n sì ti ilẹ̀kùn mọ́ ara wọn.

Kòpẹ́ tí ọkọ̀ gbéra, ní pèròsọ́kọ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní gba ìwé ìwọlé wọn. Ó kan ilẹ̀kùn ilé ìgbọ̀nsẹ̀, ó sì ní ẹjọ̀wọ́, ìwé ìwọlé yín dà? Ilẹ̀kùn ṣí díẹ̀, apá kan yọ jáde pẹ̀lú ìwé ìwọlé. Pèròsọ́kọ̀ náà gbà, ó sì bá tirẹ̀ lọ. Àwọn onísìrò owó rí èyí, wọn sì gba pé ọlọ́gbọ́n ni àwọn onímò ẹ̀rọ̀ wọ̀nyí.

Lẹ́yìn ìpàdé náà, àwọ́n onísìrò owó pinu láti ṣe bí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ, wọn sì rà ìwé ìwọlé kan ṣoṣo. Ṣùgbọ́n àwọ́n onímọ̀ ẹ̀rọ kò ra ìwé ìwọlé kankan. Ọ̀kan nínú àwọn onísìrò bèèrè pé, "báwo ni ẹ  ṣe máa rìn ìrìn àjò láì ra ìwé ìwọlé kankan? Ọ̀kan nínú àwọn onímọ̀ ẹ̀ro wí fún wọn pé "ẹ má wòran"

Nígbàtí wọ́n wọ inú ọkọ̀, wọ́n wọ ilé ìgbọ̀nsẹ̀ lọ, àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ ná sì wọnú ilé ìgbọ̀nsẹ̀ kan tí ó súnmọ́ wọn. Ọkọ̀ ṣí. Láìpẹ́ jọjọ, ọ̀kan nínú àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ kúrò ní ilé ìgbọ̀nsẹ̀ tíwọ́n, ó lọ sí ẹnu ọ̀nà ilé ìgbọ̀nsẹ̀ tí àwọn onísìrò owó wa, ó kan ìlẹ̀kùn, ó sì nípé, ẹ jọ̀wọ́, ìwé ìwọlé yín dà.́

# ORÍ ÌKỌKÀNLÉLÓGÚN

ÌPÈSE



## Ṣe Àṣàrò

**Matiu 7:11**
Njẹ́ bí ẹ̀yin tí ẹ burú báyìí bá mò bí a tií fi ohun tí ó dára fún ọmọ yín, mélòó-mélòó ni Baba yín tí ń bẹ ní ọ̀run yóo fi ohun rere fún àwọn tí ó bá bèèrè lọ́dọ̀ rẹ̀.

**Filippi 4:6**
Ẹ má ṣe jẹ́ kí ohunkohun dààmú yín, ṣugbọn ninu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ yín, ẹ máa fi àwọn ìbéèrè yín siwaju Ọlọ́run pẹlu ọpẹ́.

**Orin Dafidi 23:1**
OLÚWA ni Olùṣọ́-aguntan mi, n kò ní ṣe àìní ohunkohun.

**Orin Dafidi 34:10**
Àwọn ọmọ kinniun a máa ṣe aláìní, ebi a sì máa pa wọ́n; ṣugbọn àwọn tí wọ́n bá ń wá OLÚWA kò ní ṣe aláìní ohun rere kankan.

**Orin Dafidi 37:25**
Mo ti jẹ́ ọmọde rí; mo sì ti dàgbà: n kò tíì ri kí á kọ olódodo sílẹ̀, tabi kí ọmọ rẹ̀ máa tọrọ jẹ.

**Romu 8:32**
Ọlọ́run, tí kò dá Ọmọ rẹ̀ sí, ṣugbọn tí ó yọ̀nda rẹ̀ nítorí gbogbo wa, báwo ni kò ṣe ní fún wa ní ohun gbogbo pẹlu rẹ̀?

**Matiu 6:26**
Ẹ wo àwọn ẹyẹ lójú ọ̀run. Wọn kì í fúnrúgbìn, wọn kì í kórè, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í kó nǹkan oko jọ sinu abà. Sibẹ Baba yín tí ń bẹ ní ọ̀run ń bọ́ wọn. Mo ṣebí ẹ̀yin sàn ju àwọn ẹyẹ lọ!

**Luku 12:24**
Ẹ ṣe akiyesi àwọn ẹyẹ; wọn kì í fúnrúgbìn, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í kórè. Wọn kò ní ilé tí wọn ń kó nǹkan pamọ́ sí, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò ní abà. Sibẹ Ọlọ́run ń bọ́ wọn. Mélòó-mélòó ni ẹ fi sàn ju àwọn ẹyẹ lọ.

**Johanu 16:23-24**
"Ní ọjọ́ náà, ẹ kò ní bi mí léèrè ohunkohun. Mo fẹ́ kí ẹ mọ̀ dájúdájú pé ohunkohun tí ẹ bá bèèrè lọ́dọ̀ Baba ní orúkọ mi, yóo fun yín. Ẹ kò ì tíì bèèrè ohunkohun ní orúkọ mi títí di ìsinsìnyìí. Ẹ bèèrè, ẹ óo sì rí gbà, kí ẹ lè ní ayọ̀ lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́.

**Johanu Kinni 3:22**
À ń rí ohunkohun tí a bá bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀ gbà, nítorí pé à ń pa àṣẹ rẹ̀ mọ́, a sì ń ṣe ohun tí ó dára lójú rẹ̀.

**Romu 8:32**
Ọlọ́run, tí kò dá Ọmọ rẹ̀ sí, ṣugbọn tí ó yọ̀nda rẹ̀ nítorí gbogbo wa, báwo ni kò ṣe ní fún wa ní ohun gbogbo pẹlu rẹ̀?

**Diutaronomi 8:7-9**
Nítorí pé ilẹ̀ dáradára ni ilẹ̀ tí OLÚWA Ọlọ́run yín ń mu yín lọ. Ó kún fún ọpọlọpọ adágún omi, ati orísun omi tí ó ń tú jáde ninu àwọn àfonífojì ati lára àwọn òkè. Ilẹ̀ tí ó kún fún ọkà ati baali, ọgbà àjàrà ati igi ọ̀pọ̀tọ́, ati igi pomegiranate, ilẹ̀ tí ó kún fún igi olifi ati oyin. Ilẹ̀ tí ẹ óo ti máa jẹun, tí kò ní sí ọ̀wọ́n oúnjẹ, níbi tí ẹ kò ní ṣe aláìní ohunkohun. Ilẹ̀ tí òkúta rẹ̀ jẹ́ irin, tí ẹ óo sì máa wa idẹ lára àwọn òkè rẹ̀.

**Diutaronomi 28:11-12**
OLÚWA óo fún ọ ní ọpọlọpọ ọmọ, ati ọpọlọpọ ẹran ọ̀sìn. Àwọn igi eléso rẹ yóo máa so jìnwìnnì ní ilẹ̀ tí OLÚWA Ọlọ́run rẹ búra fún àwọn baba rẹ, pé òun yóo fún ọ. OLÚWA yóo fún ọ ní ọpọlọpọ òjò ní àkókò rẹ̀ láti inú ilé ìṣúra rẹ̀ lójú ọ̀run, yóo sì bukun iṣẹ́ ọwọ́ rẹ. Ìwọ ni o óo máa yá ọpọlọpọ orílẹ̀-èdè ní nnkan, o kò sì ní tọrọ lọ́wọ́ wọn.

**Orin Dafidi 68:19**
Ìyìn ni fún OLÚWA, Ọlọ́run ìgbàlà wa, tí ń bá wa gbé ẹrù wa lojoojumọ.

**Orin Dafidi 65:9**
Ò ń ṣìkẹ́ ayé, o sì ń bomi rin ín, o mú kí ilẹ̀ jí kí ó sì lẹ́tù lójú; o mú kí omi kún inú odò ìwọ Ọlọ́run, o mú kí ọkà hù lórí ilẹ̀; nítorí pé bẹ́ẹ̀ ni o ṣe ṣètò rẹ̀.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo dúpẹ́ nítorí òn bùkún iṣẹ́ ọwọ́ mi, mosì ṣe ìlérí láti fi ohun ìní mi àti èso mi àkọ́kọ́ bú ọlá fún ọ, ọgbà mí yóò kún fún ọ̀pọ̀.
- Baba olúwa, n ó sìn ọ́, n ó sì gbọ́ràn kín bàle lo ọjọ́ mi nínú ọ̀rọ̀ àti ìgbà mi nínú ìgbádùn.
- Olúwa, mú ọ̀rọ̀ rẹ ṣẹ, kí ó sì fúnmi ní ìbùkún tí kò ní làálà nínú.
- Torí mo jẹ́ afúni, afúni kìí sí tọrọ, ìwọ yóò pèsè fún àìní mi gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ rẹ́ nínú Jésù Krístì, èmi yóò ya orílẹ̀ èdè, n kòsí ní yá lọ́wọ́ ẹnikẹ́ni. Ìbùkún Ábráhámù jẹ́ tèmi, mo sì gba ìlérí ẹ̀mí nípasẹ̀ ìgbàgbọ́.

- Èmi àti àwọn ẹbí mi yóò ga bí igi ọ̀pe tí a gbìn sípa ódò tín mú èso rẹ̀ wá nígbà tó yẹ, ewé re kìí gbọ̀n, ohun gbogbo tí a bá sì dáwọ́lé yóò ṣe rere.

- Bàbá, modúpẹ́ fún orẹ-ọ̀fẹ́ rẹ tí o rípe á bá gbogbo àìní mi pàdé, mósì ní ju ohun tí moníló lọ kín báalè je ìbùkún fún ìran mí.

- Mo jẹ́wọ́ wípé èso mi dí ọ̀pọ̀, mo sìn gbádùn ọpọ Olúwa.

- Àwọ́n èso òdodo mí n pọ̀si, a sì ti kún mi pẹ̀lú rere Olúwa.

- Bàbá, mo gbàgbọ́ nínú ìlérí rẹ nípa ọwọ́ mi. Rànmílọ́wọ́ láti jẹ́ olóòtọ́ tín mú ìdámẹ́wà wásí ilé rẹ kí oúnjẹ ba lé wàníl̀ẹ́ rẹ, kí o balè sí fèrèsé ọ̀run sílẹ̀ fún mi tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ tí n kòní rí àyè kó ìbùkún náà sì mọ́.

# ORÍ ÌKEJÌLÈLÓGÚN

ÀWỌN ỌMỌDÉ



## Ṣe Àṣàrò

**`Jeremaya 1:5**

"Kí n tó dá ọ sinu ìyá rẹ ni mo ti mò ọ́, kí wọ́n sì tó bí ọ ni mo ti yà ọ́ sọ́tọ̀, mo yàn ọ́ ní wolii fún àwọn orílẹ̀-èdè."

**Iwe Òwe 22:6**
Tó ọmọ rẹ sí ọ̀nà tí ó yẹ kí ó máa rìn, bí ó bá dàgbà tán, kò ní kúrò ninu rè̩.

**Orin Dafidi 37:23**
OLÚWA níí darí ìgbésè ẹni; a sì máa fi ẹsẹ̀ ẹni tí inú rẹ̀ bá dùn sí múlẹ̀.

**Efesu 6:1-3**
Ẹ̀yin ọmọ, ẹ máa gbọ́ ti àwọn òbí yín nítorí pé béẹ̀ ni ó dára. "Bọ̀wọ̀ fún baba ati ìyá rẹ." Èyí níí ṣe òfin kinni pẹlu ìlérí, pé "Kí ó lè dára fún ọ, ati kí o lè pẹ́ lórí ilẹ̀ náà."

**Romu 13:2**
Nítorí náà, ẹni tí ó bá fojú di aláṣẹ ń tàpá sí àṣẹ Ọlọrun. Àwọn tí ó bá sì ṣe àfojúdi yóo forí ara wọn gba ìdájọ́.

**Orin Dafidi 91:7**
Ẹgbẹrun lè ṣubú ní ẹ̀gbẹ́ rẹ, tabi ẹgbaarun ni apá ọ̀tún rẹ; ṣugbọn kò ní súnmọ́ ọ̀dọ̀ rẹ.

**Orin Dafidi 91:10-11**
Ibi kankan kò ní dé bá ọ, bẹ́ẹ̀ ni àjálù kankan kò ní súnmọ́ ilé rẹ. Nítorí yóo pàṣẹ fún àwọn angẹli rẹ̀, nítorí rẹ, pé kí wọ́n máa pa ọ́ mọ́ ní gbogbo ọ̀nà rẹ.

**Orin Dafidi 91:14**
OLÚWA ní, "Nítorí pé ó nífẹ̀ẹ́ sí mi, n óo gbà á là; n óo dáàbò bò ó, nítorí pé ó mọ orúkọ mi.

**Diutaronomi 28:2-4**
Gbogbo ibukun wọnyi ni yóo mọ́ ọ lórí, tí yóo sì ṣẹ sí ọ lára, bí o bá gbọ́ ti OLÚWA Ọlọ́run rẹ. "OLÚWA yóo bukun ọ ní ààrin ìlú, yóo sì bukun oko rẹ. "Yóo bukun àwọn ọmọ rẹ, ati èso ilẹ̀ rẹ, ati àwọn ẹran ọ̀sìn rẹ, ati àwọn ọmọ màálúù rẹ, ati àwọn ọmọ aguntan rẹ.

**Jemisi 1:17**
Láti òkè ni gbogbo ẹ̀bùn rere ati gbogbo ẹ̀bùn pípé ti ń wá, a máa wá láti ọ̀dọ̀ Baba tí ó dá ìmọ́lẹ̀, baba tí kì í yí pada, tí irú òjìji tíí máa wà ninu ìṣípò pada kò sì sí ninu rè̩.

**Orin Dafidi 91:7**
Wò ó! Ẹ̀bùn OLÚWA ni ọmọ; òun ní fi oyún inú ṣìkẹ́ ẹniyan.

**Aisaya 54:13**
"Gbogbo àwọn ọmọ rẹ ọkunrin, ni OLÚWA yóo kọ́ wọn yóo sì ṣe ọpọlọpọ àṣeyọrí.

**Aisaya 65:23**
Wọn kò ní ṣe iṣẹ́ àṣedànù, wọn kò ní bímọ fún jamba; nítorí ọmọ ẹni tí OLÚWA bukun ni wọn yóo jẹ́, àwọn ati àwọn ọmọ wọn.

**Orin Dafidi 118:17**
N ò ní kú, yíyè ni n óo yè, n óo sì máa fọnrere nnkan tí OLÚWA ṣe.

**Aisaya 8:18**
**Ẹ wò ó! Èmi ati àwọn ọmọ tí OLÚ**WA fún mi, a wà fún àmì ati ìyanu ní Israẹli láti ọ̀dọ̀ OLÚWA àwọn ọmọ ogun, tí ń gbé orí òkè Sioni.

**Orin Dafidi 8:2**
Àwọn ọmọ-ọwọ́ ati àwọn ọmọ-ọmú ń kọrin ògo rẹ, wọ́n ti fi ìdí agbára rẹ múlẹ̀, nítorí àwọn tí ó kórìíra rẹ, kí á lè pa àwọn ọ̀tá ati olùgbẹ̀san lẹ́nu mọ́.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Bàbá, mo dúpẹ́ fún ìlérí rẹ láti pa ọmọ mi mọ́, àti ìdánilójú rẹ́ láti dáàbò bo ohun gbogbo tí mo bá fi sí ọ lọ́wọ́. Mo gbàgbọ́ wípe ìwọ yóò tọ̀ wọ́n sí ìgbàlà. Jẹ́kí ọ̀rọ̀ rẹ fi ẹ̀mí òtítọ́ hàn sí wọn, kí o si rán wọn lọ́wọ́ láti máa ṣàṣàrò nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀. Rànwọ́n lọ́wọ́ láti le súnmọ́ wọn kí ó bá lè súnmọ́ wọn, kí wọ́n sì ní etí láti gbọ ohun rẹ̀. Mú àlá wọn n wásí ìmúṣẹ Olúwa kí wọ́n le jẹ́ olóòtọ́ sí ọ.

- Olúwa, mo dúpẹ́ fún èrò rere tí o ní fún àwọn ọmọ mi kí á tó lóyún wọn, ránwọ́n lọ́wọ́ láti ní ìfaradà kí wọ́n lè mú àyànmọ́ wọn wá sí ìmúṣẹ ní orúkọ Jésù. Àmín.

- Bàbá mi ọ̀run, mo ko àwọn ọmọ mi wá sí iwájú ìtẹ́ ore-ọ̀fẹ́ rẹ, mo bèèrè fún ìtẹ́lọ́rùn fún ohun gbógbo tí o fún wọn àti ohun gbogbo tí o máá fún wọn. Jẹ́ kí wọ́n mọ̀ wípé ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú ìwà bí Ọlọ́run yóo fún wọn ní èrè ńlá. Àwọn kan gbọ́kànlé kẹ̀kẹ́ ogun, ṣùgbọ́n mo gbàdúrà wípé àwọn ọmọ mi yóò gbẹ́kẹ̀ wọ́n le ọ. Mú wọn jẹ́ olóòtọ́ nínú ohun kékeré kí wọ́n le rí ìbùkún ńlá gbà.

- Mo dúpẹ́ pé o jẹ́ asà àti ìsádi fún àwọn ọmọ mi. Bí wọ́n tiwà ní abẹ́ òjìjí rẹ, wọn kò ní wà nínú ewu ìjàmbá kankan.

- Nítorí pé ó pàṣẹ fún àwọn ángẹ́lì rẹ láti máa dáàbò bò wọ́n ní ọ̀nà wọn gbogbo. Jẹ́ kí àwọn ángẹ́lì rẹ pagbo yi wọn ká.

- Mo di ìlérí rẹ mú wípé wọ́n á lọ ní ọ̀nà wọn, wọ́n kòsí ní kosẹ̀, fún wọn ní ore-ọ̀fẹ́ láti máṣe bẹ̀rù bí ẹgbẹgbẹ̀rún tilẹ̀ ṣubú ní ẹ̀gbẹ́ wọn torí ó ti ṣe 'lérí wípé kòní súnmọ́ wọn. Ìwọ̀ yóò gbà wọ́n, oo dààbo bò wọ́n, ó sì fún wọn ní ẹ̀mí gígùn, ó sì fi ìgbàlà rẹ hàn wọ́n torí wọ́n nifé rẹ̀.

- Mo dúpẹ́ fún ohun ìní tí moní lórí àwọn ọmọ mi. Rànmílọ́wọ́ láti kọ́ wọn ní ọ̀nà tí ó yẹ kí wọ́n tọ̀, kí ẹ̀mí rẹ sì máa darí wọn. Nítorí orúkọ rẹ, dárí wọn kí o sì pawọ́n mọ́, bí o tijẹ́ ìwọ nìkan ni o lè dárí afọ́jú ni ọ̀nà tí wọ́n kòmọ̀ tí yóò sọ òkùnkùn wọn di ìmọ́lẹ̀, tí yóò sì mú ibi wíwọ́ wọn di títọ́. Sọ ọkàn wọn di ọ̀tun nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ rẹ, kí wọ́n mọ ìfẹ́ rẹ fún ayé wọn.

- Bàbá, jẹ́kí àwọn ọmọ mi nífẹsi ìjọsìn pẹ̀lú rẹ, kí o ba lejẹ̀ ohun pàtàkì jùlọ nínú ọkàn wọn, kí wọ́n sì ní ìtura fún ẹmi wọn.

- Mo gbàdúra wípé àwọn ọmọ mi yóò lewá síwájú rẹ nínú àdúrà láti gba ohunkóhun nípasẹ̀ ìgbàgbọ́, kí wọ́n sì mọ̀ wípé àdúrà wọn ṣiṣẹ́ agbára, àti pé ìwọ yóò gbọ́ wọn ó sì dáwọn lóhùn nítorí ó ní ìfẹ wọn lọ́ kàn. Mo gbàdúrà wípé wọ́n lágbára rẹ nínú iṣẹ́ látiṣe àyípadà láyíká wọn, ju èyí ti wọ́n lérò tàbí bèèrè lọ nígbàtí ó mú ohun gbogbo ṣiṣẹ́ pọ̀ fún rere fún wọn.

- Bàbá, ìwọ ni ó ntọ́ ìgbésẹ̀ àwọn ọmọ rẹ, tọ́ ìgbésẹ̀ àwọn ọmọ mi sì eegun nínú eegun wọn, àti ẹran nínú ẹran ara wọn. Mo gbàdúrà wípé wọn kòní ṣí ọkọ/aya fẹ, ṣùgbọ́n wọn a kọ́ láti tẹ̀lé ìdarí yín kí wọ́n le pàdé onírú ìfẹ́ yín tí ó ṣe sùúrù, tí ó dára, tí kìí ṣé ìlara, tíkò ṣe ìgbéraga, tí kìí tètè bínú, tàbí kò íwe iṣẹ́ sílẹ̀, tíkò ṣe inúdidùn sí iṣẹ́ ibi ṣùgbọ́n tí ò ń yọ̀ nínú òdodo. Mo gbàdúrà wípé wọn a ní ọkọ/aya tí ó ní ọkàn tí ó dára, àti ẹ̀mi tí ó tutù.

- Olúwa Jésu, mo gbàdúrà pé àwọn ọmọ mi yóò rìn nínú ìgbọràn sí Ọlọ́run. Ràn wọ́n lọ́wọ́ láti rí wípé àìgbọràn si òbí tàbí òfin ilé máa ní ìdájọ́ tí wọ́n gbọ́dọ̀ yẹ fún dání.

- Àwọn ọmọ mi jẹ́ ohun ìní mi àti èrè mi, Olúwa yóò kọ́ wọn, àlàfíà wọn yóò sì jẹ́ ńlá. N kò ní ṣe làálà lásán lórí wọn, n kòsí ní tọ́ ọmọ fún wàhálà.

- Gẹ́gẹ́ bí ìlérí ìbùkún rẹ, nígbà tí wọn bá rìn nínú ìgbọràn rẹ, fún wọn ní ore-ọ̀fẹ́ láti yan èyí tí ó dá ki wọn ma ba wà nínú àìní.

- Mo kọ gbogbo alábàrín ibi tí kòní jẹ́kí àwọn ọmọ mí gba ẹ̀bùn rere tí Ọlọ́run. Mo gbàdúrà wípé ẹ ó pa wọ́n mọ́ kúrò lọ́wọ́ alábàrìn àti èniyàn ibi tí ó báfẹ́ ṣe wọ́n ní'bi lọ́nàkọnà.

- Ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́ tí wọ́n bá ti wọ̀ tí kìí ṣe ìfẹ́ rẹ, mo fi ẹ̀jẹ̀ Jésù ba ẹgbẹ́ náà jẹ́. Pa ọkàn wọn mọ́ kúrò nínú ìrọraa ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́. Jẹ́kí wọ́n wà nínú ìfẹ́ pípé rẹ ní orúkọ Jésù.

- Olúwa, mo gbàdúrà fún ọgbọ́n fún àwọn ọmọ mi, kí wọ́n ń ṣiṣẹ́ rere nínú ìwé kíkà wọn nítorí wọ́n ní ọkàn Krístì. Mo dúpẹ́ fún ọgbọ́n, agbára, ìmọ̀, àti òye tí ẹ ti fi sí inu ìmọ̀ wọn, mo sì gbàdúrà wípé wọ́n a lọ ní ọ̀nà tí ò yẹ sí ògo rẹ̀.

- Fi ìdí iṣẹ́ ọwọ́ wọn múlẹ̀, jẹ́kí ojúrere rẹ wà lórí wọn ní ohun gbogbo tí wọ́n bá ṣe. jẹ́kí wọ́n rí èrè isẹ́ wọn nínú ẹ̀kọ́ wọn.

- Fún wọn ní ore ọ̀fẹ́ láti rántí ohun tí wọn ti kà nípasẹ̀ Ẹ̀mi Mímọ́ tí on kọ́ wọn ní ohun gbogbo. Adúpẹ́ pé ẹ wà fúnwa nígbà ìpọ́njú. Ro wọn lágbára, kí o sì dì wọ́n mú pẹ̀lú ọwọ́ ọ̀tun ìṣẹ́gun rẹ ní Orúkọ Jésù.

- Àwọn ọmọ mí kì yóò kú bíkòṣe yíye láti ròyìn ogo Ọlọ́run nínú ayé wọn, búburú kan kòní ṣubú lù wọ́n, òye ọjọ́ orí wọn ni àwọn yóò lo ní Orúkọ Jésù, Àmín.

## Awàdà

**Ìṣẹ́jú Kan**

Okùnrin kan tí n gbìyànjú láti mọ irú ẹni tí Ọlọ́run jẹ́ bèerè lọ́wọ́ rẹ wípé "Ọlọ́run, báwo ni mílíọnù ọdún ṣe pé sí lójú rẹ̀?"
Ọlọ́run sì dáhùn wípé: "ó dàbí ìṣẹ́jú kan símì ní o"
Ọkùnrin náà si beere wípé: "Ọlọ́run, báwoní million dọ́là ṣe jẹ́ níwájú rẹ?"
Ọlọ́run sì fèsì wípé: "Ó dàbí owo ẹyọ sí mi"
Ọkùnrin náà wá wípé: "Ọlọ́run, ẹ fún mi ní Owó ẹyọ kan?" Ọlọ́run sì dalóhùn wípé "màá fún ẹ lẹ́yìn ìṣẹ́jú kan".

# ORÍ ÌKẸTALÉLÓGÚN

## ÌWÒSÀN



## Ṣe Àṣàrò

**Jeremaya 17:14**
Wò mí sàn, OLÚWA, ara mi yóo sì dá, gbà mí, n óo sì bó ninu ewu. Nítorí pé ìwọ ni mò ń yìn.

**Ẹksodu 15:26**
Ó ní, "Bí ẹ bá farabalẹ̀ gbọ́ ohùn èmi OLÚWA Ọlọ́run yín, tí ẹ sì ṣe ohun tí ó tọ́ lójú mi, tí ẹ pa gbogbo òfin mi mọ́, tí ẹ sì tẹ̀lé gbogbo ìlànà mi, èmi OLÚWA kò ní fi èyíkéyìí ninu àwọn àrùn tí mo fi ṣe àwọn ará Ijipti ṣe yín, nítorí pé, èmi ni OLÚWA, olùwòsàn yín."

**Ẹksodu 23:25**
Èmi OLÚWA Ọlọ́run yín ni kí ẹ máa sìn. N óo pèsè ọpọlọpọ nnkan jíjẹ ati nnkan mímu fún yín, n óo sì mú àìsàn kúrò láàrin yín.

**Aisaya 53:4-5**
Nítòótọ́, ó ti gbé ìkáàánú wa lọ, ó sì ti ru ìbànújẹ́ wa; sibẹsibẹ a kà á sí ẹni tí a nà, tí a sì jẹ níyà láti ọ̀dọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ gẹ́gẹ́ Ọlọ́run. Ṣugbọn wọ́n ṣá a lọ́gbẹ́ nítorí àìdára wa, wọ́n pa á lára nítorí ẹ̀ṣẹ̀ wa; ìyà tí wọ́n fi jẹ ẹ́ ni ó fún wa ní alaafia, nínà tí a nà án ni ó mú wa lára dá.

**Jeremaya 30:17**
N óo fun yín ní ìlera, n óo sì wo àwọn ọgbẹ́ yín sàn, èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀. Nítorí wọ́n ti pè yín ní 'Ẹni ìtanù, Sioni tí ẹnikẹ́ni kò bìkítà fún.'

**Johanu Kẹta 1:2**
Olùfẹ́, mo gbadura pé kí ó dára fún ọ ní gbogbo ọ̀nà ati pé kí o ní ìlera, gẹ́gẹ́ bí o ti ní ìlera ninu ẹ̀mí.

**Aisaya 40:29-31**
A máa fún aláàárẹ̀ ní okun. A sì máa fún ẹni tí kò lágbára ní agbára. Yóo rẹ àwọn ọ̀dọ́ pàápàá, agara óo sì dá wọn, àwọn ọdọmọkunrin yóo tilẹ̀ ṣubú lulẹ̀ patapata. Ṣugbọn àwọn tí ó bá dúró de OLÚWA yóo máa gba agbára kún agbára. Wọn óo máa fi ìyẹ́ fò lọ sókè bí ẹyẹ idì. Wọn óo máa sáré, agara kò ní dá wọn; wọn óo máa rìn, kò sì ní rẹ̀ wọ́n.

**Ọrin Dafidi147:3**
Ó ń tu àwọn tí ọkàn wọn bàjẹ́ ninu, ó sì ń dí ọgbẹ́ wọn.

**Matiu 4:23-24**
Jésù wá ń kiri gbogbo Galili, ó ń kọ́ àwọn eniyan ninu ilé ìpàdé wọn, ó ń waasu ìyìn rere ìjọba Ọlọ́run, ó tún ń wo oríṣìíríṣìí àrùn sàn lára àwọn eniyan. Òkìkí rẹ̀ kàn ká gbogbo

Siria. Àwọn eniyan ń gbé gbogbo àwọn tí ó ní oríṣìíríṣìí àrùn ati àìlera wá sọ́dọ̀ rẹ̀ ati àwọn tí ẹ̀mí Èṣù ń dà láàmú, ati àwọn tí wárápá mú ati àwọn arọ; ó sì ń wò wọ́n sàn.

**Ise Awọn Aposteli 10:38**
Ẹ mọ̀ nípa Jésù ará Nasarẹti, bí Ọlọ́run ti ṣe yàn án, tí ó fún un ní Ẹ̀mí Mímọ́ ati agbára; bí ó ti ṣe ń lọ káàkiri tí ó ń ṣe rere, tí ó ń wo gbogbo àwọn tí Satani ti ń dá lóró sàn, nítorí Ọlọ́run wà pẹlu rẹ̀.

**Ọrin Dafidi 107:20**
Ó sọ̀rọ̀, ó sì mú wọn lára dá, ó tún kó wọn yọ ninu ìparun

**Orin Dafidi 103:2-3**
Yin OLÚWA, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo oore rẹ̀, ẹni tí ó ń dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì ọ́, tí ó ń wo gbogbo àrùn rẹ sàn.

**Romu 8:11**
Njẹ́ bí Ẹ̀mí Ọlọ́run, ẹni tí ó jí Jésù dìde kúrò ninu òkú, bá ń gbé inúyín, òun náà tí ó jí Kristi dìde kúrò ninu òkú yóo sọ ara yín, tí yóo kú, di alààyè nípa Ẹ̀mí rẹ̀, tí ó ń gbé inú yín.

**Jemisi 5:14-16**
Bí ẹnikẹ́ni ninu yín bá ń ṣàìsàn, kí ó pe àwọn àgbà ìjọ jọ, kí wọ́n gbadura fún un, kí wọ́n fi òróró pa á lára ní orúkọ Olúwa. Adura pẹlu igbagbọ yóo mú kí ara alàìsàn náà yá. Olúwa yóo gbé e dìde, a óo sì dárí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí ó ti dá jì í. Ẹ máa jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ yín fún ara yín, ẹ máa gbadura fún ara yín kí ẹ lè ní ìwòsàn. Adura àtọkànwá olódodo lágbára, nítorí Ọlọ́run a máa fi àṣẹ sí I.

**Malaki 4:2**
Ṣugbọn ní ti ẹ̀yin tí ẹ bẹ̀rù mi, oòrùn òdodo yóo tàn si yín pẹlu ìwòsàn mi, ẹ óo máa yan káàkiri bí ọmọ ẹran tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ tú sílẹ̀.

**Luku 4:18**
"Ẹ̀mí Olúwa wà pẹlu mi nítorí ó ti fi òróró yàn mí láti waasu ìyìn rere fún àwọn talaka. Ó rán mi láti waasu ìtúsílẹ̀ fún àwọn tí wọ́n wà ní ìgbèkùn, ati láti mú kí àwọn afọ́jú ríran; láti jẹ́ kí àwọn tí a ni lára lọ ní alaafia.

**Luku 8:50**
Ṣugbọn nígbà tí Jesu gbọ́, ó dá a lóhùn pé, "Má bẹ̀rù, ṣá gbàgbọ́, ara ọmọ rẹ yóo dá."

**Peteru Kinni 2:24**
Òun fúnrarẹ̀ ni ó ru ẹ̀ṣẹ̀ wa lórí igi, kí á baà lè kú sí ẹ̀ṣẹ̀, kí á wà láàyè sí òdodo. Nípa ìnà rẹ̀ ni ẹ fi ní ìmúláradá.

- ́Jésù ru ẹ̀ṣẹ̀ mi lórí igi àgbélébù, nítorí èyí, moti di òkú sí ẹ̀ṣẹ̀, mo sì di ààyè sí Ọlọ́run àti nípa ìnà rẹ ati mú mi lára dá.

- Jésù ru àìlera mi ó sì ru àìsàn mi, nítorína nkò gba àìsàn ní àyè láti jọba lórí mi. Ìyè Ọlọ́run ń ṣàn lára mi bí omi, ó sì ń mú ìlera wá sí gbogbo ara mi.

- Mo jẹ́wọ́ mosì pàṣẹ wípé agbára ìyè àti ikú wà ní ahọ́n mi, bẹ́ẹ̀ni mo sì loo láti jẹ́ẹ́kí ìyè Ọlọ́run ṣan tó gbogbo ara mi ká báyí.

- Ara mí jẹ́ tẹ́mpìlì Ọlọ́run, bẹ́ẹ̀ ni mo yin Ọlọ́run bí moṣe ńrìn ni ìwòsàn láì lo òògun.

- Ẹ̀mi kannà tí ó jí Jésù dìde nínú òkú ńgbé inú mi, ó sì ń fi ìyè sí ara kíkú mi. Bí ó tílẹ jẹ̀ wípé ara mi yóò di àìkú nígbàti ó bá fara hàn. Ní ìsinsìnyí mo gba ìyè Ọlọ́run nínú àgọ́ ara mi.

- Jésù ti ràmípadà lọ́wọ́ gbogbo ègún òfin nítorípé ó ti di ègún fún mi. Nítorí ọ̀rọ̀ rẹ̀ sọ wípé ègún ni ẹni tí a fi kọ sí orí igi. Ìdí èyí ní àìsàn kí àìsàn kò ṣe le dúró ní ara tàbí ayé mi.

- Mo gbọ́wọ́lé ìbùkún Ábráhàmu, ara mì ni ibi ibùgbé mi bẹ́ẹ̀ni baba mi tí jẹ́wọ́ wípé àìsàn kò lee wá sí àgọ́ ara mí. Bẹ́ẹ̀ni ó jẹ́ ẹbọ ààyè tí mo fi fún Ọlọ́run.

- Ọlọ́run ọba ti rán ọ̀rọ̀ rẹ tí o wò mí sàn tí ó sì dámi ní ìdè lọ́wọ́ gbogbo ìparun nítorí ó ti ṣèlérí láti fúnmi ni ìlérá kí ó sì wo àìsàn mi sàn.

- Iye Ọlọ́run sọ ara kíkú mi di ààyè, Ẹ̀mí Ọlọ́run ńgbé inú mi, nítorínà mo pàṣẹ kí ara mi gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Gbogbo kokoro àìsàn gbúdọ̀ kú ní ojú ẹsẹ̀ ní Orúkọ Jésù. Mo pà ṣẹ́ kí gbogbo àìsàn ní ara mi kó kú. Àìsàn jẹjẹrẹ tàbí kòkòrò kò lee gbé ní àgọ́ ara mi. Gbogbo ẹ̀yà ara mi ń tẹ̀lé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, bẹ́ẹ̀ni mo gba ìlera mi, nítorína etí àti ojú mi ní mo kọ sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí mo sì pa wọ́n mọ́ sì oókàn àyà mí. Mo pàṣẹ ìyè, ìlera àti ìwòsàn sí gbogbo ara mí. Jésù ń rìn kiri láti wo wọ́n sàn, bẹ́ẹ̀ni ọ̀kan lánà lónì àti títí ayé ni. Nítorínà èmi nà kò ní gba ìyè méjì ní ọkàn mi, ó ti wọ èmi ná sàn ní òní.

- Gẹ́gẹ́ bí ìlérí Olúwa tí mo bá beere ohunkóhun ní orúkọ rẹ, tí mò ńgbé ní inú rẹ̀ àti ti ọ̀rọ̀ rẹ̀ si ńgbé ní inú mi, a ó ṣè fún mi. Nítorínà mo bèeré agbára ìwòsàn rẹ̀ lórí mí ní ìsinsìnyí.

- Ọmọ òdodo Ọlọ́run dìde bíi òòrun pẹ̀lú ìwòsàn ní apá rẹ̀ kí á lè gbà mí lọ́wọ́ gbogbo àìsàn àti àìlera kí ayọ̀ mi le

kún nípasẹ̀ rẹ lórúkọ Jésù. Àmín

**KÍ Á LE GBA ÈSÌ**

- Gbàgbọ́ wípé ó ti rí ìdáhùn tí o ba ti gba àdúrà, ojú ẹsẹ̀ ni ìwòsàn máa ń ṣẹlẹ̀.

- Àṣẹ lórí àìsàn àti àìlera kíí déédé ṣẹlẹ̀, ènìyàn gbúdọ̀ pinu láti di òní ìlera.

- Gbogbo ẹran ara wa.

- Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ni egbòogi rẹ̀ ní ẹran ara wa, nítorí o máa ń di ìyè ní ara wa.

- Kí á gbàgbọ́ nínú ìwosàn kò tó, o gbúdọ̀ gbà wípé ìfẹ́ Ọlọ́run ni fún ọ pé kí a mú ẹ lára dá.

- Jé olùgbọ́ràn láti gbà lọ́wọ́ Ọlọ́run

- Máṣe kọ ibi ara sí àwọn ohun tí ó lòdì sí ìgbàgbọ́ ìwosàn rẹ̀ ṣùgbọ́n wo ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ki ó sí kọ ibi ara sí ohun tí ó sọ

**Àwàdà**

`Ọmọ kékeré kan ṣí bíbélì nla pẹ̀lú ìjọlójú, bí ó sì ṣe ń ṣì ojú ewé na lójijì kíni kan bọ sílẹ nínú bíbélì, ó sì wóo dunjúdunjú, ewé igi kan ni ó jẹ́. Ó wá sọ fún ìyá rẹ̀ wípé ẹwọ ohun tí mo rí. Ìyá rẹ̀ bèère wípé kíni ohun tí ó rí? 'Pẹ̀lú ẹ̀rin àtí ọyaya, ọmọ ná dáhùn wípé 'Mo rò wípé ewé tí Ọlọ́run fi bo Ádámù nígbàtí ó wọ̀ inú ọgbà lójọ́sí ni.

**Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n**

Wá àsìkò láti máa gbàdúrà lójoojúmọ

# ORÍ ÌKẸRÌNLÉLÓGÚN

ÌRÀPADÀ



## Ṣe Àṣàrò

**Amosi 9:14-15**
N óo dá ire Israẹli, àwọn eniyan mi, pada, wọn yóo tún àwọn ìlú tí wọ́n ti wó kọ́, wọn yóo sì máa gbé inú wọn. Wọn yóo gbin àjàrà, wọn yóo sì mu ọtí waini rẹ̀. Wọn yóo ṣe ọgbà, wọn yóo sì jẹ èso rẹ̀. N óo fẹsẹ̀ àwọn eniyan mi múlẹ̀ lórí ilẹ̀ tí mo fún wọn, a kò sì ní ṣí wọn nípò pada mọ́ lórí ilẹ̀ tí mo fún wọn. Èmi OLÚWA Ọlọ́run yín ni mo sọ bẹ́ẹ̀."

**Aisaya 61:7**
Dípò ìtìjú ìpín tiyín yóo jẹ́ meji, dípò àbùkù ẹ óo láyọ̀ ninu ìpín tí ó kàn yín. Ìlọ́po meji ni ìpín yín yóo jẹ́ ninu ilẹ̀ yín, ayọ̀ ayérayé yóo sì jẹ́ tiyín.

**Peteru Kinni 5:10**
Ṣugbọn lẹ́yìn tí ẹ bá ti jìyà díẹ̀, Ọlọ́run tí ó ní gbogbo oore-ọ̀fẹ́, òun tí ó pè yín sinu ògo rẹ̀ ayérayé nípasẹ̀ Kristi, yóo mu yín bọ̀ sípò, yóo fi ẹsẹ̀ yín múlẹ̀, yóo fun yín ní agbára, yóo sì tún fi ẹsẹ̀ ìgbé-ayé yín múlẹ̀.

**Joeli 2:25**
Gbogbo ohun tí ẹ pàdánù ní àwọn ọdún tí àwọn ọmọ ogun mi tí mo rán si yín ti jẹ oko yín; ati èyí tí eṣú wẹẹrẹ jẹ, ati èyí tí eṣú ńláńlá jẹ, gbogbo rẹ̀ ni n óo dá pada fun yín.

**Jeremaya 30:17**
N óo fun yín ní ìlera, n óo sì wo àwọn ọgbẹ́ yín sàn, èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀. Nítorí wọ́n ti pè yín ní 'Ẹni ìtanù, Sioni tí ẹnikẹ́ni kò bìkítà fún.'

**Joobu 42:10**
Lẹ́yìn ìgbà tí Jobu gbadura fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ mẹtẹẹta tán, OLÚWA dá ọrọ̀ Jobu pada, ó sì jẹ́ kí ó ní ìlọ́po meji àwọn o

**Sekaraya 9:12**
Ẹ pada sí ibi ààbò yín, èyin tí a kó lẹ́rú lọ tí ẹ sì ní ìrètí; mo ṣèlérí lónìí pé, n óo dá ibukun yín pada ní ìlọ́po meji.

**Aisaya 40:31**
Ṣugbọn àwọn tí ó bá dúró de OLÚWA yóo máa gba agbára kún agbára. Wọn óo máa fi ìyẹ́ fò lọ sókè bí ẹyẹ idì. Wọn óo máa sáré, agara kò ní dá wọn; wọn óo máa rìn, kò sì ní rẹ̀ wọ́n.

**Orin Dafidi 23:3**
Ó sọ agbára mi dọ̀tun. Ó tọ́ mi sí ọ̀nà òdodo nítorí orúkọ rẹ̀.

**Jeremaya 29:14**
Ẹ óo rí mi, n óo dá ire yín pada, n óo ko yín jọ láti gbogbo orílẹ̀-èdè ati láti gbogbo ibi tí mo ti le yín lọ;

n óo sì ko yín pada sí ibi tí mo ti le yín kúrò lọ sí ìgbèkùn. Èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀.

**Orin Dafidi 145:14**
OLÚWA gbé gbogbo àwọn tí ń ṣubú lọ dìde, ó sì gbé gbogbo àwọn tí a tẹrí wọn ba nàró.

**Isikieli 34:16**
"N óo wá àwọn tí ó sọnù, n óo sì mú àwọn tí wọ́n ṣáko lọ pada, n óo tọ́jú ọgbẹ́ àwọn tí wọ́n farapa, n óo fún àwọn tí kò lókun lágbára, ṣugbọn àwọn tí wọ́n sanra ati àwọn tí wọ́n lágbára ni n óo parun, nítorí òtítọ́ inú ni n óo fi ṣọ́ àwọn aguntan mi.

**Aisaya 65:21-22**
Wọn óo kọ́ ilé, wọn óo gbé inú rẹ̀; wọn óo gbin ọgbà àjàrà, wọn óo sì jẹ èso rẹ̀. Wọn kò ní kọ́lé fún ẹlòmíràn gbé, wọn kò sì ní gbin ọgbà àjàrà fún ẹlòmíràn jẹ. Àwọn eniyan mi yóo pẹ́ láyé bí igi ìrókò, àwọn àyànfẹ́ mi yóo sì jèrè iṣẹ́ ọwọ́ wọn.

**Orin Dafidi 126:1-2a**
Nígbà tí OLÚWA kó àwọn ìgbèkùn Sioni pada, ó dàbí àlá lójú wa. Ẹ̀rẹ̀kẹ́ wa kún fún ẹ̀rín, a sì kọrin ayọ̀.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Ọlọ́run olóòreọ̀fẹ́, bí ìyá tí ẹ ti jẹmí tẹ́lẹ̀, ìwọ Ọlọ́run mi lágbára láti ṣe àṣepé, nítorínà fi ìdí mi sọlẹ̀, ró mi lágbára kí o sì fi ọkàn mi balẹ̀ ní orúkọ Jésù Àmín.

- Mi ò ṣe àníyàn kankan nítorí mo ti mú àníyàn mi wá síwájú Olúwa, ó sì gbọ́ mi nípasẹ̀ àdúrà àti ìṣìpẹ̀, ó sì fúnmi ní ẹ̀dùn ọkàn mi.

- Àláfíà Ọlọ́run dá àbò bo ọkàn mí nípasẹ̀ Jésù Kírístì. Mó n ro ohun tó jẹ́ dáradára, mímọ́, pípé ati ìròyìn dáradára

- Mo dúpẹ fún ìlérí ìdápadà àti ìṣelọ́ṣọ́ mi, ẹbi mi, ìgbéyàwó mi, iṣẹ́ mí àti pàápàá ìdùnú àti ayọ̀ ní a o rí ni àyíká mi láti òní lọ

- Ìwọ kì yóò bínú sími àti pe àwọn alâìmọ̀ tàbí àwọn alâìpé kì yóò

wá sí ọ̀dọ̀ mi bí óṣe ńdá ìlera àti ìwòsàn mi padà àti ohun gbogbo tó yí mi ká tó sì jẹ̀ tèmi

- Èmí kì yóò ṣe aláìní gbogbo ohun tó jẹ́ tèmi bí mo ṣe ń gba ìkólọ mi padà lọ́wọ́ ìjọba okùnkun nítorí ore-ọfẹ àti ojú rere rẹ.

- Mo gba ohun gbogbo tí ọ̀ta tí gbà lọ́wọ́ mí padà. Nítorí àánú rẹ̀, mo rí ore-ọ̀fẹ́ rẹ, ànú gbàmí sílẹ̀ láti gba ọ̀rọ̀ àwọn ẹ́lẹ́nì. Èmi yóò gbìn n ó sì jẹ èrè iṣẹ́ ọwọ́ mi. Èmi kì yóò ṣe lásàn. Ìwọ yíò dápadà fún mi gbogbo ohun tí kòkòrò ajẹnirun tí jẹ àti pẹ̀lú ìwọ yóò yí ìgbà mi padà.

- Oṣé tí o sọ gbogbo ọ̀nà wíwọ́ dí títò fún mi ní gbogbo ágbọn ayé mi. Oṣe tí o dá ìgbà mi padà ti o sin dárì mi ní ipa ọ̀nà òdodo, mo mọ̀ dájú pé òdodo mi tí ọwọ́ rẹ wá.



## Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n

Ní ibi ìdákẹ́ rọ́rọ́ tí kò sí ìdíwọ́ kankan láti wà pẹ̀lú Ọlọ́run

## Ọ̀rọ̀ àpéro

Ìwà mímọ́ túnmọ̀ sí nkàn wọ̀nyí;

**Ìrẹ̀lẹ̀,**
**Ìgbọràn,**
**Ìfẹ́,**
**Ìṣotítọ́,**
**Kíkó ènìyàn mọ́ra,**
**Títayọ,**
**Ìsìn,**
**jíjọ̀wọ́ ara**

# ORÍ ÌKARÙNDÍNLỌ́GBỌ̀N

## ÌRÀNLỌ́WỌ́ NÍ ÀSÌKÒ ÀÌNÍ



## Ṣe Àṣàrò

**ÌRẸ̀WẸ̀SÌ ỌKÀN**

**Aisaya 40:10**
Ẹ wò ó! OLÚWA Ọlọ́run ń bọ̀ pẹlu agbára ipá rẹ̀ ni yóo fi máa ṣe àkóso. Ẹ wò ó! Èrè rẹ̀ ń bẹ lọ́wọ́ rẹ̀, ẹ̀san rẹ̀ sì ń bẹ níwájú rẹ̀.

**Orin Dafidi 34:4**
Mo ké pe OLÚWA, ó sì dá mi lóhùn, ó sì gbà mí lọ́wọ́ gbogbo ohun tí ń bà mí lẹ́rù.

**Johanu 16:13**
Ṣugbọn nígbà tí Ẹ̀mí òtítọ́ tí mo wí bá dé, yóo tọ yín sí ọ̀nà òtítọ́ gbogbo. Nítorí kò ní sọ ọ̀rọ̀ ti ara rẹ̀; gbogbo ohun tí ó bá gbọ́ ni yóo sọ. Yóo sọ àwọn ohun tí yóo ṣẹlẹ̀ fun yín.

**Josua 1:9**
Ranti pé mo ti pàṣẹ fún ọ pé kí o múra, kí o sì ṣe ọkàn gírí. Má bẹ̀rù, má sì jẹ́ kí ìrẹ̀wẹ̀sì bá ọkàn rẹ, nítorí pé èmi, OLÚWA Ọlọ́run rẹ wà pẹlu rẹ níbikíbi tí o bá ń lọ".

**Kronika keji 20:15**
Ó ní, "Ẹ fetí sí mi, gbogbo ẹ̀yin ará Juda ati ti Jerusalẹmu ati ọba Jehoṣafati, OLÚWA Ọlọ́run ní kí ẹ má fòyà, kí ẹ má sì jẹ́ kí ọkàn yín rẹ̀wẹ̀sì nítorí ogun ńlá yìí; nítorí pé kì í ṣe ẹ̀yin ni ẹ ó ja ogun ńlá yìí, Ọlọ́run ni.

**Orin Dafidi 43:5**
Ìwọ ọkàn mi, kí ló dé tí o fi rẹ̀wẹ̀sì? Kí ló dé tí ara rẹ kò fi balẹ̀ ninu mi? Gbẹ́kẹ̀ rẹ lé Ọlọ́run; nítorí pé n óo tún yìn ín, olùrànlọ́wọ́ mi ati Ọlọ́run mi.

**Matiu 11:28**
"Ẹ wá sọ́dọ̀ mi gbogbo ẹ̀yin tí ń ṣe làálàá, tí ẹrù ìpọ́njú ń wọ̀ lọ́rùn. Èmi yóo fun yín ní ìsinmi.

**Korinti Keji 4:8-9**
A ní oríṣìíríṣìí ìṣòro, ṣugbọn wọn kò wó wa mọ́lẹ̀; ọkàn wa ń dààmú, ṣugbọn a kò ṣe aláìní ìrètí. Àwọn eniyan ń ṣe inúnibíni sí wa, ṣugbọn Ọlọ́run kò fi wá sílẹ̀. Wọ́n gbé wa ṣubú, ṣugbọn wọn kò lè pa wá.

**Aisaya 40:31**
Ṣugbọn àwọn tí ó bá dúró de OLÚWA yóo máa gba agbára kún agbára. Wọn óo máa fi ìyẹ́ fò lọ sókè bí ẹyẹ idì. Wọn óo máa sáré, agara kò ní dá wọn; wọn óo máa rìn, kò sì ní rẹ̀ wọ́n.

# ÌPÒRURÙỌKÀN /ÌBÀNÚJẸ

**Orin Dafidi 42:11**
Ìwọ ọkàn mi, kí ló dé tí o fi ń rẹ̀wẹ̀sì? Kí ló dé tí ara rẹ kò fi balẹ̀ ninu mi? Gbẹ́kẹ̀ rẹ lé Ọlọ́run; nítorí pé n óo tún yìn ín, olùrànlọ́wọ́ mi ati Ọlọ́run mi.

**Filipi 4:6**
Ẹ má ṣe jẹ́ kí ohunkohun dààmú yín, ṣugbọn ninu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ yín, ẹ máa fi àwọn ìbéèrè yín siwaju Ọlọ́run pẹlu ọpẹ́.

**Matiu 6:25-31**
"Nítorí èyí ni mo ṣe sọ fun yín pé kí ẹ má máa ṣe àníyàn nípa ẹ̀mí yín, pé kí ni ẹ óo jẹ tabi kí ni ẹ óo mu, tabi pé kí ni ẹ óo fi bora. Mo ṣebí ẹ̀mí yín ju oúnjẹ lọ; ati pé ara yín ju aṣọ lọ. Ẹ wo àwọn ẹyẹ lójú ọ̀run. Wọn kì í fúnrúgbìn, wọn kì í kórè, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í kó nǹkan oko jọ sinu abà. Sibẹ Baba yín tí ń bẹ ní ọ̀run ń bó wọn. Mo ṣebí ẹ̀yin sàn ju àwọn ẹyẹ lọ! Ta ni ninu yín tí ó lè ṣe àníyàn títí tí ó lè fi kún ọjọ́ ayé rẹ̀? "Kí ní ṣe tí ẹ̀ ń ṣe àníyàn nípa ohun tí ẹ óo wọ̀? Ẹ ṣe akiyesi àwọn òdòdó inú igbó bí wọ́n ti ń dàgbà. Wọn kì í ṣiṣẹ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í rànwú. Sibẹ mo sọ fun yín pé Solomoni pàápàá ninu gbogbo ìgúnwà rè kò lè wọ aṣọ tí ó lẹ́wà bíi ti ọ̀kan ninu àwọn òdòdó yìí. Njẹ́ bí Ọlọ́run bá wọ koríko ìgbẹ́ láṣọ báyìí, koríko tí yóo wà lónìí, tí a óo fi dáná lọ́la, mélòó-mélòó ni yóo wọ̀ yín láṣọ, ẹ̀yin onigbagbọ kékeré? "Nítorí náà, ẹ má ṣe àníyàn pé kí ni ẹ óo jẹ? Tabi, kí ni ẹ óo mu? Tabi kí ni ẹ óo fi bora

**Matiu 6:34**
Nítorí náà, ẹ má ṣe àníyàn nípa nnkan ti ọ̀la; nítorí ọ̀la ni nnkan ti ọ̀la wà fún; wahala ti òní nìkan ti tó fún òní láì fi ti ọ̀la kún un.

**Orin Dafidi 3:3**
Ṣugbọn ìwọ OLÚWA ni ààbò mi, ògo mi, ati ẹni tí ó fún mi ní ìgboyà.

**Orin Dafidi 34:18**
OLÚWA wà nítòsí àwọn tí ọkàn wọn bàjẹ́, a sì máa gba àwọn oníròbìnújẹ́ ọkàn là

**Romu 8:38-39**
Nítorí ó dá mi lójú pé, kò sí ohunkohun–ìbáà ṣe ikú tabi ìyè, ìbáà ṣe àwọn angẹli tabi àwọn irúnmọlẹ̀, tabi àwọn ohun ayé òde òní tabi àwọn ti ayé tí ó ń bọ̀, yálà àwọn àlùjọ̀nnú ojú-ọ̀run tabi àwọn ẹbọra inú ilẹ̀; lọ́rọ̀ kan, kò sí

ẹ̀dá náà tí ó lè yà wá kúrò ninu ìfé ̣tí Ọlọ́run ní sí wa nípasẹ̀ Kristi Jesu Olúwa wa.

**Korinti Keji 10:3-4**
Nítorí à ń gbé ìgbé-ayé wa ninu àìlera ti ara, ṣugbọn a kò jagun gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ń wá ire ara wa, nítorí àwọn ohun-ìjà wa kì í ṣe ti ayé, agbára Ọlọ́run ni, tí a lè fi wó ìlú olódi. À ń bi gbogbo iyàn jíjà lórí èké ṣubú,

**Peteru Kinni 5:7**
Ẹ kó gbogbo ìpayà yín tò ̣ọ́ lọ, nítorí ìtójụ́ yín jẹ́ ẹ́ lógún.

**Orin Dafidi 30:11**
O ti bá mi sọ òf̣ò ̣mi di ijó, o ti bọ́ aṣọ òf̣ò ̣kúrò lára mi, o sì ti dì mí ní àmùrè ayọ̀,

**Orin Dafidi 40:1-3**
**Sùúrù ni mo fi dúró de OLÚ**WA, ó dẹ etí sí mi, ó sì gbó ̣igbe mi. Ó fà mí jáde láti inú ògbun ìparun, láti inú kòtò tí ó kún fún ẹrọ̀f̣ọ̀; ó gbé mi kalẹ̀ lórí àpáta, ó sì fi ẹsẹ̀ mi tẹlẹ̀. Ó fi orin titun sí mi lẹ́nu, àní, orin ìyìn sí Ọlọ́run wa. Ọ̀pọ̀ ̣yóo rí i, ẹ̀rù óo bà wọ́n, wọn óo sì gbékẹ̀lé OLÚWA.

**Ịwe Òwe 12:25**
Ọp̣ò ̣ ìpayà máa ń kó ìrèẉẹ̀sì bá eniyan, ṣugbọn òṛò ̣rere a máa mú inú eniyan dùn.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

**Nígbàtí o bá ní ìjákulè ìrèẉèṣì ọkan**

- Mo gbé òdodo Ọlọ́run wọ̀ mo si pàṣẹ pé ìrànlọ́wọ́ mí ti ọwọ Olúwa wá tí óda ọ̀run àti ayé. Ọ̀run mi kì yóo wọ̀ mọ́, àti òṣùpá mi kì yóò fàsẹ́yìn; nítorí Olúwa yíò jẹ́ ìmọ́lẹ̀ mi.
- Mò ńtẹ̀síwájú mosì dúró ṣinṣin nítorí Olúwa fi ọkàn mi balẹ̀ ní gbogbo ọ̀nà. Mo ńtẹ̀síwájú nínú ore-ọ̀fẹ́ mo sì, pàṣẹ pé orúkọ Olúwa yíò di àyìnlógo.
- Mo pàṣẹ pé gbogbo àfoníforì yíò di gbígbé sókè àti gbogbo ọ̀nà wíwọ́ yí ò di títò àti gbogbo ọ̀nà dídàrú yíò di títò àti wípé ògo Olúwa yíò farahàn láyémi, nígbeyàwó mi àti nílé mi.
- Mo jẹ́wọ́ pe mi ò ní rí ìfàsẹ́yìn àti ìjákulẹ̀ lórí ìṣoro ayé mi, ṣùgbọ́n nínú ohun gbogbo, n ó fi ọpẹ́ fún

Ọlọ́run fún ojú rere àti àànú rẹ tó dúró láíláí.

- Mo gba ìfọ̀kànbalẹ̀ rẹ ní gbogbo ọ̀nà. Bímo ṣé ǹtọ́ ọ wá pẹ̀lú àìní àti ẹ̀rù mi, mo mọ̀ wípé ìfọ̀kànbalẹ̀ tí ẹnikẹ́ni kòle fún mi láfi lémi lọ́wọ́ ní orúkọ Jésù.

- Mo fi ọpẹ́ àti ìyìn fún Ọlọ́run nítorí ìfẹ́ rẹ àti àánú rẹ. Kíyèsi, ẹni tí ó ń pa mímọ́ kì yóò tòògbé bẹ́ẹ̀nì kì yóò sùn.

- Mo pàṣẹ wípé ìwọ yóò yímiká pẹ̀lú ojú rere bíi àbò. Rànmílọ́wọ́ Olúwa láti tẹ̀lé ìlànà rẹ ní ojoojúmọ́ ìgbé ayé ọmọ lẹ́yìn Krístì ti yò múmi dàgbà nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́ tí o fi lémi lọ́wọ́ nípa ẹ̀mí rẹ ní orúkọ Jésù.

- Èmí yó dúró de Olúwa nítorí ó ti ró ọkàn mi lágbára láti ní ìgboyà pípé.

- Mo pàṣẹ wípé kí Olúwa tan ìmọ́lẹ̀ sí òkùnkùn ayé mi kí o sì darí mi nínú gbogbo ìṣòro àti ìlàkọjá tí mò ń dojú kọ

- Mo pàṣẹ wípé kí ẹ̀mí rẹ̀ fimí lọ́kànbalẹ̀ nínú ìpọ́njú àti nípa ẹ̀mí rẹ, ìjà dópin. Kò sí òkè tí ó ga tí a kò ní sọ di pẹ̀tẹ́lẹ̀ àti wípé kò sí àfonífojì tí ó lọ̀ọ́lẹ̀ tí kòle di gbígbé sókè. Orúkọ Olúwa yíò di àyìn lógo nínú gbogbo ìṣòro tí mò ń dojú kọ.

- Ọlọ́run olóre ọ̀fẹ́, kòsí àìṣeéṣé pẹ̀lú rẹ. Apàṣẹ wípé ọwọ́ Olúwa tí ó n gbáni yío darí wa, yíò sì dáàbò bò wá.

## ÌJÁKULẸ̀ TÀBÍ ÌRÒNÚ

- ́Mo kọ̀ láti gbà kí ìṣòro àti ohun tí ó yímiká sọ àwọn ọ̀rọ̀ odì ní agbègbè mi, nítorí Ọlọ́run mi yío ba gbogbo àìní mi pàdé.

- Mo pàṣẹ wípé tẹ̀rùtẹrù àti tí ìyánú tí ìyanu ní adá mi. Mo ṣe iyebíye jùlọ lọ́wọ́ Ọlọ́run ju àwọn ẹyẹ ojú ọ̀run tí Ọlọ́run fún lóúnjẹ lójoojúmọ́.

- Olúwa, èmí tọ̀ ọ́ wá pẹ̀lú ìgboyà mo sì fi gbogbo ìṣòro mi sí abẹ́ ẹsẹ̀ rẹ. Mo sì pàṣẹ wípé gbogbo làálà mí ní ìwọ yóò fún ní ìsimi.

- Bàbá, mo fi ògo fún orúkọ rẹ nítorí tí ò n múmi rìn dédé nípa òtítọ́ rẹ àti ìfẹ́ rẹ àti àánú rẹ símì kòní dáwọ́ dúró.

- Mo kọ́ láti jẹ́kí ìdojúkọ ọ̀tá borí mi nítorí ìdúró ṣinṣin mi nínú

òtítọ́ àti ìlérí mí nínú Olúwa.ra fún
ọmọ yín, mélòó-mélòó ni Baba yín
tí ń bẹ ní ọ̀run yóo fi ohun rere
fún àwọn tí ó bá bèèrè lọ́dọ̀.

# ORÍ ÌKẸRÌNDÍNLỌ́GBỌ̀N

## ẸNÌKEJÌ ẸNI NÍ TI Ọ̀RỌ̀ ÌDÍLE



## Ṣe Àṣàrò

**Matiu 7:7-11**
"Ẹ bèèrè, a óo sì fi fun yín. Ẹ wá kiri, ẹ óo sì rí. Ẹ kanlẹ̀kùn, a óo sì ṣí i fun yín. Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá bèèrè ni ó ń rí gbà; ẹnikẹ́ni tí ó bá ń wá nnkan kiri ni ó ń rí i; ẹnikẹ́ni tí ó bá ń kanlẹ̀kùn ni à ń ṣí i sílẹ̀ fún. Ta ni ninu yín, tí ọmọ rẹ̀ bá bèèrè àkàrà, tí ó jẹ́ fún un ní òkúta? Tabi tí ó bà bèèrè ẹja, tí ó jẹ́ fún un ní ejò? Njẹ́ bí ẹ̀yin tí ẹ burú báyìí bá mọ̀ bí a tií fi ohun tí ó dára fún ọmọ yín, mélòó-mélòó ni Baba yín tí ń bẹ ní ọ̀run yóo fi ohun rere fún àwọn tí ó bá bèèrè lọ́dọ̀ rẹ̀.

**Orin Dafidi 37:5**
Fi ọ̀nà rẹ lé OLÚWA lọ́wọ́; gbẹ́kẹ̀lé e, yóo sì ṣe ohun tí ó yẹ

**Iwe Òwe 10:24b**
Ohun tí olódodo ń fẹ́ ni yóo sì rí gbà.

**Maku 11:24**
Nítorí èyí, mo fẹ́ kí ẹ mọ̀ pé, ohun gbogbo tí ẹ bá bèèrè ninu adura, ẹ gbàgbọ́ pé ẹ ti rí i gbà, bẹ́ẹ̀ ni yóo rí fun yín.

**Jenesisi 2:24**
Ìdí nìyí tí ọkunrin yóo ṣe fi baba ati ìyá rẹ̀ sílẹ̀, tí yóo sì faramọ́ aya rẹ̀, àwọn mejeeji yóo sì di ara kan ṣoṣo.

**Jenesisi 2:23**
Ọkunrin náà bá wí pé, "Mo ṣẹ̀ṣẹ̀ rí ẹni tí ó dàbí mi, ẹni tí a mú jáde láti inú egungun ati ẹran ara mi; obinrin ni yóo máa jẹ́, nítorí pé láti ara ọkunrin ni a ti mú un jáde."

**Iwe Òwe 18:22**
Ẹni tí ó bá rí aya fẹ́ rí ohun rere, ó sì rí ojurere lọ́dọ̀ OLÚWA.

**Iwe Òwe 19:14**
A máa ń jogún ilé ati ọrọ̀ lọ́wọ́ baba ẹni, ṣugbọn OLÚWA níí fúnni ní aya rere.

**Àwon Oniwasu 4:9-11**
Eniyan meji sàn ju ẹnìkan ṣoṣo lọ, nítorí wọn yóo lè jọ ṣiṣẹ́, èrè wọn yóo sì pọ̀. Bí ọ̀kan bá ṣubú, ekeji yóo gbé e dìde. Ṣugbọn ẹni tí ó dá wà gbé! Nítorí nígbà tí ó bá ṣubú kò ní sí ẹni tí yóo gbé e dìde. Bẹ́ẹ̀ sì tún ni, bí eniyan meji bá sùn pọ̀, wọn yóo fi ooru mú ara wọn ṣugbọn báwo ni ẹnìkan ṣe lè fi ooru mú ara rẹ̀?

**Aisaya 62:4-5**
A kò ní pè ọ́ ní "Ẹni-tí-a-kọ̀-sílẹ̀" mọ́, bẹ́ẹ̀ ni a kò ní pe ilẹ̀ rẹ ní "Ahoro" mọ́, "Ẹni- OLÚWA -fẹ́" ni a óo máa pè ọ́, a óo máa pe ilẹ̀ rẹ ní "Ẹni-a-gbé-níyàwó." Nítorí pé OLÚWA nífẹ̀ẹ́ rẹ, ilẹ̀ rẹ yóo sì dàbí iyawo lójú rẹ̀. Bí

ọdọmọkunrin tií nífẹ̀ẹ́ wundia, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọkunrin rẹ yóo nífẹ̀ẹ́ rẹ. Bí inú ọkọ iyawo tuntun tíí dùn nítorí iyawo rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni inú Ọlọ́run rẹ yóo dùn nítorí rẹ.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- ´Ọṣé o Jésù nítorí o ti sọ nínú ọ̀rọ̀ rẹ wípe kòsí ẹni tí yóò yàgàn. Mo gba ìlérí rẹ fún ayé mi. Mo pàṣẹ wípé yío ṣe àwárí mi láwùjọ àrín ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ní orúkọ Jésù.

- Ọṣé fún ìlérí rẹ tó sọ wípé ohunkóhun tí mo bá bèèrè ní orúkọ ré nígbà tí mo bá gbàdúrà a ó fi fun mi níwọ̀n ìgbà tí mo bá gbàgbọ́. Mo gbàdúrà wípé ìfẹ́ rẹ fún mi láti ní ẹnìkejì yío wá sí ìmúṣẹ lórí àwọn ọmọ mi àti àwọn ọmọ ọmọ mi.

- Olúwa, ọ̀rọ̀ rẹ sọ wípé ìpòngbẹ ọkàn àwọn olódodo lẹ o fifún wọn, nítorínà bí mo ṣe ń fi gbogbo ìdílé mì tí wọ́n wojú rẹ fún ẹnìkejì, mo mọ̀ wípé ìwọ kì yóò jáwọn kulẹ̀ àti wípé ìfẹ́ ọkàn wọ́n lẹ́ o fifún wọn gẹ́gẹ́ bí ìfẹ́ rẹ.

  Bàbá mi àti Ọlọ́run mi, ọ̀rọ̀ rẹ wípé ohun gbogbo dáradára jẹ́ tí àwọn tó bá ń rìn déédé. Mo gbàdúrà wípé ìfẹ́ rẹ fún ẹnìkejì mi kòní dí ìdadúró àti wípé mí ò ní kánjú.

Ọmọ májẹ̀mú nimí, mosì pàṣẹ wípé Ọlọ́run á pèsè fún mi ẹni tí óti yàn fúnmi nínú ògo rẹ̀.

Olúwa, nípa ẹnìkejì mi, ọjọ́ iwájú, mo pàṣẹ wípé èmi yóò rí ojú rere nítorípé ọkàn mi sinmi lé ọ. Ìwọ yio darí mi kí o sì tọ́mi nínú àtiyàn mi.

**Àwàdà**

## Bí aṣe lè dé Ọ̀run

Olùkọ kan bèèrè lọ́wọ́ àwọn ọmọ nínú ilé ẹ̀kó ọjọ́ ̀isinmi wípé bí mo bá ta ilé àti ọkọ̀ mi, tí mo ní ibùdókọ̀ ńlá tí mo tá tí mo sì fi gbogbo owo mí fún ̀ijọ Ọlọ́run, ǹjẹ́ ń ma dé ọ̀run bí?' 'Rárá o' gbọ́ àwọn ọmọ dáhùn. 'Tí mo bá ntun ̀ijọ Ọlọ́run ṣe lójoojúmọ́, tí mo sì tún ọgbà ṣe àti ohun gbogbo tí ó wà nínú rẹ̀ dáradára, ǹjẹ n ó dé ọ̀run bí?' Síbẹ̀, ̀idáhùn wọn sìjẹ́ 'rárá' 'ṣùgbọ́n, olùkọ́ náà tẹ̀síwájú, 'báwo wá ni mo ṣe lè dé ọ̀run?'
Ní ẹ̀yin yàrá, ọmọkùnrin kékeré tó jẹ́ ọmọ ọdún máàrún pariwo,
"ẹ ò ní láti kú"

# ORÍ ÌKẸTÀDÍNLỌ́GBỌ̀N

## ÀṢEYỌRÍ NÍNÚ ÈTÒ ÌDÍLE



## Ṣe Àṣàrò

**Ìwé Òwe 31:10-19**
Ta ló lè rí iyawo tí ó ní ìwà rere fé? Ó ṣòwọ́n ju ohun ọ̀ṣọ́ olówó iyebíye lọ. Ọkọ rẹ̀ yóo fi tọkàntọkàn gbẹ́kẹ̀lé e, kò sì ní ṣaláì ní ohunkohun. Rere ni obinrin náà máa ń ṣe fún un kò ní ṣe é níbi, ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ̀. A máa lọ wá irun aguntan ati òwú ìhunṣọ, a sì máa fi tayọ̀tayọ̀ hun aṣọ. Obinrin náà dàbí ọkọ̀ ojú omi oníṣòwò, tí ó ń mú oúnjẹ wálé láti ọ̀nà jíjìn réré. Ìdájí níí tií jí láti wá oúnjẹ fún ìdílé rẹ̀, ati láti yan iṣẹ́ fún àwọn iranṣẹbinrin rẹ̀. Bí ó bá rí ilẹ̀ oko, a yẹ̀ ẹ́ wò, a sì rà á, a sì fi èrè iṣ ẹ́ rẹ̀ gbin ọgbà àjàrà. A fi agbára fún ọ̀já mọ́nú, a sì tẹpá mọ́ṣẹ́. A máa mójútó ọjà tí ó ń tà, fìtílà rẹ̀ kì í sì í kú lóru. Ó fi ọwọ́ lé kẹ̀kẹ́ òwú, ó sì ń ran òwú.

**Jenesisi 2:18**
Lẹ́yìn náà OLUWA Ọlọ́run sọ pé, "Kò dára kí ọkunrin náà nìkan dá wà, n óo ṣe olùrànlọ́wọ́ kan fún un, tí yóo dàbí rẹ̀."

**Orin Dafidi 1:3**
Yóo dàbí igi tí a gbìn sí etí odò tí ń so ní àkókò tí ó yẹ, tí ewé rẹ̀ kì í rẹ̀. Gbogbo ohun tí ó bá dáwọ́lé níí máa yọrí sí rere.

**Orin Dafidi 128:1-6**
Ayọ̀ ń bẹ fún ẹni tí ó bèrù OLÚWA, tí ó sì ń tẹ̀lé ìlànà rẹ̀. O óo jèrè iṣẹ́ ọwọ́ rẹ, ayọ̀ ń bẹ fún ọ, yóo sì dára fún ọ. Aya rẹ yóo dàbí àjàrà eléso pupọ ninu ilé rẹ; bí ọmọ tií yí igi olifi ká, ni àwọn ọmọ rẹ yóo yí tabili oúnjẹ rẹ ká. Wò ó, béè ni OLÚWA yóo ké ẹni tí ó bẹ̀rù rẹ̀. Kí OLÚWA bukun ọ láti Sioni! Kí o máa rí ire Jerusalẹmu ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ. Kí o máa rí arọmọdọmọ rẹ. Kí alaafia máa wà ní Israẹli.

**Efesu 5:22-33**
Ẹ̀yin aya, ẹ máa tẹríba fún àwọn ọkọ yín gégé bí Olúwa. Nítorí ọkọ ni olórí aya gẹ́gẹ́ bí Kristi ti jé olórí ìjọ. Kristi sì ni Olùgbàlà ara rẹ̀ tíí ṣe ìjọ. Bí ìjọ ti ń bọ̀wọ̀ fún Kristi, béè ni kí àwọn aya máa ṣe sí àwọn ọkọ wọn ninu ohun gbogbo. Ẹ̀yin ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́ bí Kristi ti fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fi ara rẹ̀ fún un. Ó ṣe èyí láti yà á sọ́tọ̀. Ó sọ ọ̀ di mímọ́ lẹ́yìn tí ó ti fi omi wẹ̀ ẹ́ nípa ọ̀rọ̀ iwaasu. Kí ó lè mú ìjọ wá sọ́dọ̀ ara rẹ̀ bí ìjọ tí ó lọ́lá, tí kò ní àléébù kankan, tabi kí ó hunjọ, tabi kí ó ní nnkan àbùkù kankan, ṣugbọn kí ó lè jé ìjọ mímọ́ tí kò ní èérí. Béè ni ó yẹ kí àwọn ọkọ fẹ́ràn àwọn aya wọn, bí wọn ti fẹ́ràn ara tiwọn. Ẹni tí ó bá fẹ́ràn aya rẹ̀, òun tìkararẹ̀ ni ó fẹ́ràn. Nítorí kò sí ẹnìkan tí ó kórìíra ara rẹ̀. Ǹṣe ni eniyan máa ń

tọ́jú ara rẹ̀, tí ó sì máa ń kẹ́ ẹ. Béẹ̀ ni Kristi ń ṣe sí ìjọ. Nítorí ẹ̀yà ara Kristi ni a jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí Ìwé Mímọ́ ti sọ, pé, "Nítorí náà ni ọkunrin yóo ṣe fi baba ati ìyá rẹ̀ sílẹ̀, tí yóo darapọ̀ pẹlu aya rẹ̀, àwọn mejeeji yóo wá di ara kan." Àṣírí ńlá ni èyí. Mò ń sọ nípa ipò tí Kristi wà sí ìjọ. Àkàwé yìí ba yín mu. Ẹnìkọ̀ọ̀kan yín níláti fẹ́ràn aya rẹ̀ bí òun tìkararẹ̀. Aya sì níláti b ọ̀ wọ̀ fún ọkọ rẹ̀.

**Aisaya 34:16**
Ẹ lọ wá inú ìwé OLÚWA, kí ẹ ka ohun tí ó wà níbẹ̀. Kò sí ọ̀kan àwọn wọnyi tí kò ní sí níbẹ̀, kò sí èyí tí kò ní ní ẹnìkejì. Nítorí OLÚWA ni ó pàṣẹ bẹ́ẹ̀, ẹ̀mí rẹ̀ ni ó sì kó wọn jọ.

**Iwe Òwe 5:18-19**
Jẹ́ kí orísun rẹ ní ibukun, kí inú rẹ sì máa dùn sí iyawo tí o fi àárọ̀ gbé. Olólùfẹ́ rẹ tí ó dára bí abọ egbin. Jẹ́ kí ẹwù rẹ̀ máa mú inú rẹ dùn nígbà gbogbo, kí ìfẹ́ rẹ̀ máa mú orí rẹ yá nígbàkúùgbà.



## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo fi ìpìlẹ̀ ìdílé mi lé ọ lọ́wọ́ mo sì pàṣẹ pé ilé-ẹ̀kọ́ ìgbeyàwó tí ìwọ nìkan dá nipa ẹ̀mí rẹ ní ìwọ yóò bẹ̀wo nípa iná Ẹ̀mí mímọ́ rẹ.

- Gbogbo ìgbìmọ̀ òkùnkùn ti o lòdì sí ìgbeyàwo mi kì yóò dúró.

- Mo pá láṣẹ mo sì tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ wípé gbogbo ìdílé yíò fi ìbùkún Ọlọ́run àti ìrànwọ́ rẹ hàn.

- Jésù ti kó gbogbo àwọn àrùn, ósì gbé ẹrù mi sókè, mo sì jẹ́wọ́ wípé ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ yío farahàn nínú ìgbeyàwó mi. Gbogbo ẹ̀mí àìgbọràn ni a bàjẹ́ asì tíi jáde nípa Ẹ̀mí mímọ́ Ọlọ́run.

- Oṣé Jésù Olúwa wa, nítorí tí ó tí sọ nínú ọ̀rọ̀ rẹ́ wípé kò ní sí àjàkálẹ̀ àrùn nípa ìrìn àjò ìgbéyàwó aláìléso ní ààrín wa. Nígbànà ní mo sọ ọ̀rọ̀ aṣẹ̀ gun lórí gbogbo ilé tí ó ń dàrú mó sì tún pàṣẹ àlááfíà.

- Mo jẹ́wọ́ wípé nítòótọ́ mo ṣe iyebíye, mo jẹ́ ìbùkún fún ọkọ mi èmi yóò si ṣé oore fún lójojúmọ́. Olúwa yóò bùkún iṣẹ́ ọwọ́ mi yì ó sì tún só agbára mi dí ọ̀tun.

- Ọsé Olúwa tí ó fúnmi ní ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ sí ọkọ/aya mi. Mo gbàdúra wípé ọkọ mi tàbi aya mi yóò fi ìfẹ́ Ọlọ́run hàn sí mi nínú ohun gbogbo. Mo gbàdúra wípé Krístì yío jẹ àpẹrẹ fún wa bí à ṣe n palẹ̀mọ́ ara wa láti wá síwájú Olúwa láì lẹ́gàn tàbí àbàwọ́n.

# ORÍ ÌKEJÌDÍNLỌ́GBỌ̀N

## ÌSÈSO



## Ṣe Àṣàrò

**Heberu 11:11-12**

Nípa igbagbọ, Abrahamu ní agbára láti bímọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Sara yàgàn, ó sì ti dàgbà kọjá ọmọ bíbí, Abrahamu gbà pé ẹni tí ó ṣèlérí tó gbẹ́kẹ̀lé. Nítorí èyí, láti ọ̀dọ̀ ẹyọ ọkunrin kan, tí ó ti dàgbà títí, tí ó ti kú sára, ni ọpọlọpọ ọmọ ti jáde, wọ́n pọ̀ bíi ìràwọ̀ ojú ọ̀run, ati bíi iyanrìn etí òkun.

**Jenesisi 25:21**
Isaaki gbadura sí OLÚWA fún aya rẹ̀ tí ó yàgàn, OLÚWA gbọ́ adura rẹ̀, Rebeka aya rẹ̀ sì lóyún.

**Orin Dafidi 113:9**
Ó sọ àgàn di ọlọ́mọ, ó sọ ọ́ di abiyamọ onínú dídùn. Ẹ máa yin OLÚWA

**Orin Dafidi 127:3**
Wò ó! Ẹ̀bùn OLÚWA ni ọmọ; òun ní fi oyún inú ṣìkẹ́ eniyan.

**Samueli Kinni 2:21**
OLÚWA bukun Hana: ọmọkunrin mẹta, ati ọmọbinrin meji ni ó tún bí lẹ́yìn Samuẹli. Samuẹli sì ń dàgbà níbi tí ó ti ń ṣe iṣẹ́ iranṣẹ sin OLÚWA.

**Jenesisi 30:22**
Lẹ́yìn náà ni Ọlọ́run ranti Rakẹli, ó gbọ́ ẹ̀bẹ̀ rẹ̀, ó sì ṣí inú rẹ̀.

**Luku 1:36**
Ati pé Elisabẹti, ìbátan rẹ náà ti lóyún ọmọkunrin kan ní ìgbà ogbó rẹ̀. Ẹni tí wọ́n ti ń pè ní àgàn rí sì ti di aboyún oṣù mẹfa.

**Diutaronomi 7:14**

OLÚWA yóo bukun yín ju gbogbo àwọn eniyan yòókù lọ; kò ní sí ọkunrin kan tabi obinrin kan tí yóo yàgàn láàrin yín, tabi láàrin àwọn ẹran ọ̀sìn yín.

**Orin Dafidi 128:3**

Aya rẹ yóo dàbí àjàrà eléso pupọ ninu ilé rẹ; bí ọmọ tií yí igi olifi ká, ni àwọn ọmọ rẹ yóo yí tabili oúnjẹ rẹ ká.

**Ekisodu 23:26**

Ẹyọ oyún kan kò ní bàjẹ́ lára àwọn obinrin yín, bẹ́ẹ̀ ni ẹyọ obinrin kan kò ní yàgàn ninu gbogbo ilẹ̀ yín. N óo jẹ́ kí ẹ gbó, kí ẹ sì tọ́.

**Aisaya 66:9**

Ṣé mo lè jẹ́ kí eniyan máa rọbí, kí n má jẹ́ kí ó bímọ bí? Èmi OLÚWA,

tí mò ń mú kí eniyan máa bímọ, ṣé, mo jẹ́ sé eniyan ninu?”

**Jenesisi 1:28**

Ó súre fún wọn, ó ní, “Ẹ máa bímọ lémọ, kí ẹ máa pọ̀ sí i, kí ẹ kún gbogbo ayé. Kí ayé wà ní ìkáwọ́ yín, kí ẹ ní àṣẹ lórí àwọn ẹja inú omi, lórí ẹyẹ ojú ọ̀run, ati lórí gbogbo ẹ̀dá alààyè tí ń rìn káàkiri lórí ilẹ̀ ayé.”

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo jẹ́wọ́ wípé mo sò èso rere ní gbogbo ọjọ ayé mi. Mí òní pàdánù ìṣe lọ́ṣọ̀ mi nìtorí mo ti gbilẹ̀ asì ti gbìn mí sínú Ọlọ́run, nítorína moṣe àṣeyorí nínú ohun gbogbo.
- Mo bẹ̀rù, mo sì tún ńrìn nínú ìlànà Ọlọ́run, nítorínà ati bùkún mi jú ìwọ̀n lọ. Èmi yóò jẹ èrè iṣẹ́ ọwọ mi mo sì jẹ́wọ́ wípé yóò dára fúnmi. Mo pe àwọn èso mi kí wọ́n jáde wá nínú ìran yìi àti èyí tí ńbọ̀.
- Olúwa mo gbàdúrà fún ìso èso nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́ tí o gbé lémi lọ́wọ́ mo sì tún jẹ́wọ́ wípé iṣẹ́ àti ìrúbọ tí ó ṣe lórí àgbelébù ní kálfárì yíò ṣiṣẹ́ fún mi àti ìdílé mi.
- Modúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún ogún rere lọ́pọ̀lọpọ̀ tí o fúnmi ati ìran mi. Mo gba gbogbo ilẹ̀ tí o fúnmi mo sì ńrì nínú òmìnira jákèjádò àgbáyé.
- Mo jẹ́wọ́ wípé àwọn ọmọ tí Ọlọ́run fifún mi wọ́n o pọ̀ ní orílẹ̀ ayé wọn o sì di alábùkún fún nínú Olúwa.
- Mo gbàdúrà wípé Ọlọ́run yíò tọ́mi, yíò sì darí mi ní gbogbo ọjọ́ ayé mi, yíò sì sọ́mi di ọ̀pọ̀lọpọ̀.
- Mo jẹ́ onínú dídùn ìyá àwọn ọmọ mí mo sì jẹ́wọ́ wipe kò sí ẹnikánkan tí yóò yàgàn nínú ilé wa.
- Bí mo ṣe ń ní ìpín nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, mo jẹ́wọ́ wípé èso inú mi ní afi fúnmi gẹ́gẹ́bí ẹ̀bùn.
- Olúwa, mo gbàdúrà fún gbogbo àwọn tí ó n wojú rẹ fún èso inú pé wọ́n o bí ọmọ ní àkókò tó yẹ, agbára Ọlọ́run yíò sì wá lórí wọn. Ọlọ́run yío mú gbogbo àwọn obìnrin tí kò bímọ láti gba ìbùkún wọn

## Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n

Fi ìgbẹ́kẹ̀lẹ́ rẹ sí inú Olúwa lâìṣe ninú àwọn ǹkan míràn bíi owó tàbí èǹìyàn.

## Àwàdà

**`Adìyẹ Kékere´**

Arábìnrin tí àńpe orúkọ rẹ̀ ní Freshman lọsí Ibùdo àwọn ẹlẹ́ran láti ra adìyẹ fún oúnjẹ ọjọ́ ìsinmi. Ẹlẹ́ran yẹ́n ní adìyẹ kékeré kan tó ṣẹ́kù. Ó fi sí orí ìwọ̀n. "Ìwọ̀n rẹ̀ jẹ́ póùndì mẹ́ta" arákùnrin yí dáhùn.

'Ìyẹn tí kéré jù; ṣé ẹkò ní òmíràn tí ó tóbi ni?' Arábìrin Freshman bèrè. Ẹlẹ́ran yi díbọ́n láti fi ọ̀rọ̀ bóó mọ́lẹ̀, ó sì tún gbé adìyẹ kánnà sí orí ìwọ̀n pẹ̀lú ọwọ́ o rẹ̀. Ó pe ìwọ̀n yẹn ní mẹ́ta àti àbọ̀.

Ìyẹn náà dára, arábìrin Freshman dáhùn, ósì wípé 'òhun yíò mu méjèèjì'

# ORÍ ÌKỌKÀNDÍNLÓGBỌ̀N

DÍDÚRÓ
DE ÌYANU



## Ṣe Àṣàrò

**Jeremaya 32:17**
'OLÚWA Ọlọ́run! Ìwọ tí o dá ọ̀run ati ayé pẹlu agbára ńlá ati ipá rẹ! Kò sí ohun tí ó ṣòro fún ọ,

**Luku 18:27**
Ó dáhùn pé, "Ohun tí kò ṣeéṣe fún eniyan, ó ṣeéṣe fún Ọlọ́run."

**Efesu 3:20-21**
Ògo ni fún ẹni tí ó lè ṣe ju gbogbo nnkan tí à ń bèèrè, ati ohun gbogbo tí a ní lọ́kàn lọ, gẹ́gẹ́ bí agbára rẹ̀ tí ń ṣiṣẹ́ ninu wa. Kí ògo yìí wà fún un ninu ìjọ ati ninu Kristi Jesu láti ìrandíran títí laelae. Amin.

**Aisaya 30:18**
Nítorí náà 'OLÚWA ń dúró dè yín, ó ti ṣetán láti ṣàánú yín. Yóo dìde, yóo sì ràn yín lọ́wọ́. Nítorí 'Ọlọ́run Olódodo ni 'OLÚWA.Orin

**Dafidi 27:14**
Dúró de 'OLÚWA, ṣe bí akin, kí o sì mú ọkàn gírí, àní, dúró de 'OLÚWA.

**Romu 8:28**
Àwa mọ̀ dájú pé 'Ọlọ́run a máa mú kí ohun gbogbo yọrí sí rere fún àwọn tí ó fẹ́ràn rẹ̀, àwọn tí ó ti pè gẹ́gẹ́ bí ìpinnu rẹ̀ láti ayébáyé.

**Romu 10:11**
Ìwé Mímọ́ sọ pé, "Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà á gbọ́ tí ojú yóò tì."

**Mika 7:7**
Ṣugbọn ní tèmi, n óo máa wo ojú OLÚWA, n óo dúró de Ọlọ́run ìgbàlà mi; Ọlọ́run mi yóo sì gbọ́ tèmi.

**Aisaya 40:31**
Ṣugbọn àwọn tí ó bá dúró de OLÚWA yóo máa gba agbára kún agbára. Wọn óo máa fi ìyẹ́ fò lọ sókè bí ẹyẹ idì. Wọn óo máa sáré, agara kò ní dá wọn; wọn óo máa rìn, kò sì ní rẹ̀ wọ́n.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo wá síwájú ìtẹ́ rẹ mo sì jẹ́wọ́ wípé ọwọ rẹ̀ kò kéré ju láti gbani, bẹ́ẹ̀ sìni etí rẹ̀ kò wúwo jù láti gbọ́ wa. Mò ńwojú rẹ fún iṣẹ́ àmìn àti iṣẹ́ ìyanu rẹ ní gbogbo ọjọ aye mí.
.
- Èmi/àwa dúró lórí ọ̀rọ̀ ìlérí rẹ asì pàṣẹ wípé pẹ̀lú Olúwa, ohun gbogbo ní ṣíṣe. Èmi/àwa wípé ìyanu wá jáde nípa ẹ̀mí Ọlọ́run a sì gba àṣẹ lórí àrékérekè àti ìrìnsí ọ̀tá ní orúkọ Jésu.

- Bímo ṣe ń dúró de Ọlọ́run, agbára mi ni asọ dọ̀tun, èmi yóò fi ìyẹ́ gòkè bíi idì. Èmi yóò sáré kì yóò si rẹ̀mí. Gbogbo ìpòngbẹ ọkàn mi ní ìbámu pẹ̀lú Ọlọ́run ní afi fún mi.

- Olúwa, mo jẹ́wọ́ pé ìwọ dáabòbó mi osì jẹ́ kín dúró gẹ́gẹ́ bi aṣẹ́gun nípa nína ọwọ́ agbára rẹ.

- Èmí jẹ́ òdodo Olúwa, nítorí nàa akì yóò ṣími nídì nípa ọwọ́ ọ̀tá nítorí wípé dípò gbogbo ìtìjú mi ìwọ yóò fúnmi ní ọlá ní ìlọ́pọ méjì.

- Olúwa, módúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ nítorí wípé ọwọ́ ọ̀tá kònì borí ayé mi àti ayé gbogbo ìdílé mi.

- Mo jẹ́wọ́ wípé nínú àánú rẹ ní afi agbára fúnmi àti nínú àilera mi ní àti sọ́ agbára rẹ́ dọ̀tun. Mo borí gbogbo ẹmí ẹ̀rù mo sì sádi ọwọ́ ìgbàlà òdodo rẹ.

- Olúwa, mo fi ìgbẹ́kẹ̀lé mi sí inú rẹ́, mo sì jẹ́wọ́ wípé mo borí gbogbo àrékérekè àti ẹ̀rù tí sàtánì dá sínú mi. Ọ̀nà àwọn ọ̀tá kònì borí ayé wa.

- Bí aṣẹ́ ńdúró dè ọ́ Olúwa a ò ní ṣàárẹ̀, àti agbára wa ní a ó sọ dí ọ̀tun nípa ore-ọ̀fẹ́ àti àánú rẹ.

### Àwàdà

**Tani Ópèsè Kọfí?**

Àwọn tọkọtaya ní àríyànjiyàn lórí ẹni tí yóò pèsè kọfí, ìyàwó básọ wípé Bíbélì sọ wípé ọkùnrin ni kí ó máa pèsè kọfí, ọkọ náà sì bèrè ibi tí èyí wà nínú Bíbélì. Ìyàwó náà ṣì Bíbélì, o sì tọ́ka sí ìwé Hébérù ní èdè òyìnbó tí ó túmọ̀ sí wípé ọkùnrin ni ó ń pèsè.

# ORÍ ỌGBỌ̀N

## Ọ̀RỌ̀ ẸJỌ́



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 35:23-24**
Paradà, OLÚWA, jí gìrì sí ọ̀ràn mi, gbèjà mi, Ọlọ́run mi, ati OLÚWA mi! Dá mi láre, OLÚWA, Ọlọ́run mi, gẹ́gẹ́ bí òdodo rẹ; má sì jẹ́ kí wọ́n yọ̀ mí!

**Aisaya 50:7**
OLÚWA Ọlọ́run ń ràn mí lọ́wọ́, nítorí náà ojú kò tì mí; nítorí náà mo múra gírí, mo jẹ́ kí ojú mi le koko, mo sì mọ̀ pé ojú kò ní tì mí.

**Diutaronomi 3:22**
Ẹ kò gbọdọ̀ bẹ̀rù wọn rárá, nítorí pé OLÚWA Ọlọ́run yín ni ó ń jà fun yín.'

**Diutaronomi 20:4**
Nítorí OLÚWA Ọlọ́run yín ń ba yín lọ láti bá àwọn ọ̀tá yín jà, ati láti fun yín ní ìṣẹ́gun.'

**Diutaronomi 31:6**
Ẹ múra gírí, kí ẹ sì mú ọkàn gidigidi. Ẹ má bẹ̀rù rárá, ẹ má sì ṣe jẹ́ kí àyà fò yín; nítorí pé, OLÚWA Ọlọ́run yín ń ba yín lọ. Kò ní já yín kulẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni kò ní fi yín sílẹ̀

**Orin Dafidi 5:12**
Nítorí ìwọ OLÚWA a máa bukun àwọn olódodo; ò sì máa fi ojurere rẹ tí ó dàbí apata dáàbò bò wọ́n.

**Aisaya 54:17**
Kò sí ohun ìjà tí a ṣe láti fi bá ọ jà tí yóo lágbára lórí rẹ. Gbogbo ẹni tí ó bá bá ọ rojọ́ nílé ẹjọ́, ni o óo jàre wọn. Èyí ni ìpín àwọn iranṣẹ OLÚWA, ati ìdáláre wọn lọ́dọ̀ mi. Èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀."

**Orin Dafidi 17:1-2**
Gbọ́ tèmi OLÚWA, àre ni ẹjọ́ mi; fi ìtara gbọ́ igbe mi. Fetí sí adura mi nítorí kò sí ẹ̀tàn ní ẹnu mi. Jẹ́ kí ìdáláre mi ti ọ̀dọ̀ rẹ wá; kí o sì rí i pé ẹjọ́ mi tọ́.

**Aisaya 49:25**
OLÚWA ní: "Bí ó bá tilẹ̀ ṣeéṣe láti gba òǹdè lọ́wọ́ alágbára, tabi láti gba ìkógun lọ́wọ́ òkúrorò eniyan. N óo bá àwọn tí ó ń bá ọ jà jà, n óo sì gba àwọn ọmọ rẹ là.

**Ẹkún Jeremaya 3:58-59**
"OLÚWA, o ti gba ìjà mi jà, o ti ra ẹ̀mí mi pada. O ti rí nnkan burúkú tí wọ́n ṣe sí mi, OLÚWA, dá mi láre.

**Iwe Òwe 16:7**
Bí ọ̀nà eniyan bá tẹ́ OLÚWA lọ́rùn, a máa mú kí àwọn ọ̀tá rẹ̀ pàápàá bá a gbé pẹlu alaafia.

**Jeremaya 51:36**
Nítorí náà, OLÚWA sọ fún àwọn

ará Jerusalẹmu pé, "Ẹ wò ó, n óo gba ẹjọ́ yín rò, n óo sì ba yín gbèṣan. N óo jẹ́ kí omi òkun Babiloni gbẹ, n óo sì jẹ́ kí orísun odò rẹ̀ gbẹ.

**Orin Dafidi 7:10**
Ọlọrun ni aláàbò mi, òun níí gba àwọn ọlọ́kàn mímọ́ là.

**Aisaya 50:9**
Wò ó! OLÚWA Ọlọ́run ń ràn mí lọ́wọ́, ta ni yóo dá mi lẹ́bi? Gbogbo wọn ni yóo gbọ̀n dànù bí aṣọ, kòkòrò yóo sì jẹ wọ́n.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Mo pàṣẹ pé kòsí ẹni tí yóò le dúró níwájú mi ní gbogbo ọjọ́ ayé mi. Olúwa wà pẹ̀lú mi bí alágbára, yóò sì kọ́ ọwọ́ mi láti bá àwọn ọ̀tá mi jà. Ẹnikẹ́ni tí ó bá kórajọ nítorí mi lá o túká.

- Gbogbo ẹ̀sùn tí a bá fíkàn mí, iṣẹ́ mi àti ohun gbogbo tí mo bá dáwọ́lé ni a ó mú kúrò, gbogbo òkè ni a ó sìsọ di pẹ̀tẹ́lẹ̀, gbogbo ọ̀nà wíwọ́ mi ní a ó sìsọ di títọ́, a ó sì rí ògo Ọlọ́run nínú mi. Tí Ọlọ́run báwà fún wa, kòsí ẹni tí ó le ba ìpinu Ọlọ́run fún wa jẹ, torí Jésù tó jìnde tí san gbèsè náà.

- Olúwa, ọ̀rọ̀ rẹ sọ wípé ọkàn ọba wà lọ́wọ́ rẹ, torínà, mo gbàdúrà wípé kí ó gbémi sí ọwọ́ rẹ̀, kí ó sí fi mí polongo ohun tí o lẹ́ṣe pẹ̀lú ohun èlò rẹ́ tí ó bá fi ara rẹ̀ sílẹ̀ fún ọ láti lò.

- Nípa ọ̀rọ̀ yí, ojú kòtí rí, etí kòtí gbọ, bẹ́ẹ̀ni kò tíì wọ ọkàn ènìyàn, ohun tí Ọlọ́run fẹ́ ṣe. Màá jẹ́ri nípa ìpinu àti ìpe rẹ̀ fún ayé mi. Ìgbàlà wá láti ọwọ́ olùràpadà wa. Gbogbo ète ọ̀tá ní kòní wá sí ìmúṣẹ.

- Mo jẹ́wọ́ wípé Olúwa yóò rànmílọ́wọ́, ojú kòsì ní tìmí. Onídàjọ́ ní Olúwa, ó sì ba gbogbo ète ọ̀tá jẹ́.

- Taló dàbí rẹ́ Olúwa, ní gbogbo ayé àti ní ọ̀run, kòsí ẹni tí a lè fi ọ we. Ọ̀run ni ìjọba rẹ́wà, o sí fi ayé ṣe àpótì ìtìsẹ̀ rẹ́. Ìnà Olúwa yóò ba ìpinu ọ̀tá jẹ́ lórí ẹjọ́ yi.

- Olúwa yòó rán ìrànlọ́wọ́ láti Síonì, akò sìní dójú tìwá, bẹ́ẹ̀ni ọ̀tá kòní dẹ́rù bà wá.

- Mo pàṣẹ pé gbogbo irúgbìn tí baba mi Ọrun kò gbìn ní a ó fàtu ti gbòngbò ti gbóngbò, torí Olúwa dìde láti fúnmi ní ìsinmi àti àláfíà. Morí ohun gbogbo tí n siṣẹ́ pọ̀ fún rere lórí ẹjọ́ yi, ìdájọ́ yóò sìwà fún ojúrere mi ní Orúkọ Jésù.

- Mo dúpẹ́ Olúwa pé ò ń rómi lágbára nípasẹ̀ ẹ̀mí rẹ. Mo gbàdúrà wípé ẹ o gbàmí lọ́wọ́ àwọn ènìyàn búburú, o sì pamímọ́ kúrò nínú èrò ibi wọn. Mo pàṣẹ pé kí ògo rẹ lọ síwájú mi, kí ángẹ́lì rẹ sì fi ojúrere yímiká. Olúwa yóò pàṣẹ òdodo àti ìdájọ́ rere fúnmi, gbogbo ìpinu tí a ba sìṣe nítòri mi ni yóò jẹ́ fún ojúrere mí.

- Mo pàṣẹ wípé kòsí ọ̀rọ̀ òdì tí a sọ símí tí yóò ṣe rere. Ahọ́nkáhọ́n tí ó básì dìde sími ni a o dálẹ́jọ ní orúkọ Jésù.

## Àwàdà

### Ọmọdé a máa sọ ohun ti ń pani lẹ́rìn

Ìyá kan ń se oúnjẹ́ fún àwọn ọmọ rẹ̀, Kevin ọmọ ọdún márùn, àti Ryan, ọmọ ọdún mẹta. Àwọn ọmọ náà bẹ̀rẹ̀ síní jiyàn lórí ẹni tí yóò kọ́kọ́ jẹún. Ìyá wọn ri èyí bí ayé láti fi kọ́ wọn lẹ́kọ̀. Ó ní, tí Jésù bá wa níbí, yóò ní jẹ́kí arákùnrin mi kọ́kọ́ jẹun na, màà dúró. Kevin kọjú sí àbúrò rẹ̀, ó sì wípé, ìwọ, ṣe bíi Jésù.

# ORÍ ÌKỌKÀNLÉLỌ́GBỌ̀N

## OJÚ RERE NÍNÚ IṢẸ́ ÀTI OKÒOWÒ



## Ṣe Àṣàrò

**Àìsáyà 58:11**
N óo máa tọ yín sọ́nà nígbà gbogbo, n óo fi nnkan rere tẹ yín lọ́rùn; n óo mú kí egungun yín ó le, ẹ óo sì dàbí ọgbà tí à ń bomi rin, ati bí orísun omi, tí omi rẹ̀ kì í gbẹ.

**Orin Dafidi 84:11**
Nítorí OLÚWA Ọlọ́run ni oòrùn ati ààbò wa, òun níí ṣeni lóore, tíí dáni lọ́lá, nítorí OLÚWA kò ní rowọ́ láti fún ẹni tí ọkàn rẹ̀ mọ́ ní ohun tí ó dára.

**Orin Dafidi 90:17**
ẹ́ kí ojurere OLÚWA Ọlọ́run wa wà lára wa, fi ìdí iṣẹ́ ọwọ́ wa múlẹ̀, jẹ́ kí iṣẹ́ ọwọ́ wa fi ìdí múlẹ̀.

**Diutaronomi 28:8**
"OLÚWA yóo bukun ìkórè inú àká rẹ, ati gbogbo nnkan tí o bá dáwọ́ lé. OLÚWA Ọlọ́run rẹ yóo bukun ọ ní ilẹ̀ tí ó fún ọ.

**Iwe Òwe 10:22**
Ibukun OLÚWA ní ń mú ni í là, kì í sì í fi làálàá kún un.

**Orin Dafidi 68:19**
Ìyìn ni fún OLÚWA, Ọlọ́run ìgbàlà wa, tí ń bá wa gbé ẹrù wa lojoojumọ.

**Lefitiku 26:3-5**
"Bí ẹ bá ń tẹ̀lé ìlànà mi, tí ẹ sì ń pa àwọn òfin mi mọ́, n óo mú kí òjò rọ̀ ní àkókò rẹ̀, ilẹ̀ yóo mú ìbísí rẹ̀ wá, àwọn igi inú oko yóo sì máa so èso. Ẹ óo máa pa ọkà títí tí èso àjàrà yóo fi tó ká, ẹ óo sì máa ká èso àjàrà lọ́wọ́, títí àwọn nnkan oko yóo fi tó gbìn. Ẹ óo jẹ, ẹ óo yó, ẹ óo sì máa gbé inú ilẹ̀ yín láìléwu.

**Orin Dafidi 92:12-14**
Àwọn olódodo yóo gbilẹ̀ bí igi ọ̀pẹ, wọn óo dàgbà bí igi kedari ti Lẹbanọni. Wọ́n dàbí igi tí a gbìn sí ilé OLÚWA, tí ó sì ń dàgbà ninu àgbàlá Ọlọ́run wa. Wọn á máa so èso títí di ọjọ́ ogbó wọn, wọn á máa lómi lára, ewé wọn á sì máa tutù nígbà gbogbo

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Olúwa, mo jẹ́wọ́ wípé ní ìgbésí ayé mi, iṣẹ mi àti òwò mi, èémí rẹ̀ wà lórí rẹ̀, mo sì sọ wípé a kòní rími nípejọ àwọn ènìyàn ibi. Mo jẹ́ pípé nínú ìṣòwò mi pẹ̀lú ènìyàn àti Ọlọ́run, o sì fi ojú rere rẹ̀ bòmi.

- Mo dúpẹ Olúwa pé ọwọ yín wà lórí mí, etí rẹ ṣí láti gbọ́ mi, o sì sàn mí lẹ́san ire.

- Mo sọ wípé ẹti múmi wa síbi ńlá, ọgbà mí sì kún, n kò ṣe àìní ogún tó dára nípa ẹ̀mí Ọlọ́run. Ilé mi dára, o sì kún fún oyin àti wàrà. Ọrọ̀ àwọn kèfèrí ní a ti kówá sí wájú mi.

- Olúwa, mo dùpẹ́ fún ore-ọfẹ láti le gbé ojú mí sókè si yín, ohunkóhun kòsì le mú ojú mi kúrò lọ́dọ̀ yín. Nkò nì sín mámmónì, ṣùgbọ́n èmi yóò rántí wípé ìwọ ni Ọlọ́run tí ó fúnmi lágbára láti ní ọrọ̀.

- Olúwa, mo sọ wípé ọrọ̀ àwọn kèfèrí ni a ó kówá sí ilé wa. Idókòwò wa ní a ó kò lórí ìpìnlẹ̀ Olúwa. Gbogbo ìpìnlẹ̀ tí kìí ṣe t'Olúwa ní a ó gbá jọ sínú iná torí ìdúróṣinṣin wá wa nínú Olúwa. Ọwọ́ Olúwa wà lórí àwọn olódodo, etí rẹ̀ kòsì di sí ẹkún wọn. Olúwa, mo dúpẹ èrè ti ẹ fún àwọn tí o ṣe déédé, mo sì gbàdúrà wípé ẹ o kọ́ ọwọ́ mi láti jà lórí owo mi nítorí on darí mi, kí ó sì máa ṣọ́mi bí Olùṣọ́ àgùntàn mi.

Bàba mi, ìwọ ni olùdá ayé àti ọ̀run, mo gbàgbọ́ wípé bímo ṣé ń gbọ́ràn tímo sì ń sìn ọ́, máa lo ọjọ́ mi nínú ọ̀rọ̀, àti ìgbà mi nínú ìgbádùn.

Olúwa, ìwọ ni Olùṣọ́ àgùntàn mí, èmi kì yóò ṣe aláìní. Ó darí mi ní ọ̀nà tí ó yẹ fún ayé mí, mo sí wà nínú ìfẹ́ rẹ. Modúpẹ́ fún ojú rere lójú àwọn oníbárà mi, àti àwọn olórí mi, nítorí na, nkò ní mú ọwọ ọ̀fo lọ ibikíbi.

Bàba, mo dúpẹ́ torí ẹ ṣe asà mi. Mo jẹ́wọ́ wípé ojú rere yín ṣíwájú mí síbi gbogbo, o sì múmi ri ojú rere gbà níwájú àwọn oníbárà tó bẹ́ẹ tí wọ́n fúnmi ní ohun gbogbo tí mobá bèère fún.

## Àwàdà

### Mo dúró ní ẹnu ọ̀nà, mosì kàn kùn

Àlúfàà túntún kan tí aṣẹ̀ gbé wá sí ìlú kán ní ó lọ bẹ àwọn ọmọ ìjọ rẹ wọ ní ọjọ́ kan. Ohun gbogbo ńlọ dáradára kí o tódé ilé kan. Àmì ìdánilójú wa wípé èniyàn wà nínú ilé, ṣùgbọ́n kòsí ẹni tí ó wà ṣílẹ̀kùn fún àlúfà náà bí o tí kanlẹ̀kùn tó. Ó mú ìwé ìdánimọ̀ rẹ jáde, o sí kọ ìfihàn orí kẹta, ẹsẹ̀ ogún sí ẹ̀yin rẹ, ó wá fi há ara ilẹ̀kùn náà.

Ní ọjọ́ kejì tíí ṣe ọjọ́ ìsínmí, bí ó tín ka owo ọrẹ, o rí ìwé ìdánimọ̀ rẹ nínú igbá ọrẹ. lábẹ́ ohun tí o kósí ìwé náa ní wọn kọ Jẹ́nẹ́sísì orí kẹta, ẹsẹ̀ kẹwà sí.

Ìfihàn òrí kẹta, ẹsẹ̀ ogún sọpé: wòo, mo dúró ní ẹnu ọ̀nà, mò ń kan ilẹ̀kùn. Bí ẹnikẹ́ni bá gbọ ohun mí, tí ó ṣílẹ̀kùn, n óo wọlé tọ̀ ọ lọ́, n óó ba a jẹ́un, òún náà yóò sìbá mí jẹ́un.

Jẹ́nẹ́sísì orí kẹtà, ẹsẹ̀ kẹwà sọ wípé: ó dá Ọlọ́run lóhùn, ó ní, nígbà ti mo gbùròó rẹ́ nínú ọgbà, ẹ̀rù bàmí, mo bá farapamọ́ nítorí pe ìhòohò ni mo wà.

# ORÍ ÌKEJÌLÉLỌ́GBỌ̀N

## ÀṢEYỌRÍ NÍNÚ ÌDÁNWÒ



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 119:99**
Òye mi ju ti àwọn olùkọ́ mi lọ, nítorí pé ìlànà rẹ ni mo fi ń ṣe àṣàrò.

**Filippi 4:6-7**
Ẹ má ṣe jé kí ohunkohun dààmú yín, ṣugbọn ninu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ yín, ẹ máa fi àwọn ìbéèrè yín siwaju Ọlọ́run pẹlu ọpé. Alaafia Ọlọ́run, tí ó tayọ òye eniyan yóo pa ọkàn ati èrò yín mọ́ ninu Kristi Jesu.

**Iwe Òwe 3:5-6**
Fi tọkàntọkàn gbẹ́kèlé OLÚWA, má sì tẹ̀lé ìmọ̀ ara rẹ. Mọ Ọlọ́run ni gbogbo ọ̀nà rẹ, yóo sì mú kí ọ̀nà rẹ tó.

**Jemisi 1:5**
Bí ẹnikẹ́ni bá wà ninu yín, tí ọgbọ́n kù díẹ̀ kí ó tó fún, kí olúwarẹ̀ bèèrè lọ́dọ̀ Ọlọ́run, yóo sì fún un. Nítorí Ọlọ́run lawọ́, kì í sìí sìrègún.

**Filippi 4:13**
Mo lè ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹni tí ó ń fún mi ní agbára.

**Aisaya 41:10**
Má bẹ̀rù, nítorí mo wà pẹlu rẹ, má fòyà, nítorí èmi ni Ọlọ́run rẹ. N óo fún ọ ní agbára, n óo sì ràn ọ́ l ọ́wọ́; ọwọ́ ọ̀tún mi, ọwọ́ ìṣẹ́gun, ni n óo fi gbé ọ ró.

**Timoti Keji 1:7**
Nítorí kì í ṣe ẹ̀mí ojo ni Ọlọ́run fún wa bíkòṣe ẹ̀mí agbára ati ti ìfẹ́ ati ti ìkóra-ẹni-níjàánu.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

Olúwa, mo dúpẹ́ fún Ẹ̀mí Ọlọ́run tí ó pín sí ọ̀na meje, ẹ̀mí ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìmọ̀ràn, agbára, ìbẹ̀rù Olúwa, àti Ẹ̀mí Ọlọ́run tóju gbogbo ẹ̀mí lọ. Mo gbàdúrà wípé ẹ̀mí Ọlọ́run yóò gbé mi fò bíí ti ìdì, mosì ní àṣeyọrí ní gbogbo ìdáwọ́lé mi.

Mo yín ọ fún ẹ̀bùn Ẹ̀mí Mímọ́ tí o fún mi, tí ó le mu ohun gbogbo wá sí ìrántí mi, tí o sì fi ohun gbogbo yé mi, tí ó sì múmi taayọ.

Olúwa mi mo gba ìmọlẹ̀ rẹ láti ọ̀run wá, mo sì gba ẹ̀mí àṣeyorí láti borí ìdánwo kí dánwo.

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún ojú rere lórí gbogbo ẹ̀kọ́ mi, mo bá ẹ̀mí àṣìṣe wí ní Orúkọ Jésu.

Olúwa, mo dúpẹ́ pé ẹ mú mi mọ̀ jú àwọn akẹgbẹ́ mi lọ, ẹsì fún mi lóye ju àwọn Olùkọ́ mi lọ.

Mo dúpẹ́ Olúwa fún ẹ̀bùn Ẹ̀mí

mímọ́ tí ẹ fúnmi, tí ó lágbára láti mú ohun gbogbo wá sí ìrántí mi, tí ó sìle kọ́mi ní ohun gbogbo pẹ̀lú àwọn ìbéèrè tí n bọ̀ nínú ìdánwò mi.

- Olúwa, mo bèère fún ẹ̀mí òye lórí ohun gbogbo tí n dáni lójú rú ní àsìkò ìgbáradì, mo sì bèèrè fún ìmọ́lẹ̀ yín àti ẹ̀mí yín láti ṣe ìdánwọ̀ yíi. Àwọn ẹni ìkà kòní yọ̀ lórí òlódodo.

- Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún ojú rere rẹ lórí ẹ̀kọ́ mi, mo sì sọ wípé o kìì ṣe aláìṣòdodo láti gbàgbe ìṣẹ ìfẹ́ mi. Ọkàn mi ní àgbẹkẹ̀lé nínú rẹ, n kò sì ní rẹ̀wẹ̀sì. Akitiyan àwọn ẹni ibi yóò jású asán.

- Bàbá mi ọ̀run, mo gbàdúrà pé bí mo ti ń gbaradì fún ìdánwò mi, pé ẹ̀mí rẹ yóò darí mi, yóò mú mi dúró, yóò sì dáàbò bòmí. N kò ni ṣe lásán, bẹ́ẹ̀ni ipá mi kòní pin nínú ìdánwo yíi. Mo ní ìgbàgbọ́ fún orí pípé àti òye tí o péye. Ìrònú mí jẹ ọ̀tun, mo sì gba agbára láti le rántí gbogbo ohun tí ati kọ́mi tí mo sì ti kà, kí n le dáhùn àwọn ìbéèrè mi ní ọ̀nà tí ó yẹ ní orúkọ Jésù.

- Modúpẹ́ Olúwa fún ànfààní láti kọ́ oun túntún. Modúpẹ́ fún ààbò ré nínú ẹ̀kọ́ mi títí di ìgbà ìdánwò. Mo ko gbogbo àníyàn mi nípa ìdánwò yíi àti èsì rẹ̀ wá síwájú rẹ. Jẹ́ kí àlàáfià rẹ tí ó ju gbogbo ìmọ̀ lọ jẹ́ tèmi bímo ṣé ń retí èsì ìdánwò ní orúkọ Jésù, Àmín.

## Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n

Mọ agbára Jésù Krístì tín ṣiṣẹ nínú rẹ.

## Àwàdà

### Máṣe dásí ọ̀rọ̀ ọlọ́rọ̀

Ọmọde kùnrin kan wà nínú ọkọ kan, ó sìn jẹ ìjẹkújẹ. Ó jẹ àkọ́kọ́ tan, ó mú ìkejì, ni àgbàlagbà tí ó joko tìí bá sọ fún wípé njẹ́ o mọ̀ wípé ìjẹkújẹ á ba eyín rẹ jẹ́? Ọmọ kùnrin náà fèsì wípé, bàbá bàba mi wá láyè fún ọgọ́run ọdún ó lé díẹ̀. Àgbàlagbà ná sì wa bèèrè wípé, ṣé ìjẹkújẹ ní ó mú dàgbà tó yen ni? Ọmọdé kùnrin náà dáhùn wípé rárá o, ṣùgbọ́n, kìí dásí ọ̀rọ̀ ọlọ́rọ̀.

# ORÍ ÌKẸTÀLÉLỌ́GBỌ̀N

## ÀÁNÚ NÍNÚ ÌRÌN ÀJÒ



## Ṣe Àṣàrò

**Orin Dafidi 121:7-8**
OLÚWA óo dáàbò bò ọ́ lọ́wọ́ gbogbo ibi, yóo pa ọ́ mọ́. OLÚWA yóo pa àlọ ati ààbọ̀ rẹ mọ́, láti ìsinsìnyìí lọ ati títí lae.

**Iwe Òwe 2:8-9**
Ó ń tọ́ wọn sí ìdájọ́ òtítọ́, ó sì ń pa ọ̀nà àwọn ẹni mímọ́ rẹ̀ mọ́. Nígbà náà ni ìtumọ̀ òdodo ati ẹ̀tọ́ yóo yé ọ ati àìṣe ojuṣaaju, ati gbogbo ọ̀nà rere.

**Orin Dafidi 18:36**
O la ọ̀nà tí ó gbòòrò fún mi, n kò sì fi ẹsẹ̀ rọ́.

**Orin Dafidi 91:1-12**
Ẹni tí ń gbé abẹ́ ààbò Ọ̀gá Ògo, tí ó wà lábẹ́ òjìji Olód ùmarè, yóo wí fún OLÚWA pé, "Ìwọ ni ààbò ati odi mi, Ọlọ́run mi, ẹni tí mo gbẹ́kẹ̀lé." Nítorí yóo yọ ọ́ ninu okùn àwọn pẹyẹpẹyẹ ati ninu àjàkálẹ̀ àrùn apanirun. Yóo da ìyẹ́ rẹ̀ bò ọ́, lábẹ́ ìyẹ́ apá rẹ̀ ni o óo ti rí ààbò; òtítọ́ rẹ̀ ni yóo jẹ́ asà ati apata rẹ. O ò ní bẹ̀rù ìdágìrì òru, tabi ọfà tí ń fò kiri ní ọ̀sán, tabi àjàkálẹ̀ àrùn tí ń jà kiri ninu òkùnkùn, tabi ìparun tí ń ṣeni lófò ní ọ̀sán gangan. Ẹgbẹrun lè ṣubú ní ẹ̀gbẹ́ rẹ, tabi ẹgbaarun ni apá ọ̀tún rẹ; ṣugbọn kò ní súnmọ́ ọ̀dọ̀ rẹ. Ojú nìkan ni óo kàn máa fi rí wọn, tí o óo sì máa fi wo èrè àwọn eniyan burúkú. Nítorí tí ìwọ ti fi OLÚWA ṣe ààbò rẹ, o sì ti fi Ọ̀gá Ògo ṣe ibùgbé rẹ, ibi kankan kò ní dé bá ọ, bẹ́ẹ̀ ni àjálù kankan kò ní súnmọ́ ilé rẹ. Nítorí yóo pàṣẹ fún àwọn angẹli rẹ̀, nítorí rẹ, pé kí wọ́n máa pa ọ́ mọ́ ní gbogbo ọ̀nà rẹ. Wọ́n óo fi ọwọ́ wọn gbé ọ sókè, kí o má baà fi ẹsẹ̀ gbún òkúta.

**Iwe Òwe 3:23-24**
Nígbà náà ni o óo máa rìn láìléwu ati láìkọsẹ̀. Bí o bá jókòó, ẹ̀rù kò ní bà ọ́, bí o bá sùn, oorun yóo máa dùn mọ́ ọ.

**Diutaronomi 3:8**
"A gba ilẹ̀ náà lọ́wọ́ àwọn ọba Amori mejeeji tí wọ́n wà ní òkè odò Jọdani nígbà náà. Ohun tí ó bẹ̀rẹ̀ láti àfonífojì Anọ́ni títí dé òkè Herimoni.

## Àdúrà/Ìjẹ́wọ́

- Olúwa wa Jésù, mo bèèrè fún ojú rere rẹ́ lórí gbogbo ìrìn àjò mí àti tí gbogbo mọ̀lẹ́bí mi, mosì sọ wípé ìrìn àjò wá jẹ́ alábùkún fún. Ó fi ojúrere yí wa ká bí aṣà.
- Jésù Olúwa, mo fi ẹ̀jẹ̀ Jésù bo gbogbo ìrìn àjò mi, mo sìsọ wípé ìpamọ́ rẹ ni ìpín mi ní orúkọ Jésù.
- Olúwa, mo sọ wípé mo wà níbi ìpamọ́ rẹ, ibi jìnà sími, ó sì máa gbàmí lọ́wọ́ ìkẹkùn àwọn pẹyẹpẹyẹ àti àjàkálẹ̀ ààrùn.
- Olúwa, mo jẹ́wọ wípé ìwo yóò gbàmí nínú ìgbekùn àwọn ọ̀tá. Olúwa, mo jẹ́wọ́ wípé ìrànlọ́wọ́ mí wà láti ọ̀dọ̀ rẹ, mo sì gbé ara mí pamọ́ sínú rẹ̀, torí ìpamọ́ rẹ sìjẹ́ tèmi, ikú jìnà sí mi.
- Olúwa yóò mú ètè àwọn ọ̀tá kùnà, ìpinu Olúwa ni yóò sisẹ́ lórí ìrìn àjo mi. Olúwa yóò lọ níwájú mi láti sọ gbogbo òkè di pẹ̀tẹ́lẹ̀.
- Olúwa, mo gbàdúrà fún ọwọ ìpamọ́ rẹ lórí gbogbo ìrìn àjò mi àti tí mọ̀lẹ́bí mi, jẹ́ kí ẹ̀jẹ́ Jésù kí o bòwá. Mo jẹ́wọ́ wípé gbogbo ahọ́n ọ̀tá ni a ó pà lẹ́nu mọ́.
- Olúwa, á fi ìrìn àjò yí sí ọwọ́ rẹ, pawá mọ́ kúrò nínú gbogbo ewu. Mo gbàdúrà pé kí ẹ ṣọ́ wa, kí o sì pawá mọ́ kúrò nínú gbogbo ewu ìjàmbá. Maṣé jẹ́kí ìjàmbá ṣẹlẹ̀ sí ara wa tàbí ọkàn wa. Jẹ́kí ángẹlì rẹ pawámọ́ lọ́wọ́ ète àwọn ọ̀tá, kí o sì máa rán wa létí ìfẹ́ rẹ sí wa.
- Modúpẹ́ Olúwa fún ìrìn àjò yí, mo pàṣẹ wípé èmi kòní bẹ̀rù ohunkóhun. Àwọn ángẹ́lì rẹ́ ń ṣọ́mi níbi gbogbo tí mo bán lọ ní orúkọ Jésù.

## Ọ̀rọ̀ Àpérò

**Ohun arifin meewa ti awon eniyan maa n se ninu ile ijosin.**

1. Sísọ ọ̀rọ̀ láàrín ìsìn
2. Títẹ ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ láarin ìsìn
3. Sísùn, ká tún máa hanrun láàrìn ìsìn
4. Kí á máa gé èékáná láàrin ìsìn. Ó jẹ́ ìyàlẹ́nu bí àwọn ènìyàn tí máá ń ṣe èyí. Ẹnìkan sọ wípé ẹní tí ó wà nídí ẹ̀rọ agbóhùn sáfẹ́fẹ́ wọn ní ilé ìjọsìn rẹ̀ ń gé èékán, kòsí mo wípé gbogbo ìjọ ni ngbọ́ bí ó tí n dùn lórí ẹ̀rọ.
5. Kí á máá fi ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ pe nínú ìsìn
6. Dídìde àti jíjáde ṣáà láàrín ìsìn
7. Rírìn jáde láarin ìsìn, pàápà láàrín àdúrà
8. Fífi àyè gba àwọn ọmọdé latí máa sunkún láàrín ìsìn
9. Jíjẹ́un láàrín ìsìn. Ẹníkan láti Puerto Rico sọ wípé ó máá n bí òhun nínú tí ohun báti ń rìn àwọ́n ń jẹ́un bí ewúrẹ́.
10. Fífi ìfẹ́ hàn fún ara ẹni nínú ìjọ. Ẹ̀nikán ló ṣàròye nípa tọkọtaya kan tí ń máa fi ọwọ ra ẹ̀yìn ara wọn láàrìn ìsìn.

Jọ̀wọ́, máṣe rí Ọlọ́run fín. Má ṣà ì lọ sí ilé ìjọsìn. Lọ, kí o lọ gbọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Má ṣe rojọ́, tẹ fónù rẹ, sùn, tàbí gba ìpè nígbà tí Ọlọ́run bá n sọ̀rọ̀. Tẹ́tí sí bíi pé ayé rẹ gbáralé ọ̀rọ̀ náà.

### Ọ̀rọ̀ Ọgbọ́n

A lè yan ìhùwàsí wa. Ìdùnú jẹ yíyàn. Ìdánilójú jẹ́ yíyàn. Ká láànú jẹ́ yíyan. Fífífúni jẹ́ yíyàn. Ìbọ̀wọ̀fún ni jẹ́ yíyàn. Ohun tí o bá yàn ni yóò yàn ẹ́. Yàn pẹ̀lú ọgbọ́n.

# ORÍ ÌKẸRÌNLÉLỌ́GBỌ̀N

## ÌTÚSÍLẸ̀ NÍNÚ ÌṢÒRO



## Ṣe Àṣàrò

**Johanu Kinni 4:4**
Ẹyin ọmọde, ti Ọlọ́run nìyí, ẹ ti ṣẹgun ẹ̀mí alátakò Kristi nítorí pé ẹni tí ó wà ninu yín tóbi ju ẹni tí ó wà ninu ayé lọ.

**Orin Dafidi 34:3**
Ẹ bá mi gbé OLÚWA ga, ẹ jẹ́ kí á jùmọ gbé orúkọ rẹ̀ lékè!

**Orin Dafidi 34:17**
Nígbà tí olódodo bá kígbe fún ìrànlọ́wọ́, OLÚWA a máa gbọ́, a sì máa gbà wọ́n kúrò ninu gbogbo ìyọnu wọn.

**Orin Dafidi 107:4-6**
Àwọn kan ń káàkiri ninu aṣálẹ̀, wọn kò sì rí ọ̀nà dé ìlú tí wọ́n lè máa gbé. Ebi pa wọ́n, òùngbẹ gbẹ wọ́n, ó sì rẹ̀ wọ́n wá láti inú. Nígbà náà ni wọ́n ké pe OLÚWA ninu ìpọ́njú wọn, ó sì yọ wọ́n kúrò ninu ìṣẹ́ wọn.

**Samueli Keji 22:2-3**
"OLÚWA ni àpáta mi, ààbò mi, ati olùgbàlà mi; Ọlọ́run mi, àpáta mi, ọ̀dọ̀ ẹni tí mo sá pamọ́ sí. Àpáta mi ati ìgbàlà mi, ààbò mi ati ibi ìpamọ́ mi, olùgbàlà mi, ìwọ ni o gbà mí lọ́wọ́ ìwà ipá.

**Orin Dafidi 32:7**
Ìwọ ni ibi ìsásí mi; o pa mí mọ́ kúrò ninu ìṣòro; o sì fi ìgbàlà yí mi ká.

**Jeremaya 15:20-21**
N óo sọ ọ́ di odi alágbára tí a fi idẹ mọ, lọ́dọ̀ àwọn eniyan wọnyi. Wọn yóo gbógun tì ọ́, ṣugbọn wọn kò ní ṣẹgun rẹ, nítorí pé mo wà pẹlu rẹ láti gbà ọ́, ati láti yọ ọ́. Èmi OLÚWA ni mo sọ bẹ́ẹ̀. N óo gbà ọ́ lọ́wọ́ àwọn eniyan burúkú, n óo sì rà ọ́ pada lọ́wọ́ àwọn ìkà, aláìláàánú eniyan."

**Ekisodu 15:1-14**
Lẹ́yìn náà, Mose ati àwọn ọmọ Israẹli kọ orin yìí sí OLÚWA, wọ́n ní: "N óo kọrin sí OLÚWA, nítorí pé, ó ti ja àjàṣẹ́gun tí ó lógo. Àtẹṣin, àtẹni tí ń gùn ún ni ó dà sinu Òkun Pupa. OLÚWA ni agbára ati orin mi, ó ti gbà mí là, òun ni Ọlọ́run mi, n óo máa yìn ín. Òun ni Ọlọ́run àwọn baba ńlá mi; n óo máa gbé e ga. Jagunjagun ni OLÚWA, OLÚWA sì ni orúkọ rẹ̀. Ó da kẹ̀kẹ́ ogun Farao ati àwọn ọmọ ogun rẹ̀ sinu òkun, ó sì ri àwọn akọni ọmọ ogun rẹ̀ sinu Òkun Pupa. Ìkún omi bò wọ́n mọ́lẹ̀, wọ́n rilẹ̀ sinu ibú omi bí òkúta. Agbára ọwọ́ ọ̀tún rẹ pọ̀ jọjọ, OLÚWA; OLÚWA, ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni ó fọ́

àwọn ọ̀tá túútúú. Ninu títóbi ọláńlá rẹ, o dojú àwọn ọ̀tá rẹ bolẹ̀, o fa ibinu yọ, ó sì jó wọn bí àgékù koríko. Èémí ihò imú rẹ mú kí omi gbájọ, ìkún omi dúró lóòró bí òkítì, ibú omi sì dì ní ìsàlẹ̀ òkun. Ọ̀tá wí pé, 'N óo lé wọn, ọwọ́ mi yóo sì tẹ̀ wọ́n; n óo pín ìkógun, n óo sì tẹ́ ìfẹ́ ọkàn mi lọ́rùn lára wọn. N óo fa idà mi yọ, ọwọ́ mi ni n óo sì fi pa wọ́n run.' Ṣugbọn o fẹ́ afẹ́fẹ́ lù wọ́n, òkun sì bò wọ́n mọ́lẹ̀, wọ́n rì bí òjé ninu ibú ńlá. "Ta ló dàbí rẹ OLUWA ninu àwọn oriṣa? Ta ló dàbí rẹ, ológo mímọ̀ jùlọ? Ẹlẹ́rù níyìn tíí ṣe ohun ìyanu. O na ọwọ́ ọ̀tún rẹ, ilẹ̀ sì yanu, ó gbé wọn mì. O ti fi ìfẹ́ rẹ tí kì í yẹ̀ ṣe amọ̀nà àwọn eniyan rẹ tí o rà pada, o ti fi agbára rẹ tọ́ wọn lọ sí ibùgbé mímọ́ rẹ. Àwọn eniyan ti gbọ́, wọ́n wárìrì, jìnnìjìnnì sì dà bo gbogbo àwọn olùgbé ilẹ̀ Filistini.

**Orin Dafidi 50:15**
Ẹ ké pè mí ní ọjọ́ ìṣòro; n óo gbà yín, ẹ óo sì yìn mí lógo."

**Luku 4:18**
"Ẹ̀mí Olúwa wà pẹlu mi nítorí ó ti fi òróró yàn mí láti waasu ìyìn rere fún àwọn talaka. Ó rán mi láti waasu ìtúsílẹ̀ fún àwọn tí wọ́n wà ní ìgbèkùn, ati láti mú kí àwọn afọ́jú ríran; láti jẹ́ kí àwọn tí a ni lára lọ ní alaafia,

**Sefanaya 3:16-17**
